# IJIYA FUN KRISTI

RICHARD WURMBRAND



# IJIYA FUN KRISTI

Richard Wurmbrand

**Christian Martyrs Publication**
P.O. Box 476, Agege
Lagos—NIGERIA

Fun opolopo osu ninu aja-ile, opolopo odun ti idaloro, ijiya fun ebi ati otutu, ogbe ti opolo ati idanilori-ru Nwoyi ni Oluso aguntan omo ilu Rumania eniti nwon fi si ewon awon Komunisti fun odun merinla.

Kinni oran ti o da? Tire ati ti egoegberun awon elomiran ni igbagbo nwon ti o ye koro ninu Jesu Kristi ati eri nwon ni ita gbangba fun igbagbo won.

Nwon npade ni abele, ni ikoko ati ninu aginju, Nigbamiran a kilo fun won lati mase wasu ni gbangba tabi ni opopo ona, Awon olotito onigbagbo nwonyi ntesiwaju ninu eri won, Bi o tile se wipe nwon mo ere ise won.

Eyi ni itan won ti igboya, igbagbo ti o ye koro ati suru ti o soro lati gbagbo, bi nwon ti nfarada

**IJIYA FUN FRISTI**

## IYASOTO:

Si ini owo W. Stuart Harris, Oludari agab fun ise iranse ti awon oyinbo (European Christian Mission, London) eniti o mu ise iranse itunu awon onigbagbo ti iwo orun wa si odo mi ni kete ti a dami sile kuro ninu ogba ewon. Ni oru ni o wo ile wa, lehin opolopo ikiyesara, omu oro itunu ati ife ati pelu ebun itura wa fun awon ebi oniogbagbo ajeriiku Jesu Kristi Ni oruko won, mo fi ope wa han.

ISBN 0-88264-001-1.

# IJIYA FUN KRISTI

Ti a ti te nj ede metaleladota

Copyright (C) 1969 Tortured for Christ by Richard Wurmbrand

Published by:
**Christian Martyrs Publications**
**P.O. Box 476, Agege**
**Lagos—NIGERIA**

Printed at
**Sabina Printing Press**
V-31, Green Park, New Delhi, India.

# (TABLE OF CONTENTS)
## AWON KOKO PATAKI INU IWE YI


1. AWON ENIA RUSIA TI ONGBE EMI NGBE ______ 9
2. "IRU IFE YI TI ENIKENI KO NI" ______ 36
3. OWO IDASILE ATI ITUSILE FUN ISE IRANSE NI IWO ORUN 57
4. SISEGUN IJOBA ALASEPO NIPA EMI IFE TI KRISTI ______ 63
5. IJO ABELE TI O FARASIN TI O SI NTAN KALE ______ 107
6. BI ISIN AWON KRISTIANI SE NSEGUN IJOBA ALASEPO ___ 136
7. BI AWON ONIGBAGBO OLOMINIRA IWO ORUN SE LE RAN WA LOWO165

## NIPA ENITI O KO IWE YI

Ẹni Ọwọ Richard Wurmbrand jẹ alufa Oniwasu ihinrere, ẹniti ogbe ọdun Mẹrinla ninu ewon Ijoba Alasepo (Komunisti) ati idaloro ni ilu re ti Rumania. Ojẹ okan ninu awọn asaju awọn onigbagbọ, Olukọwe ati Olukọni ti o ni okiki pupọ. Awọn Orukọ diẹ ni a mọ ju tirẹ lọ ni ilu rẹ yi.

Ni ọdun 1945, nigbati Ijọba Alaşepọ (Komunisti) gba Rumania kan, ti nwon si gbiyanju lati ṣe akoso awọn ile isin (Ṣọsi) fun ero tiwọn. Richard Wurmbrand, lẹsẹkẹsẹ bẹrẹ isẹ iranşẹ ti o mulẹ gidi ni-kọkọ larin awọn eniyan rẹ ti a mu ni ẹru ati awọn jagunjagun ti nwọn ngbogun bọ. Laipe jọjọ, nwọn mu ni ọdun 1948, ati on ati iyawo rẹ, Sabine. Iyawo rẹ jẹ eru (Iwọfa) fun odun meta. Richard Wurmbrand lo ọdun meta ni ihamọ. On nikansoso - ni akoko yi, ko fi oju ri ẹnikẹni afi awọn asoju Ijọba Alaşepọ (Komunisti) ti nwọn ndaloro. Lẹhin ọdun meta yi, nwọn gbe lọ si yara kan ni ile ẹwọn, nbiti awọn ẹlewon pọ si. Ọdun marun ni olo ni ibiyi, nibiti idaloro ti atehinwa ko dinku.

Nitori bi ipo re ti ga to gegebi ọkan ninu awọn asaju isin Kristi ni agbaiye, awọn Oselu ti Ilu okere bebe pe ki Ijọba Alasepọ (Komunisti fun wọn wipe Richard Wurmbrand ti sa kuro ni Rumania. Olọpa inu kan, ti ọṣe bi okan ninu awọn ẹlẹwọn ti ada silẹ, sọ fun iyawo Richard pe on lọ si ibi isinku Richard ni itẹ ti ọgba ewọn. Nwọn sọ fun awọn ẹbi rẹ ti nwọn wa ni Rumania ati awọn ọrẹ rẹ ti nwọn wa ni okere wipe ki nwọn gbagbe Richard nitoripe o ti ku.

Lẹhin ọdun mẹjọ nwọn da Richard silẹ kuro ninu ẹwọn. Lẹsẹkẹsẹ, Richard tun pada

si ori iṣẹ rẹ pẹlu Ijọ Abẹlẹ. Ọdun meji lẹhin na, ni ọdun 1959, nwọn tun mu Richard, nwọn si dalẹjọ lati lọ si ewọn ọdun mejila.

A da silẹ ni ọdun 1964 nigbati ijọba dariji gbogbo awọn ẹlẹwọn, be lo si tun nba iṣẹ iwasu ti ikọkọ rẹ lọ. Awọn ẹlẹsin Kristi ti o wa ni Norway ri wipe nwọn tun fẹ sọ Olusọ Agutan Richard si ewon ni ẹketa, nipa eyi nwọn se eto pẹlu awọn alasẹ ijọba alasepọ (Komunisti) ati le fi mu Richard kuro ni Rumania. Ni akoko ti a nwi yi, awọn ijọba Alasepo (Komunisti) ti bere si 'ta' awon ẹlẹwọn won ti o ba ni se pẹlu oro oṣelu. Iye owo ti nwọn nta ẹlẹwọn kọkan je Ẹgbẹjo Naira (N1,600) sugbon iye owo ti nwọn ta Richard jẹ Ẹdẹgbata Naira N5,000).

Ni osu karun (May) ọdun 1966, ojẹri ni ilu Washington niwaju igbimọ ti Amerika ti nboju to abo ara ilu ti inu Amerika, o si bọ asọ rẹ ati sokoto ti o wa ni idi rẹ lati fi apa mejidinlogun ti idaloro gidi ti o wa kakiri ara rẹ. Agbe itan rẹ kakiri agbaiye ninu iwe han, irohin ni awon ilu U.S. (United States), Europe (Ilu Oyinbo) ati Asia. A kilo fun ni osu kẹsan ọdun 1966 wipe ijọba Alasẹpọ (Kọmunisti) ti Rumania nlepa lati pa; sibẹsibẹ ko dakẹ lori gbogbo ideruba wonyi. Awọn enia a ma pe ni "ohun Ijọ Abẹlẹ." Awọn asaju awọn Kristiani ti a ma npe ni "Ajeriku Aye" ati Paulu ti aṣọ ikele irin".

## ORO ISIWAJU

Lati ọwọ Olusọ Agutan W. Stuart Harris F.R. G.S. Alakoso gbogbo ipade isọji awon Oyinbo Onigbagbọ.

Ni osu kejila ọdun 1966 ni mo kọkọ wọ orile-ede Rumania. Saju, yatọ si orile-ede Albania, Rumania jẹ Orile-ede kansoso ni gbogbo Europe (Orile-ede awọn Oyinbo) ti nko i ti de. Fun oṣu bi melo kan, mo ti ri awọn itọkasi lati ọdọ Olorun wipe mo ni latilọ. Nipa be, emi ati eni ọwọ John Moseley kọja odi Hungari si Rumania.

Laipẹ, a se akiyesi pe a wa ni orile-ede ijọba Alasepọ (Komunisti) nibiti awọn Alasẹ ti nsọ wa tọwọtẹsẹ. Bi o tilẹ ri bẹ, awọn Onigbagbo ibẹ fi tọkantọkan gbawa. Bẹni ni irọle ọjọ isimi eyi ti ise ọjọ isimi kini ninu Ọse Iranti bibọ Jesu, a lọ si ile isin ijọ Baptisi ti Jamani (German Baptist Church) ti o wa ni Bucharest, Ni ibi yi, nwọn fun wa laye lati ki ijo ati lati sọ ẹri wa ninu igbagbọ. Nigbati ipade na pari, ọpọlọpọ ni awọn ti nwọn ba wa sọrọ. Ninu nwọn ni ọkunrin kan ti o ga ti osi ni iwa ti itara ni oju re ti o funfun osi ru. Ogba aye lati ba wa ṣoro lẹhin eyi ti o sọ wipe on ko ni kọ lati fi ara on wu ewu ti a ba le wa si ile oun. Nipa bẹ, lẹhin ti ile ti ṣu ni nkan bi ago mẹwa alẹ a lọ si ile ti Richard Wurmbrand, pẹlu iyawo rẹ ati ọmọ rẹ Mihai, ngbe ni yara kekere kan ni oke aja.

Ni aipariwo, a wọ inu ile. Lẹhinna, Oluso Agutan na, irohin ẹniti mo ti ngbọ gan ni igbati mo wa ni Iwọ Orun, tudi aṣiri gbogbo iriri

iyalẹnu ati igbala on lakoko odun merinla ti on fi wa ni ẹwọn. Saju ọmọ Richard Wurmbrand, Lẹhinna iyawo re, ti oruko re nje Sabine, jade lo lati lọ wo titi. Awọn mejeji lọ si mu irohin wa wipe awọn Ọlọpa yi ile na ka. Ọkọ-ayọkelẹ awon ọlọpa yi si wa ni ita ni odikeji ile na. Bawo ni yio ti pe to ti nwon o fi ṣọ ile na? Kini eyi yio yori si? Richard Wurmbrand,, mu itan rẹ wa si opin lehin eyi ni agbadura. Ipade adura ojọ yen ye ni iranti bi a ti bẹbẹ pe ki Olorun dabobo awọn iranse re. Awa ti ri awon ami idaloro ni ara rẹ, bẹni a si ti wa mo ni otitọ gẹgẹbi a ko ti mo ri awon ohun ibanileru ti igbani. Sibesibe bi nwon ti ndan ju gbogbo itan buruku ti iwa won ati ijiya yi, imole ogo ati ifẹ wa lara wọn. Ọlọrun gbọ adura wa ti ofi jẹpe nigbati a pada si titi, gbehingbehin, awon Olopa ti lo.

A ti ri fun igba akọko, ẹbi yi ti o ni iberu Olọrun, awọn akọni ti nwọn njẹri fun Jesu Kristi, bẹni awa mejeji ro wipe a ko tun le ri bakanna mọ. Nipa be o jẹ ohun ọla fun mi lati sọ iwe yi di mimọ. Mo si wa ṣe bẹ gẹgẹ, pelu adura gbigbona pe ki Ọlorun sọ ọpọlọpọ ọkan ji ki nwọn le fẹran awọn enia iha Ila-Orun Europe, eyiti idahun oninurere yio fi le mu iranlowo, ti o se danindanin lo fun awọn ti nwọn njiya nitori Jesu Kristi ki nwọn si kun eyiti o wa lehin ninu iponju ti Kristi ti o wa ni ẹran ara nwọn nitori ara Kristi eyiti ṣe Ijọ na.

## ORI KINNI

### Ęniti Ko Gbagbọ Pe Ọlọrun Nbę Ri Kristi

Ębi ti ko ka isin kankan si ni a gbe tọ mi. Ni igba ewe mi, nko kọ ękọ nipa ęsin. Nigbati mo ma fi pe ọmọ ọdun męrinla, mo ti ni idaniloju bęni okan mi ti le wipe Ọlọrun ko si. Eyi ję abajade igba ewe kikoro. Mo ję Ọmọ alailobi lati kutukutu aiye mi, bęni mo ti mo ọsi ni awọn ọdun inira ti igba ogun agbaye kini. Ni omo odun merinla, idaniloju temi nipe Ọlọrun ko si şe gegę pęlu ti awọn Ijọba Alaşepọ ọjọ oni. Mo ti ka awọn iwe ti nwọn kọ lori esin igbagbọ nipa iwalaiye Ọlorun, ki si işe pe nkọ ni igbagbọ ninu Ọlọrun tabi Kristi. Mo korira awọn imọ bawọnyi. Mọ si nro wọn pe nwọn ję okan ipanilara fun iye enia. Nipa bę, mo dagba ninu ikoro si isin Ọlorun.

Sugbon gegebi oye ti ye mi lehinna, mo ni ore ọfę lati ję okan ninu awọn ayanfę Ọlọrun fun idi ti ko ye mi. Awọn idi wọnyi ję eyiti ki ise ti eyikeyi ninu iwa mi, nitoripe iwa mi buru jai.

Bi o tilę jępe alaigbagbọ ninu iwalaye Ọlọrun ni mi, ohun kan eyi ti ko yemi ma nfa mi nigbagbogbo lọ si ile isin. O ni mi lara lati kọja ni tosi ile isin ki nma si wọle. Sibęsibe, oye ohun ti nwon nse ni ile isin wọnyi ko ye mi. Mo fetisi awọn iwasu, sugbọn ko ni itumọ kankan si mi. O damiloju gbangba pe Ọlọrun ko si. Mo korira awon imo isina ti pe Olorun ni alakoso eniti mo ni lati teriba fun. Bakanna,

mo korira imo isina ti Ọlọrun eyi ti mo ni ninu ọkan mi. Sugbọn mo ni ife pupọ lati mọ wipe ọkan ti o ni ifẹ gidi wa ni ibikan larin agbaiye.

Mo ti mọ diẹ ninu aye igba ewe ti ọdọ. O ti nwu mi pe ki ibikan wa, ti ọkan ti o ni ifẹ mi, ti o si nwa mi wa.

Mo mọ pe Ọlọrun ko si. Nigbakan, ninu ijakadi ti emi, mo wọ inu Ijọ katoliki kan, mo ri awọn enia ti nwọn nkunlẹ, ti nwọn si nwi ohun kan nibẹ. Mo ba ronu wipe, ngo kunle nitosi wọn, ngo kọ ohun ti nwọn nwi ngo si ma wi lati ri bi ohunkohun yio ṣẹlẹ. Nwọn ngbadura si wundia Mimọ: "Alafia, Maria, ẹni ti o kun fun ore ofẹ." Mo nsọ eleyi tẹle wọn lera lera, mo wo ere Maria Wundia ṣugbọn ohunkohun ko ṣẹlẹ. Ọkan mi bajẹ gidigidi nipa eyi.

Ni ọjọ kan, bi mo se ni idaniloju pe Ọlọrun ko wa, mo gbadura si Ọlọrun. Adura mi lo bayi: "Ọlọrun mo mọ dajudaju pe o ko si. Ṣugbọn boya o wa, eyiti mo jiyan rẹ, ko ki ise ẹtọ mi lati ni igbagbọ ninu Rẹ, ẹtọ Rẹ ni lati fi ara Rẹ han fun mi." Mo je eniti ko gbagbọ pe Ọlọrun nbẹ, sugbọn igbagbọ mi yi ko fun ọkan mi ni alafia.

Ni akoko idamu ti o ti inu wa yi - gẹgẹbi mo ti ri lẹhinna, ni abule kan ti o wa loke ni awọn oke giga ti Rumania, gbẹnagbẹna arugbo kan ngbadura bayi: "Ọlọrun mi, mo ti sin Ọ ni aiye, beni mo fẹ lati gba ere ni aiye yi ati ni ọrun pẹlu. Bẹni mo fẹ ki ere mi jẹ pe ki nmase ku titi ngo fi mu Ju kan tọ Kristi wa, nitoripe Jesu wa lati ọdọ awọn Ju. Ṣugbọn nko lowo, mo darugbo beni alaisan ni mi, nko le rin kiri lati wa Ju kan Ni abule mi, ko si okankan Mu Ju kan wa si abule mi, emi yio si sa ipa mi dopin lati le mu onitọhun tọ Kristi wa."

Ohun kan eyi ti nko le bori fa mi lo si abule yẹn. Nigbati Gbẹnagbẹna ri wipe Ju ni

mo ję, o mu mi ni orę ju bi ati șe le mu obinrin ti o lęwa ni orę lọ. O ri wipe emi ni idahun adura re, o si fun mi ni Bibeli lati ka. Mo ti ka Bibeli ni opolopo igba ri lati le fi la oju si șugbọn Bibeli ti okunrin yi fun mi ję orișì Bibeli miran. Gęgebi o ti so fun mi lęhinna, o gbadura fun wakàti aimoye pęlu iyawo rę fun iyi-lọkan pada mi ati ti iyawo mi. A ko ko Bibeli ti o fun mi pęlu ọrọ pupo, Șugbọn pęlu ina ifę ti a nkọ nipa adura re. Agbara kaka ni mo fi ka. Ekun nikan ni mo le sun le lori bi mo ti nfi igbesi aiye mi buburu we igbesi aiye Jesu: iwa aimo mi pęlu iwa mimọ Re: Ikorira mi pelu ifę ti Rę: O tewọgba mi lati ję ọkan ninu ti Re.

Laipę lęhin mi, iyawo mi na yi ọkan pada, o mu awọn ọkan miran tọ Jesu wa, bẹni awon okan miran wonyi tun mu awon miran to Jesu wa nipasę eyiti ijọ titun ti Luther fi dide ni Rumania.

Wayi, akoko ti awọn Nasi de. Opolopo nkan lo wa fun wa lati jiya re. Ni Rumania, eto awọn Nasi npasę tipatipa, eyi ti o nfi iya ję awọn ti nwọn ntenumo otitọ ati pęlupęlu awọn Ju.

Ki ato fun mi ni oye alufa, ati ki nwọn to șe eto imura mi fun ișę iwasu, emi gan to ję asaju ijọ yi, niwọn igbati o ti ję emi ni mo da ijọ na silę. Emi ni mo ru ęru ijo yi. Opọlọpọ igba ti olopa ti mu mi ko ni iye pelu iyawo mi, nwọn lu wa, bẹni nwọn si ru wa de iwaju awon adajọ Nasi. Ipaiya awọn Nasi yi pọ sugbọn die lo ję lara ti awon Onijoba Alașepọ. A ni lati fun omo mi Mihai ni orukọ ti ki ise ti awon Ju lati le fi gba ęmi rę la.

Șugbọn anfani nla kan wa ni inu akoko ti awon Nasi yi. Nwọn fi ye wa pe a le farada nina ti ara, ati pęlu pe emi ọmọ eniyan, pęlu iranlọwọ Olorun, le roju ninu gbogbo idaloro. Nwon ko wa ni ogbon ti a fi nse ise Onigbagbo ni ikoko eyiti o je imura sile fun idanwo ti o

tun le gan ti o nbo ni iwaju - eyi ni idanwo lile ti o nbọ ni iwaju wa lẹhin eyi ti o nkọja yi.

## ISE IRANSE MI SI AWON ENIYAN RUSSIA

Pẹlu abamo pe mo ti je eni ti ko gbagbọ pe Ọlọrun nbẹ, lati ọjọ ti mo ti yipada ni mo ti nfẹran ati le jeri fun awon eniyan Russia. Awọn eniyan Russia jẹ awọn ti a ti ko lati kekere wa pe Kosi Ọlọrun. A mu ifẹ mi lati de odo awon eniyan Russia yi sẹ. Imuse rẹ bẹrẹ ni akoko awọn ti Nasi, nitoripe ni Rumania egbẹrun aimoye ni awọn ẹru ti a ko ni Russia, aye si wa fun wa lati se ise onigbagbo ni arin won.

Iṣẹ na nlọ pẹlu iyanu. Nko jẹ gbagbe iba pade mi pẹlu ẹru Russia kan. O so fun mi wipe ẹlero (an Engineer) ni ohun. Mo bi lere boya o ni igbagbọ ninu Ọlọrun Bi oba ṣe wipe o sọ wipe "rara", emi iba ti fi ọkan si pupọ. Ẹtọ eniyan kokan ni lati gbagbọ tabi lati ma gbagbo. Sugbon nigbati mo bi lere boya o ni igbagbọ ninu Ọlọrun, ogbe oju sodo mi laisi oye, osi ni 'A ko fun mi ni aṣẹ tabi anfani be lati gbagbo. Ti aba fun mi ni aṣẹ, emi yio gbagbọ.

Omi da ni oju mi. O dabi wipe a ya ọkan mi si wẹwẹ. Okunrin kan ni eyi ni iwaju mi, eniti iye rẹ ti ku, okunrin ti o ti padanu ẹbun ti o tobi julọ eyiti Ọlọrun ti fi fun ọmọ-araiye - eyi ni lati le jẹ ẹniti ara rẹ. Ojẹ ohun elo ti a ti gba agbara ọpọlọ rẹ ni ọwọ awọn ijọba Alaṣepọ (Komunisti), o si ṣetan lati gbagbọ tabi ma gbagbọ lori aṣẹ, ko le ronu mọ ni ti ara rẹ. On yi jẹ aworan ọmọ Russia lẹhin gbogbo ọdun ti Ijoba Alasepo (Komunisti) yi ti bori! Lẹhin Ijaiye ati riri ohun ti Ijoba Alasepo (Komunisti)

ti ṣe si ọmọ eniyan, mo ṣe ileri fun Ọlọrun wipe ngo ya aiye mi sọtọ fun awọn eniyan wọnyi lati fi iye nwọn pada fun wọn ati lati fun wọn ni igbagbọ ninu Ọlọrun ati Kristi.

Ko di igba ti mo ba lọ si Russia ki nto le de ọdọ awọn eniyan Russia.

Bẹrẹ ni ọjọ ketalelogun osu kẹjọ ọdun 1944, ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun ọmọ-ogun awọn ọmọ Russia ni nwọn wọ Rumania, ati wipe laipe lẹhin eyi awọn ijọba Alaṣepọ (Kọmunisti) gba agbara ni ilu wa. Iya nla kan wa bẹrẹ eyi ti o jẹ ki ijiya ni abe awọn Nasi dabi ẹnipe o rọrun.

Ni akoko yẹn, ni Rumania, eyiti iye eniyan ti o wa ninu rẹ jẹ ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun mejidinlogun, awọn Ijoba Alaṣepọ (Komunisti) ni eniyan ẹgbẹrun mẹwa pere. Sugbon Vishinski eniti o jẹ akọwe Soviet Union ni ilu okere fi agbara wọ ibi ise Oba wa ti a feran pupọ, Michael kini, o si fi ese lu ori tabili o wipe "O ni lati yan awọn asoju Ijọba Alasepọ si ori aga Ijọba." Nwon gba ohun ija lọwọ awọn ọmọ-ogun wa ati awọn Ọlọpa; ati pe, nipa ipa eyiti opolopo eniyan korira, awọn ijọba alaṣepọ (Komunisti) gba agbara. Ki si ise laisi isowọpọ awọn alakoso ti Amerika ati ti ilu Oyinbo ti akoko igba na. Ki iṣe fun ẹsẹ ti ara wọn nikan ni awọn eniyan yio dahun niwaju Ọlọrun, ṣugbọn nwon yio dahun fun ese ti orile-ede pẹlu ọrọ ibinuje ti gbogbo orile-ede ti ako lẹru nipa aikiyesara awon Kristinai American ati Britain. Awọn eniyan Amerika ni lati mọ wipe nwon ti ran Ijoba Russia lọwọ laimọ, lati fi ipa gbe ijoba apaniyan ati amunisin le wa lori. Awon eniyan Amerika ni lati fopin si eleyi nipa riran awọn eru wọnyi lọwọ lati wa si imọlẹ Kristi.

## EDE IFE ATI EDE IWA ETAN, OKANNA NI

Bi Ijoba Alasepọ (Kọmunisti) ti gba agbara, nwọn fiogbongbon lo ọna iwa ẹtan si ọdọ Ijọ. Ede ifẹ ati ede iwa ẹtan ọkanna ni. Ẹniti onfẹ omobirin fun iyawo ati ẹniti o nfe lati lo ni ilokulo ni alẹ kan, lehineyi ti yio tari rẹ sọnu, awọn mejeji ni yio sọ wipe "Mo ni ifẹ rẹ." Jesu ti sọ fun wa wipe ki a mọ iyato larin ede ẹtan ati ede ife ati lati mọ iyatọ larin ikoko ati agutan totọ.

Nigbati awọn ijọba Alasepọ (Kọministi) gba ijọba, ẹgbẹrun aimoye alufa ati ojiṣẹ Ọlọrun ni ko mọ bi awọn ṣe le fi iyatọ si arin awọn ohun mejeji.

Awon ijoba Alaṣepọ (Kọmunisti) yi pe apejọ ti gbogbo awọn ẹgbẹ Onigbagbọ si ile ajọ Oba. Awọn ẹgbẹrun merin alufa ati ojise Ọlọrun lati gbogbo ijọ ni o wa ni ibẹ. Awọn egbẹrun mẹrin alufa ati ojiṣẹ Ọlọrun wọnyi yan Joseph Stalin gegebi alaga ọlọla ti ajọ yi. Bakanna ni osi tun jẹ alaga ẹgbẹ ti agbaiye awọn ti ko ni Ọlọrun ati ti pipa awon Onigbagbọ ni akopọ. Ẹnikan lẹhin ẹnikan, awọn Olori awọn alufa ati awon alufa a dide ni ibi ile ajọ Ọba wa nwon a si kede wipe ijoba alasepọ ati isin Kristi jẹ Okanna ni ipilẹsẹ ati pe nwọn le jijọ wa pọ. Awon iranṣẹ Ọlọrun nfi ọkan kan sọ ọrọ iyin si ijoba Alasepọ (Komunisti) yi; nwọn tilẹ nfi ye ijọba titun yi pe Ijọ yio ṣe ọto pelu won.

Iyawo mi pelu emi wa ni ibi apejọ yi. Iyawo mi joko ni tosi mi, o si sọ fun mi pe "Richard, dide kio si yọ itiju yi kuro ni oju Kristi; Nse ni nwọn ntutọ si Kristi loju".

Mó si so fun iyawo mi pe "Ti mo ba se be, o padanu ọkọ rẹ." O si sọ pe "Nko fe lati ni okunrin ojo ni ọkọ."

Mo ba dide mo si sọrọ ni apejọ yi, nko yin awọn ti npa awon onigbagbọ, sugbọn mo yin Kristi ati Ọlọrun mo si sọ wipe iṣẹ otọ wa tọ si Kristi ṣaju. Awọn ọrọ ti ibi apejo yi ni gbogbo ilu gbo, eyi si je ona fun wa lati wasu ihinrere Kristi lati ibiti awọn ijọba Alaṣepọ (Komunisti) ti pejọ! Nigbehin, mo ni lati jiya ohun ti mo se, sugbon o jẹ ohun ti o yẹ.

Awon olori ti ipilese ati awon olori ijo ti o tun yapa kuro lara ti ipilese yẹn njijadu larin ara won lati yọda fun ijọba Alasepo. Olori awọn alufa ti ijọ ipilẹse kan fi ami ijoba alasepo eyiti ise Olu ati doje si ara asọ rẹ. O si so fun awon alufa rẹ pe ki nwọn ma pe on ni "Ore-ọfẹ rẹ" mo, sugbon ki nwon ma pe on ni "Bisobu Ẹlẹgbẹ". Mo lo si apejọ eyi ti awọn ijọ Baptisi ni Ilu Reista - apejọ eyi ti o wa labẹ Asia pupa, nibiti nwọn ti gbe ko orin iyin si Soviet Union pelu Olukuluku ni iduro. Alaga awon ijo Baptisi polongo pe Stalin ko se nkan miran ju lati pa ofin Olorun mọ. Oyin Stalin gegebi Olukoni ti Bibeli ti o gborin! Awon alufa bi Patraskoiu ati Rosianu so ọrọ tara.

Nwọn sọ wọn di Olori ninu awọn Olọpa inu. Rapp, eniti iṣe igba keji Olori awọn alufa ti Ijọ Luther ni Rumania bẹrẹ si kọ awon eniyan ni ẹkọ ni ile ẹkọ giga ti Bibeli pe Ọlọrun fun ni ifihan meta: Ọkan nipa ọwọ Mose, Ọkan nipa ọwọ Jesu ati ẹkẹta lati ọwọ Stalin, ati pe eyi ti ikẹhin yi ju eyi ti osaju re.

A ni lati ni imọ pe awọn ijọ Baptisi totọ, awọn ti mo feran pupo, ko gba, nwọn si se olotọ gidigidi si Kristi, nipa eyi ti nwọn fi jiya pupọ. Sibẹsibẹ, awọn ijọba Alasepo 'yan' awọn asaju nwọn, awọn ijọ Baptisi wọnyi ko si ni aye ati yan ifẹ wọn bikoṣepe ki nwon gba awọn asaju ti a yan. Bakanna ni osi ri ni oni

nipa ti awọn Olori julọ ti isin.

Awon ti nwon di iranse ijọba alaṣepọ dipo ti Kristi bẹrẹ si sẹ awọn arakunrin won ti ko darapọ mọ wọn.

Gegebi awọn ẹlesin Kristi ti Russia ti da Ijo ti Ikọkọ silẹ lẹhin isọtẹ awọn eniyan Russia, Gbigba Ijọba ti awọn ijoba Alasepo gba ijọba ati ofofo ti ọpọlọpọ awọn olori ijọ ti nwon je asoju. Ijoba mu ki awa na fi dandan le lati da iru Ijoba ikoko yi silẹ ni Rumania, eyiti ofi otito iwasu ihinrere ati lati tọ awọn ọmọde sipa ọna ti Kristi han. Ijoba alasepọ ka gbogbo eleyi si iṣelodi bẹni Ijọ ti Ijoba alasepo da silẹ na gba bẹ.

Ni ifọwọsowọpọ pẹlu awọn ẹlomiran mo bẹrẹ iṣẹ ikọkọ ni arin ẹgbẹ. Mojẹ ẹnikan ti gbogbo eniyan bu ọla fun eyiti koni ohunkohun lati se pelu iṣẹ isọji ti ẹgbẹ Luther ti Norway bakanna mosi tun nse aṣoju ti ajọ igbimọ Ijọ ti agbaiye ni Rumania. (Ni Rumania ako ni oye kan pe ikojọ yi yio jewa ni irepo pẹlu awon Ijoba Alaṣepọ. Ni akoko ti a nwi yi nwon koṣe nkan miran ju iṣe iranlowo ni ilu wa). Awọn oye meji yi muki nle ni iduro ti o mulẹ niwaju awọn alaṣẹ tiko mọ nipa ise abẹlẹ mi.

Eyi ni eya meji: ekini je ti iṣẹ iranṣẹ ihinrere ikọko wa larin awọn ọmọ-ogun Russia ẹgberun lọna ẹgberun.

Eya keji jẹti iṣẹ iranṣẹ ihinrere abẹlẹ wa si awọn eniyan Rumania ti akc leru.

## AWỌN ENIYAN RUSSIA - AWỌN ENIYAN TI "ONGBẸ" ỌKAN NGBẸ

Nitemi, lati wasu ihinrere fun awon eniyan Russia jẹ bi ọran ninu aiye. Moti wasu ihinrere yi fun awọn eniyan ti aimoye orile-ede, sugbon nko tiri ẹnikan ti ofi gbogbo ara ati ọkan gba ihinrere yi bi awọn Russia. Ongbẹ okan yi ngbẹ wọn gidi ni.

Alufa Ijọ ti Ipilẹsẹ kan, eniti ojẹ ọrẹ mi bami sọrọ ni ori ẹrọ foonu, osi sọfun mi pe Oloye Russia kan tiwa ba oun lati jẹwọ. Ọre mi yi kosi gbo ede Russia. Nigbati osi mọ wipe emi leso ede Russia, oko oruko ibiti mo ngbe fun oloye yi. Ni ojọ ti o tẹle eyi, okunrin yi wa si ọdọ mi. Oni ife Olorun, o nwa lati mọ Ọlọrun, ṣugbọn ko iti ri Bibeli kan ri. Ko tilo si ile isin ri (ile isin ṣe ọwọn pupọ ni Russia) Ako komi ni eko isin ri. Oni ife Ọlọrun lai ni oye kan nipa Ọlọrun.

Mowa bẹrẹ si ika iwasu lori oke ati awọn owe Jesu sii leti. Lehin igba ti ogbọ won, ojo yika inu iyara pẹlu ayọ nla, o npolongo pe: "Iru ẹwa iyalẹnu wo ni eyi! Bawo ni mose lema gbe igbe aiye mi lai mo Kristi yi!" Eyi je igba kini ti ngo ri eniyan ti okun fun ayo nla ninu Kristi.

Ṣugbọn mose asise kan. Moka ijiya ati ikan-mọagbelebu Kristi sii leti, lai mu wa ni imurasile fun eyi. Ko reti re. Bi osi tiwa gbọ bi nwọn tiṣe lu Kristi, bi ati ṣe kan mọ agbelebu ati bi oti se wa ku ni igbẹhin, o subu.

si inu aga kan osi bere si sun ekun kikoro. Oti ni igbagbo ni inu Olugbala kan, Olugbala na siti ku nsisiyi!

Mo woo, oju si timi pe moti pe ara mi ni Onigbagbọ, ati alufa, eniti oti nko awọn miran. Nko tii ni ipin ninu ijiya Kristi ri bi okunrin Oloye Russia yiti nni ipin ninu rẹ bayi. Bimo ti nwoo, o dabi enipe mo tun nri Maria Magdaleni ti o nsun'kun ni ẹsẹ agbelebu, ti o nsun' kun nitoto papa nigbati Jesu jẹ oku ni inu iboji.

Nigbana nimo wa ka itan ajinde sii leti. Koti mope Olugbala oun jinde kuro ninu iboji. Nigbati o gbo irohin iyalenu yi, olu orunkun re osi bura aimo, sugbon bimo ti ro, ibura "mimo" gan ni. Eyi ni ona oro rẹ tiko ni ero. Osi tun yo. O nkigbe pelu ayo: "O ye! O Ye!" O si tun jo kakiri yara pelu ekunr rere ayo!

Mo wi fun u, "Jẹki a gbadura!" ko mo ohun ti njẹ adura. Ko mo awọn gbolohun oro mimọ wa. A jijọ kunle ni ori ekun wa, awon ọrọ adura rẹ silọ bayi: "Ọlọrun, ọmọdekunrin dada ni ọ! Ti o ba je wipe emi ni iwo ti osi je wipe Iwo ni emi, emi kiba ti dari ese re jiọ. Sugbọn dajudaju, omodekunrin dada niỌ! Mo fẹran rẹ lati inu gbogbo ọkan mi."

Moro wipe gbogbo awọn angeli ti owa ni ọrun ni o dawọ ohun ti nwọn nse duro lati gbo adura ti oni ọla yi lati enu Oloye Russia kan. Atijere ọkan rẹ fun Kristi!.

Ni ile-oja kan, moba ọgagun Russia kan pẹlu obinrin Oloye kan. Nwọn nra orisirisi nkan bẹni nwọn ni isoro diẹ nipa biba oloja tita sọro nitori ko gbo ede Russia. Moso wipe

ngo ran wọn lọwọ lati tumọ ohun ti nwọn basọ fun ọlọja tita yi, asi di ọre. Mope wọn ki wọn pe ''Ile Onigbagbọ ni ẹwa, awa sini ise ati gbadura.'' Mo gba adura nani ede Russia. Nwọn siko amuga ijẹun ati ọbe wọn silẹ, nwon ko sini ifẹ ati jẹun mọ. Nwọn bere si bere ọpọlọpọ ibere nipa Ọlọrun, Kristi ati Bibeli. Nwon ko mo ohunkohun.

Kojẹ ohun irọrun lati sọrọ si wọn. Mose owe okunrin ti oni ogọrun agutan, ti osi so ọkan nu fun wọn. Ko ye won. Nwọn se ibere bayi pe: ''Bawo ni oti ṣejẹ, ti ofi ni ọgọrun agutan? Ṣe oko apapọ ti Ijọba ṣepọ ko ti ko wọn lọ ni? Ni moba sọ wipe Ọba kan ni Jesu. Nwọn tun dahun nwon ni: ''Gbogbo awon Oba ni nwọn tije ọkunrin buruku ti nwọn tini gbogbo eniyan lara, Jesu si nilati jẹ oniwa bayi''. Nigbati mosọ owe awon osisẹ inu ogba ajara fun won, nwon ni: ''Beni, awon okunrin wonyi se dada lati ṣọtẹ si okunrin ti oni ọgba ajara na. Ọgba ajara na nilati je ti gbogbo eniyan.'' Gbogbo nkan ni oje titun fun won. Nigbati moso fun won nipa ibi Jesu, nwọn se ibere kan eyiti yio jẹ ọrọ odi leti awon eniyan Iwọ Ọrun, nwọn ni: ''Maria hajẹ iyawo Ọlọrun bi? Mosi wari oye lati inu ifi ọrọ we ọrọ mi pẹlu wọn ati ọpọlọpọ awọn miran wipe lati wasu ihinrere fun awon eniyan Russia lẹhin ọpọlọpọ ọdun ti Ijoba Alasepo , ani lati lo ede titun patapata

Awon Onisẹ Ọlọrun ti nwon losi Ipinlẹ Arin Afrika ni isoro lati tumọ ọrọ Isaiah ti oni: ''Ti ẹsẹ nyin ba pupa bi alaari, wọn owa di funfun bi Sno'' Kosi enikan ni Ipinle Arin

Afrika ti oti ri sno ri. Nwọn kosi ni ọrọ fun sno. Nwon ni lati tumọ rẹ ese nyin yio wa funfun bi koro agbon."

Nitorina a nilati tumo ihinrere si ede ti awon ti ntelẹ ilana Marx ati lati mu u wasi oye won oje nkan ti ako leṣe nipa ara wa, sugbọn Emi Mimo ni Ose iṣe Re lati ọwọ wa.

Ogagun yi ati obinrin Oloye yi ni nwon di eni igbala ni ọjọ ti ajọ ni ọrọ pọ yi. Lẹhinna, nwọn ran wa lọwọ pupọpupọ ninu iṣe iwasu wa ti abẹlẹ si awọn eniyan Russia.

Awa ntẹ iwe ihinrere ati awọn iwe kika fun awon Onigbagbo ni ikoko, ti won ti gba Jesu gbọ, a wa nri aye ati kọ ọpọlọpọ Bibeli ati awon apa Bibeli wo Russia.

A tun ma nlo ogbon miran lati fi muki awon atunko oro Ọlọrun de ọwọ awon eniyan Russia. Awọn Ọmọ-ogun Russia ti nja fun ọpọlọpọ ọdun, beni ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ ni ile ti wọn ko iti ri gbogbo igba wonyi. (Awon eniyan Russia ni ife ọmọ pupọ). Ọmọ mi, Mihai, pelu awon omo kekeke miran ti nwon koju ọdun mẹwa lọ yio losi ọdọ awọn Ọmọ-Ogun Russia wọnyi ni ori titi ati ni arin awon ogba iṣere nla, wọn si ngbe ọpọlọpọ Bibeli, iwe ihinrere ati awọn iwe kika miran ni apo wọn. Awon Ọmọ-Ogun Russia wọnyi yio fi ọwọ lu wọn jeje ni ori, nwọn asi tun ba won sọrọ pẹlu ifẹ, nwọn oma ro nipa ti ọmọ awon ti awon ko tiri fun odun pupọ. Awon Ọmọ-ogun wonyi yio fun awọn ọmọ ni ipanu, awọn omode na yio sifun awon Ọmọ-ogun wonyi ni nkan pada. Bibeli ati awon iwe ihinrere, eyiti awọn Ọmọ-ogun wonyi ngba pẹlu

itara. Ni opolopo igba, ohun ti o lewu ni inu Ijo Abẹlẹ ni owo te ti asi na gidigidi fun eleyi, sugbon nwon kose ofofo ipejopo wa.

Lakoko iṣẹ yi ani ayọ ati ba awon ara wa lati ijọ Abẹlẹ ti Russia pade ati lati gbọ nipa iriri wọn. Saju, ari ise Emi Mimo ti o gaju ninu wọn. Nwọn ti gba ọpọlọpọ odun kọja ninu eyiti ati nfi ipa kọ wọn ni ẹko ti aigba Ọlorun gbọ! Awon miran ninu wọn ni oti losi ile ẹkọ giga ti Unifersity ti awọn Ijoba Alaṣepo, sugbọn bi ẹja ti ma ngbe inu omi ti oni iyọ ti osi ma nlẹ da eran ara rẹ si ti ofi ndun, nwon losi ile-ẹkọ ti awọn Ijọba alaṣepọ, sugbon nwọn pa ọkan wọn mọ ti osi funfun ninu Kristi.

Awọn Onigbagbọ Russia wọnyi ni ẹmi ti o dara. Nwon sọ wipe: "Awa mọpe irawo pẹlu ilu ati doje ti o nwa ni iwaju fila ti a nwo je irawo asodi si Kristi." Nwon sọ eleyi pelu ibanuje ti opọ. Nwon ran wa lọwọ pupọpupọ lati tan ihinrere yika larin awọn Ọmọ-ogun Russia ti oku.

Mole sọ wipe gbogbo ire Onigbagbo ni nwọn ni, afi ire ayọ. Eyi nikan ni nwọn ma nni nigba ti nwọn bayi pada. Nigbana yio farahan. Mowa nro pẹlu iyalẹni pupọ. Nigbakan mose ibere kan lọwọ Ijọ Baptisi kan wipe: "Bawo ni oko ṣe ni ayọ?" O dahun: "Bawo nimo ṣele kunfun ayọ nigbati ojẹ wipe moni lati mafi ara pamọ fun alufa Ijo wa 'pe Onigbagbọ toto ni emi ise, wipe mo ngbe igesi-aiye adura. 'pe mo nigbiyanju lati jere ọkan? Alufa Ijọ waje eniti nse ofofo fun awọn Ọlọpa inu. Awọn ara wa ni nwọn nse ami ara wa beni awọn Oluṣọ-

Agutan ni nwọn si nse ofofo awon agbo agutan. Ayọ igbala wa ninu wa lohun, ṣugbon inu didun ti ita ti iwọ niyi - awa kole ni mọ.

''Ise Onigbagbọ ti dabi ere pẹlu wa. Nigbati ẹnyin Onigbagbọ ti ẹwa ni ominira ba jere ọkan kan fun Kristi, e jere ẹya ara Ijo ti o wa laye jẹjẹ. Ṣugbọn nigbati awa ba jere okunrin kan, amọ wipe ni kete oun nlọ si ẹwọn, ati pẹlu wipe awọn ọmọ rẹ ledi alainibaba. Ayọ wipe amu enikan to Kristi wa ma ndapo mọ imọ yi pe iye kan wa ti ani nilati sun.''

Ati ba orisi awọn Onigbagbọ miran pade ti nwọn yato gidigidi: awon Onigbagbo ti Ijọ Abẹlẹ.

Ni ibi ni ati ri iyalenu pupọ.

Gẹgẹbi oti jẹ wipe ọpọlọpọ ni owa ti nwọn gbagbọ pe Onigbagbọ ni awọn ṣugbon ti o je wipe nitoto nwọn ojẹ Onigbagbọ bena ni ari 'pe ọpọlọpọ ni owa ni arin awon eniyan Russia ti nwọn gbagbo wipe awọn oni-igbagbo ninu Ọlọrun sugbọn ti ojẹ wipe niti otito, kori be pẹlu won.

Nigbakan, ọkọ ati iyawo, awọn eniyan Russia kan wa ni iwaju mi, ti nwon je Onisọna okuta. Nigbati mo sọrọ si wọn nipa Ọlọrun, nwon dahun bayi: ''Rara Ọlọrun ko wa. Awa ni ''Besboshnikilai si Ọlorun. Ṣugbọn ao sọ nkankan ti o dun ti o ṣẹlẹ si wa.

''Nigbakan ri, a nse ona si okuta Stalin. Bi ati nsise nalọ iyawo mi bimi ni ibere oni: ''Ọkọ mi, bawo niti atampako? Ti ako ba lese ki atampako tako awon ika iyoku - ti awon ika ti ọwọ ba dabi ti ẹse - a kiba ledi Olu irin, olu igi, ohun isise kankan, iwe tabi buredi kekere

mu. Igbesiaiye Ọmọ eniyan koni sese tiko ba si atampako kekere yi. Wayi o, tani eni ti oda atampako yi? Awa mejeji ni ako igbagbo Marx ni ile eko asi mọ wipe ọrun ati aiye ni owa fun ara wọn. Ọlọrun kọni o da wọn. Bẹni moti kọ, bẹni mosi gbagbọ. Sugbon ti Olorun koba da orun ati aiye, ti oba je atampako yi nikan ni o da, oye ni eniti aba yin fun nkan kekere yi.

"A nyin Edison ati Bell ati Stephenson awọn ti o dọgbọn atupa ina mọnamọna, ero fonu, ati ọna ọkọ ilẹ ati awọn nkan miran. Ṣugbọn kini idi rẹ ti ako fini yin ẹniti o dọgbọn atampako? Ti Edison koba ni atampako, kiba tile dọgbọn ohunkohun. Eto gidi loje lati bu ola fun Ọlọrun ti o da atampako."

Inu sibi ọkọ yi gidigidi bi awọn ọkọ ti ma nse nigbati awọn iyawo wọn baso ọro ti omu ọgbọn wa fun wọn. "Maṣe sọ ọro omugọ oti kọ ẹko pe kosi Ọlorun. Oko sile mọ lailai boya ile yiwa ninu ewu ati bi awa oba ni subu sinu wahala. Fisi inu kan lekan ati titi wipe kosi Olorun. Ni orun kosi enikẹni!"

Iyawo re dahun oni: "Eyi tun je iyalenu ti otun gaju. Ti oba je wipe ni ọrun Olọrun ti o lagbara julọ wa ninu eniti awọn baba nla wa gbagbọ pelu iwa omugo o ni lati je dandan fun wa lati ni atampako. Ọlọrun alagbara julo lose ohun gbogbo, nitorina Ole se atampako pẹlu. Sugbon sa bi oba je wipe kosi enikan ni ọrun, emi ni temi moti pinnu lati okan mi wa lati sin eniti kosi ti oda atampako.

Nwọn wa di ẹniti nsin "Eni ti kosi!" Igbagbọ wọn ninu "Eniti kosi" yi npo sii bii

ojo ti nlo. Igbagbo won ninu re kise ti wipe oda atampako nikan, sugbon pe o tun da awon irawo, ododo, omode ati gbogbo ohun ti o lewa ni aiye.

Okan dabi igba atijo ni Athens, Paulu pade awon ti nwon nsin "Olorun aimo."

Ayo awon toko-taya yi kose fi enu so nigbati won gbo lenu mi pe nwon gbagbo ni ona otito, wipe ni Orun to ni kosi "Ara kan - ti ko si", Olorun eniti ise Emi. emi, ife, oye, otito ati agbara, eniti ofe won tobe ge ti ofi ran omo bibi re kansoso lati fi ara re rubo lori agbelebu.

Nwon tije Onigbagbo ninu Olorun laimo wipe awon sebe. Moni anfani ati tun mu won tesiwaju fun igba die si si iriri igbala ati irapada.

Nigbakan, mori omoge Oloye Russia ni opopo ona. Mo sunmo o, mosi toro aforiji: Momo wipe koki se iwa rere lati tete soro si obinrin ti eniyan o mo ri ni titi. Sugbon alufa ni mi beni ero mi se pataki. Mo ni ife ati ba o soro nipa Kristi.

O ba bimi lere wipe: "Nje o feran Kristi?" Moni: "Beni! lati inu gbogbo okan mi. "Nigbana ni o subu lemi lapa osi fi enu ko mi lenu leralera. Eyi je nkan iyalenu fun alufa, ni moba fi enu ko o li enu pada, pelu ero wipe eniti oba ri wa aro wipe ibatan ni wa. O kigbe soke bi oti nso fun mi wipe "Emi na feran Kristi!" Mo mu u lo si ile wa. Nibe ni moti se akiyesi pelu iyalenu wipe ko mo nkankan nipa Kristi - ko mo nkankan patapata - afi oruko yen. Sibesibe o feran Kristi. Ko mo wipe oun ni Olugbala, tabi itumo igbala. Ko mi, ibi ti Kristi gbe ati ibi

ti oti ku beni ko mọ bi oti se gbe igbesi-aiye re ati bi oti se ku. Ko mọ nipa awon eko re. Loju temi, bi eniti o nse ofintoto ti ako lese alaye ni obinrin yi je. Bawo ni ose le feran enikan ti o mo oruko rẹ nikan?

Nigbati mo bi lere, o ṣe alaye fun mi pe: "Ni igba ọmọde, a ko mi lati maka aworan. Fun 'a' nwon ya ọrọ Oyinbo ti a npe ni 'apul; fun 'b' nwọn ya agogo ti a nlu, eyiti Oyinbo npe ni 'bell', fun 'C' (eyi ni oro Oyinbo tiko sini Yoruba). Nwọn ya Ologbo, eyiti Oyinbo npe ni 'Kat', ati bebẹ lọ. Nigbati mo wa si ile eko giga, ako mini iṣẹ isin mimo mi lati dabobo Orile-ede Ijọba alaṣepọ. Nwọn ko mi ni eko giga alasepo. Sugbon sa nko mọ bi' iṣẹ isin mimo' tabi 'ẹkọ' tiri. Mo nfẹ aworan fun awọn wọnyi. Wayi mo mọ wipe awọn baba-nla wa tini aworan fun gbogbo ohun ti o dara, ti oye fun yinyin ti osi se otitọ ni aiye. Iya ti obi iya mi a ma teriba fun awọran yi nigba-gbogbo, a si ma wipe aworan enikan ni ti a npe ni 'Kristos' (eyi ni Kristi). Beni mosi feran oruko yi ni tire. Orukọ yi waję ojulowo fun mi! Ki a sa so wipe orukọ yi ni nfun eniyan niiru ayo iwayi."

Bi mo ti ngbo ohun ti o nwi, mo ranti ohun ti ako si Phillip wipe ni orukọ Rẹ gbogbo ekun nilati wole. Boya asodi-si-Kristi le gbi-yanju fun igba diẹ lati pa imọ Olorun rẹ sugbon agbara wa ninu oruko Kristi ti o rorun beni eleyi yio tọ lọ si imole.

Pelu ayo ni ofi gba Kristi ni ile mi, ati wipe eniti o feran oruko Rẹ wa ngbe inu rẹ ni odindi.

Gbogbo iran ti ngbe pelu awọn eniyan Russia ni o kun fun iwe Olosunwọn pẹlu itumo ti o jinle. Arabinrin kan ti o ntan ihinrere yi ka ni awọn ibi iduro ọkọ oju irin ni o fun oloye kan ni ibujoko mi nitoripe o ni ife si i.

Ni irọlẹ kan o wọ ile mi · okunrin ogagun ti o ga ti o si lẹwa.

Mo bii lere 'pe: ''Bawo ni mose le ran ọ lọwọ?''

Odahun o ni: ''mowa fun imọle ni.''

Mo bere sika fun, awon ibi ti ose pataki julọ ni inu Bibeli Mimo. O gbe ọwọ rẹle temi osi ni: ''Mo be o lati inu gbogbo okan mi wa, mase simi lona. Mo je okan ninu awon eniyan ti afi si inu okunkun . So fun mi, jowọ, njẹ eyi haje ọrọ Ọlọrun tọtọ bi?'' Mo fun o ni idaniloju wipe ọrọ Ọlọrun ni. O teti silẹ fun wakati pupo ... osi gba Kristi.

Awọn eniyan Russia kojẹ mu ọrọ Isin Olorun ni jelenke. Ti nwọn ba nlodi si isin tabi ti nwọn ba gba tọwọtẹsẹ ti nwọn si nwa Kristi, gbogbo ọkan wọn ni nwon fi nse bẹẹ. Idi rẹ ni eyi ni Russia ti Onigbagbọ kọkan fijẹ oniranse ajere ọkan. Idi rẹ ree tiko fisi ilu na ni gbogbo aiye ti o tii gbo ti osi mu ere wa fun ise ihinrere. Awon eniyan Russia je okan ninu awon eniyan agbaiye ti ojẹ wipe nipa ẹda wọn, Olufokansin ni wọn. Ipa ọna aiye vi se yipada ti aba le fun wọn ni ihinrere.

Ojẹ ọrọ ibinuje ju wipe Orile-ede ti Russia ati awọn eniyan rẹ ni awọn ti ebi ọrọ Ọlọrun npa ju, sibẹsibẹ o dabi ẹni wipe ofẹ isẹ gbogbo eniyan ni oti kẹhin si wọn.

Ninu oko oju irin kan, Ijoye Russia kan

joko ni iwaju mi. Moti baa soro nipa Kristi fun iseju die nigbati o bere si jiyan gegebi eniti ko gba wipe Olorun wa. Awon eko nipa Marx, Stalin, Voltaire, Darwin ati awon oro miran ti o lodi si Bibeli ni o nti enu re jade wa. Ko fun mi ni aye ati le tako oun. O soro fun bi wakati meji ati fi yemi wipe Olorun kosi. Nigbati o soro tan, mobi lere moni: "Tiko basi Olorun, kini idi re ti ofi ma ngbadura nigbati oba wa ni idamu?" Gegebi ole ti a mu lairotele nibi ti oti njale. O dahun oni: "Bawo ni ose mo wipe mo ngbadura?" Nko jeki oyo ninu eyi. Mo wipe: "Emi ni mo koko se ibere. Mo bere idi re ti ofi ngbadura. Jowo dahun!" Ote ori re ba osi jewo wipe: "Ni oju ogun, nigbati awon eniyan ilu Jamani yi waka, gbogbo wa la gbadura Ako mobi ati se ngbadura, ni aba so wipe: "Olorun ati emi Iya" - eyiti oje adura loju eniti nwo okan.

Iwasu wa fun awon eniyan Russia timu eso pupo wa.

Mo ranti Piotr (Peteru). Kosi eniti omo ogba ewon Russia ti oku si. Odo gidi ni! Boya nkea ti ogun odun ni ojo ori re. Oti wasi Rumani pelu awon omo-ogun Russia. Ayi lokan pada ni ibi ipade abelekan osi wipe ki nse iribomi fun oun.

Lehin iribomi yi, moso fun u wipe ki oso ese kan ninu Iwe Mimio (Bibeli) ti odun moo ninu ju, ati ti omu ki oto Kristi wa.

O wipe, oun teti sile dada ninu ikan ninu awon ipade ikoko wa nigbati moka iwe ihinrere ti Luku ori kerinlelogun, eyi ni itan bi Jesu se ba awon omo-ehin meji ti nlo si ona Emmaus. Bi nwon ti sunmo Abule, "O sebi enipe oun

olọ si iwaju sii". Piotr so wipe: "Oya mi lẹnu idi re ti Jesu fiso eleyi. Dajudaju ofẹ wa pelu awọn Ọmọ-ẹhin Rẹ. Ki ha ni idi re ti Ofi so wipe oun fẹlọ siwaju sii? Alaye mi ni wipe Jesu ni iwa rere, Ofẹni idaniloju wipe nwọn nfẹ oun. Nigbati o rii wipe nwọngba oun tọwọtẹsẹ, o fi ayọ wọ ile na pelu wọn. Awọn eniyan Ijọba alasepo koni iwa rere pẹlu ipa ni nwọn fi nwọ inu ọkan ati iye wa. Nwọn nfi agbara muwa lati owuro titi di alẹ lati teti si wọn. Nwọn nse bẹ nipa ile ekọ wọn, ero gboungboun, iwe irohin, ipade awọn tiko gba pe Ọlọrun wa ati gbogbo ibiti oba yiju si. Boya ofẹẹ tabi o korira re, o nilati maa feti si ọrọ aigba Ọlọrun gbọ ti nwọn npolongo kiri. Jesu bu ola fun ominira wa. Lẹsọlẹsọ ni o nkan ilẹkun. Jesu ti jere mi nipa iwa rere Rẹ. Iyatọ nla ti ọwa larin Ijọba alasẹpọ ati Kristi yi ni oti yee.

Oun nikan ko lojẹ eniyan Russia ti iru iwa Jesu yi dun mọ ninu (Emi gẹgẹbi alufa nko i ti ro ni iru ona bayi ri).

Lẹhin ironupiwada rẹ, Piotr fi ominira ati ẹmi rẹ w' ewu ni ọpọlọpọ igba lati yọ mu iwe kika fun awọn Onigbagbọ ati awọn ohun iranlọwọ fun Ijọ Abẹlẹ lati Rumania lọ si Russia. Ni igbẹhin ọwọ tee. Mo mọ wipe ni odun 1959 o'si wa ni ewon. Oha ti ku ni? O ti wa ni orun alafia tabi o si nja ija rere na ni aiye? Emi ko mọ. Ọlọrun nikan ni o mo ibi ti o wa loni.

Gẹgẹbi oun, ọpọlọpọ ni o wa ti o jẹ wipe ki ise wipe a kan yi won lẹkan pada nikan. A ko gbodọ duro ni ibi wipe a jere okan kan fun

Kristi. Nipa eleyi, idaji ise ni a se. Gbogbo okan ti a ba jere fun Kristi ni a nilati se ni ajere okan. A ko kan yi awon eniyan Russia ni okan pada nikan, sugbon nwon je Onise Olorun ni inu Ijo Abele. Nwon ko bikita beni nwon ni igboya fun Kristi, nwon a maa so ni gbogbo igba wipe ohun ti nwon se yi kere ju fun Kristi ti o ku fun won.

## IWASU WA ABELE FUN ORILẸ-EDE TI O WA NI OKO ẸRU

Ẹya keji isẹ wa ni iwasu wa Abele larin awọn eniyan Rumania tikalarawọn.

Laipe, awon Ijoba alasepọ mu bojuboju wọn kuro Ni ibẹrẹ nwọn lo iwa ẹtan lati fi jere awọn asaju Ijọ si ọdọ wọn, ṣugbọn nigbana, ijiya wa bẹrẹ. Ẹgbẹrun aimoye ni a fi ofin mu. Lati jere okan kan fun Kristi bẹrẹ sidi ohun ti o nṣẹlẹ lojiji fun wa gẹgẹbi oti ma nri fun awọn eniyan Russia fun igba pipe.

Nigba toya emi paapa lo si ẹwọn pẹlu awọn ti Olorun ti ran mi lọwọ lati jere fun Kristi. Mo wa ninu yara kanna pẹlu ẹnikan ti ofi ọmọ mefa si ile ti osi jọwọ ara re lati lọ si ẹwọn nitori igbagbọ rẹ ninu Kristi. Ebi npa iyawo ati awọn ọmọ rẹ. O ṣeeṣe ki oma ri wọn mọ. Mo bi lere ni: "Nje o ni ikunsinu kankan simi nitori wipe mo mu ọ tọ Kristi wa ati wipe nitori eyi awọn ẹbi rẹ wa ninu oṣi

iru eyi? O dahun wipe: "Nko ni ọrọ ti mo le so bi mo ti dupẹ to wipe o ti mu mi wa si ọdọ Olugbala iyanu. Nko le ni nkan bayi ni ona miran.

Iwasu Kristi ninu awọn ipo titun wọnyi ko rọrun. A yege ninu ọpọlọpọ iwe kekeke fun awọn Onigbagbọ ti a nte, ti osi ngbe awọn Ijọba alasepo ti nwọn nyẹ gbogbo iwe wo sugbọn ti nwọn kori awọn iwe wọnyi. Iwe ti a nkọ fun eniti o nye gbogbo iwe wo wọnyi yio ni aworan Karl Marx ẹniti oda Ijọba alaṣepọ silẹ ni iwaju rẹ. A nfun awọn iwe bawonyi ni oruko bi "Isin ni ohun ti o nfun awon eniyan ni idera" tabi awọn orukọ miran ti o dabi iru wọnyi. Eniti o nyẹ awọn iwe wo wonyi ka won kun awon iwe Ijoba alasepo, yio sifi edidi te won. Ninu awon iwe wọnyi, ni awọn oju iwe ti o saju, ao ko ọpọlọpọ awon orin ti awọn Marx, Lenin ati Stalin sọ, eyiti o dun mọ okunrin ti o nye iwe wo yi ninu. Lehin na, ao wa sọ ọrọ wa nipa Kristi.

Ijo ti Abele yi ko fi gbogbo ara wa ni abele tan gegebi yinyin nla ti maa nfo loju omi pelu bi idameta ara re ninu omi, die ninu ise Ijo yi wa ni gbangba. A lọ si ibi ti awọn eniyan Ijọba alasepọ ti pọ, asi npin awọn iwe "ti Ijọba alasepo yi". Nigbati awọn eniyan wọnyi ri aworan Marx, nwọn berẹ si du lati ra iwe na. Nigbati nwon ba ma fi ka de oju iwe kewa ti nwon si ri wipe ọrọ nipa Ọlọrun ati Jesu ni o wa nibe, a o ti rin jina.

Lati ma wasu ninu ipo titun wọnyi ko rọrun. A pọn awọn eniyan wa loju pupọ.

Awọn Ijọba alasepo gba ohun gbogbo lọwọ gbogbo eniyan. Lowo agbẹ, nwọn gba ọkọ ati agutan re. Lati ọwọ afarun tabi Onisọna asọ wiwo, nwon gba ile-oja rẹ. Ki i se awọn ti nwọn lọla ti wọn lọla nikan ni a gba ẹru wọn. Awọn otosi pelu a ma jiya pupọ. O fẹrẹjẹ wipe gbogbo ẹbi ni oni eniyan ni ẹwọn bẹni aini sima npọ pupọ. Awon eniyan a ma ṣe bere wipe " Bawo ni o se jẹ wipe Ọlọrun se fun ibi ni aye ati bori?

Bẹẹ na ni kole rọrun fun awọn Aposteli iṣaju lati wasu Kristi ni Ọjọ Friday Rere, nigbati Jesu nku lori agbelebu ti o si nwi awon ọrọ wọnyi pe: "Ọlọrun Mi, Ọlọrun Mi, eṣe ti Iwọ fi kọ mi silẹ?"

Sugbọn otitọ wipe ise yi se, fi di rẹ mulẹ pe lati ọdọ Ọlọrun wa ni ki ise lati ọdọ wa. Igbagbọ awọn Onigbagbo ni idahun fun awọn iru ibere wọnyi.

Jesu sọ fun wa nipa Lasaru otosi ti a pọn loju bi a ti se pọn awa na loju - bi o ti nku, ebi npa bẹni awọn aja nla egbo rẹ - sugbọn ni ikẹhin awon Angeli gbee lọsi ookan aya Abrahamu.

## BI IJỌ ABELE TIṢE ṢE APAKAN IṢẸ RẸ NI GBANGBA

Ijọ Abele yi a ma ni ipade wọn ni ile ara wọn, ninu igbo, ni inu yara ti o wa ni abe iletabi ibikan ti o ba ti·le se ipade naa. Ni ibi ikọkọ yi ni o ti nṣeto iṣẹ ti yio se ni gbangba. Bi a se wa labẹ awọn Ijoba alasepọ yi, a ṣe eto

lati maa se iwasu ni opopo ona eyi ti oje wipe bi ojo ti npe si, o fa ewu lowo. Sugbon ni ona yi a kan awon opolopo okan ti a ko ba ti jere fun Kristi nipa ona miran. Ara iyawo mi ya si ise yi gan. Awon Onigbagbo miran a rora pejo ni ikoko kan ni opopo ona nwon a si maa korin. Awon eniyan yio si sun mo odo won lati gbo orin didun ti nwon nko. Iyawo mi a si se iwasu re. A maa nkuro ni oju yen ki awon

Ni osan ojo kan, bi mo ti nba ise lo ni ibomiran, iyawo mi wasu larin egberun aimoye awon osise, ni abawole ile ise nla ti MALAXA, ni arin ilu Bukarest. O soro fun awon osise wonyi nipa Olorun ati nipa igbala. Ni ojo ti o telee opolopo awon osise ibi ise yi ni a yin ibon pa nitoripe nwon tako aisododo ti awon Ijoba alasepo. Nwon tete gbo iwasu ihinrere yi.

Awa je Ijo Abele, sugbon gegebi Johannu Baptisi, a wasu ni gbangba fun awon eniyan ati awon alakoso nipa Kristi.

Nigbakan, ni ori awon ategun okan ninu awon ile Ijoba wa, awon onigbagbo arakunrin meji lo ba Oloye giga julo wa Gheorghin Dej. Ni arin iseju die ti nwon ni, nwon wasu fun u nipa Kristi, nwon nro lati yipada kuro ninu ese ati inunibini re. O ni ki nwon ju awon meji yi si ewon fun igboiya ti nwon ni lati wa wasu fun won. Odun pupo lehin iyen, nigbati ijoye kanna yi, Gheorghin Dej. Se aisan, eso ihinrere ti nwon ti gbin ni odun pupo sehin eyiti nwon si jiya pupo nitori re, so eso - ni akoko ti ose alaini, ijoye yi ranti awon oro ti nwon ti baa so.

Awọn ọrọ wọnyẹn, gẹgẹbi Bibeli ti sọ "yara bẹni nwọn lagbara, nwon si mu ju ida oloju meji lọ." Nwọn ge ja lile ọkan rẹ, beni o si jọwọ igbesi-aiye rẹ fun Kristi. O jẹwọ ẹṣẹ rẹ, o gba Olugbala O si bẹrẹ si sin I ni inu aisan rẹ. Kope lehin eleyi, o ku ṣugbọn o lọ si ọdọ Olugbala ti o sese ri, gbogbo re nitori wipe awon Onigbagbọ meji ṣetan lati san iye rẹ. Awọn wọnyi sijẹ apẹrẹ awọn Onigbagbọ ti nwọn ni igboiya ni Orile-ede awọn Ijoba alaṣepọ loni.

Nipa bayi, Ijọ Abele yi nṣiṣẹ, ki ṣe ni ipade ati aapon ikọkọ wa nikan, ṣugbọn ni igboiya, nwọn npolongo ihinrere ni opopo ọna awọn Ijoba alaṣepo ati fun awọn asaju Ijọba alasepo. Iye kan wa, a se tan lati san. Bẹni Ijọ Abele si ṣetan lati san iye yi loni.

Awọn Ọlọpa inu pọn Ijọ Abele yi loju pupọ nitori nwọn ri wipe ninu rẹ nikan ni itako ti ole ku si. Ati wipe iru itako, ani itako ti Emi, eyiti ojẹ wipe ti nwọn bafi silẹ laidi lọwọ, yio jin agbara igbagbọ wọn lẹsẹ. Nwọn ranti, gegebi esu nikan ti le ranti, ona ikilo. Nwon mo wipe ti okunrin kan ba gbagbo ninu Kristi, koni jẹ fi ifẹ tẹriba fun wọn. Nwọn mọ wipe awọn le ko awọn eniyan si itimọle, nipa bẹ, pẹlu agbara ni nwọn fi nja.

Sugbọn Ijọ Abele yi ma ni awọn ti nwọn nba duro tabi ọmọ ẹgbẹ wọn ti o wa ninu awọn Ijoba alaṣepọ ati ninu awọn Ọlọpa inu.

A fun awon Onigbagbo ni ase lati pelu awọn Ọlọpa inu, ki nwọn si wọ aṣọ eyiti gbogbo ilu korira ti nwon si kegan, ki nwọn ba le ma sọ apọn awọn Olọpa inu fun Ijo Abele. Ọpọlọpọ ninu awọn ẹgbẹ Ijo ikọkọ ni nwọn ṣe eyi ti

nwọn si nfi igbagbọ wọn pamọ. Ko je ohun ti o rọrun lati ri wipe ebi ati ọrẹ rẹ nkẹgan rẹ nitoripe wipe o wọ asọ awọn Ijọba alasepọ, ki o maa si so ododo iṣẹ rẹ fun wọn sibẹsibẹ nwọn nṣee. Ife wọn fun Kristi ga pupọ.

Nigbati nwọn jimi gbe ni titi ti nwon si fi mi si ipamọ ti o le fun ọpọlọpọ ọdun, lati le wadi ibi ti mo wa, Onigbagbọ Oniṣegun kan di egbe Olopa inu! Gẹgẹbi Onisegun Ọlọpa inu, o ni aye lati de gbogbo yara awọn ẹlẹwọn o si ni ireti lati wa mi ri. Gbogbo awọn ọrẹ rẹ lo kẹhin sii, nwọn nro wipe o ti darapọ mọ awọn Ijoba alasepo. Lati maa rin kiri ninu asọ awọn adaniloro je irubo ti o ga fun Kristi ju wipe lati wọ aṣọ ẹlẹwọn.

Onisegun yi ri mi ninu yara ti o jin ninu ile ti o si dudu, o si ranṣẹ wipe mo si wa laiye. Oun loje ore mi ti o kọkọ wa mi ri ninu ọdun mẹjọ ati abọ ti mo kọkọ lo ni ẹwọn! Nipa oun, ni o fi tan ka wipe mo si wa laiye ati 'pe' nigbati a da awọn elẹwon silẹ ni akoko ti Eisenhower-Kruschev da won silẹ ni odun 1956, awọn Onigbagbo pariwo 'pe ki nwọn da emi naa silẹ, nwọn da mi silẹ mo si wa ni ominira fun igba diẹ.

Ti ko ba se ti Onigbagbo Onisegun yi ni, ẹni ti o di Ọlọpa inu nitori ti'emi gan, nwọn ko ba ti da mi sile lai. Nba si wa ni inu ẹwọn (tabi ni sare) loni.

Bi nwon ti nlo ipo wọn ninu ẹgbẹ Ọlọpa inu, awọn ọmọ ẹgbẹ Ijọ Abẹle yi maa nkilo fun wa ni ọpọlọpọ igba, nwon si se wa ni anfani pupo. Ijọ Abẹle si ni awọn eniyan ninu Ọlọpa inu loni, awọn ti nwọn nse alaabo ti nwọn si

nkilo fun awọn Onigbagbọ nigbati ewu ba nbọ. Awọn miran jẹ oga gidi ninu agbo awọn Ijoba alasepo yi, bẹni nwọn mu igbagbọ ninu Kristi pamọ, nwọn si nran wa lọwọ gidi. Ọjọ kan ni ọrun, nwọn yio le polongo Kristi ni gbangba, ẹniti nwọn nsin ni ikọkọ.

Bi o tilẹ ribẹ, ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Ijọ Abẹle ni nwọn ri ti nwọn si sọ si ẹwọn. A ni "awọn Judasi" wa pẹlu, ti nwọn nṣe ofofo fun awon Olopa inu. Nipa nina, fifun eniyan ni ogun ti o le je ki o sọrọ tipatipa, idẹruba ati sisọrọ eniyan ni buburu, awọn Ijọba alasepọ gbiyanju lati ri awọn onisẹ Ọlọrun ati awọn eniyan Ijọ ti ki se alufa ti yio ma ran wọn lọwọ lati se ofofo ara wọn.

## ORI KEJI

## "IRU IFE YI TI ENIKENI KO NI"

Mo ṣiṣẹ labẹ aṣẹ ati ni ona ikọkọ titi o fi di ọjọ kọkan-din-lọgbọn osu keji odun 1948. Ọjọ simi ni,o jẹ ọjọ isimi ti o dara. Ni ọjọ simi yi, bi mo ti nlọ si ile Ọlọrun, awọn Ọlọpa inu ji mi gbe lati ori titi.

Igba pupọ ni mo ti ma nro wipe kini itumọ "jiji eniyan gbe", ti a sọ nipa rẹ ninu bibeli.. Ijọba alasepo ti kọ wa.

Ọpọlọpọ ni a ji gbe ni akoko yẹn ni ọna bayi. Ọkọ nla awọn Ọlọpa inu duro ni iwaju mi, awọn okunrin merin bẹ jade lati inu rẹ nwọn si ti mi lo si inu ọkọ na. Nwon mu mi lọ fun ọpọlọpọ ọdun. O ju ọdun mẹjọ ti ko fi si ẹni ti o mọ boya mo wa laiye tabi mo ti ku. Awọn Ọlọpa ikọkọ lọ si ọdọ iyawo mi nwọn si ṣe bi enipe ẹlẹwọn ti a da silẹ ni nwọn. Nwọn sọ fun u wipe awọn lọ si ibi isinku mi. Ọkan rẹ bajẹ.

Ogunlọgọ lati orisirisi Ijọ ni nwọn lọ si ẹwọn ni akoko yen. Ki se alufa nikan ni nwọn fi si ile tubu, nwọn tun fi agbẹ ti ko mọ nkankan, awon ọdọ okunrin ati obinrin ti nwọn njeri fun igbagbọ wọn lọ si ẹwọn. Awọn ile tubu kun, bẹni ni Rumania, gẹgẹbi gbogbo ilu ti Ijoba alaṣepo ti gbilẹ, lati wa ni ẹwọn jẹ lati wa ni ibi idaniloro.

Awọn idaloro a ma banilẹru nigbamiran. Mo yan lati ma so pupọ nipa awọn eyi ti mo ti la koja. Nigbati mo ba ṣe bẹẹ, nko ni le sun loru. O ni irora pupọ.

Ninu iwe miran "Ninu Ijo Abele ti Olotu ti W. H. Allenko, mo tun so l'okankan lekeji gbogbo iriri wa pelu Olorun ninu tubu.

## AWON IDALORO TI KO SE FI ENU SO

Nwọn da alufa kan, oruko ẹni ti njẹ Floresen, loro pelu awọn irin ti o gbona gan ti o si npupa ati ọbẹ. Nwọn lu pẹlu ada. Lehinna nwọn si aye sile fun awọn ekute ti ebi ti npa lati inu iho nla. Ko le sun, sugbon o ni lati dabobo ara re ni gbogbo igba. Ti o ba simi, awon ekute a dojukọ ọ.

Pẹlu ipa ni o fi nilati duro fun ọsẹ meji, ọsan ati oru. Awọn ti nwọn gbe Ijọba alaṣepọ lẹsẹ fẹ fi ipa mu lati se ofofo awọn ara rẹ. Ṣugbọn ṣa o taku ni iduro ṣinṣin. Ni ikẹhin, nwọn mu ọmọ rẹ ọkunrin, ti iye ọdun rẹ jẹ mẹrinla, nwọn si bẹrẹ si na ni iwaju babare, nwọn si nsọ pe awọn yio ma lu ọmọ na sa titi alufa yi yio sọ ohun ti nwọn fẹ ko sọ. Okunrin yi tiya were de idaji. O rọju de ibi ti o le rọju mọ. Nigbati ara rẹ ko gba mọ. O so fun ọmọ rẹ pẹlu igbe o ni: "Alexander, mo nilati sọ ohun ti nwọn fẹ Nko le rọju pẹlu nina rẹ yi mọ! Ọmọ rẹ dahun o ni "Baba, ma ṣe ṣe aisotitọ ti

ati ni olofofo gegebi obi si mi. Durosinsin! Ti nwon ba pa mi ngo ku pẹlu awọn ọrọ wọnyi Jesu ati ile - baba - mi!'' Inu awọn ti nwọn ngbe Ijọba alaşepọ yi ru, nwọn si fi ibinu lu ọmọ yi titi o fi ku, ẹjẹ si ta si gbogbo ara ogiri yara tubu. O ku pẹlu iyin Ọlọrun lẹnu rẹ. Ara arakunrin wa ọwọn, Floresen, yi ko ri bakanna lehin igba ti o ri eleyi.

Ṣẹkẹṣẹkẹ ti o ni iṣo ti o mu ni inu rẹ nwọn nko si ọrun ọwọ wa. Ti a ba duroje patapata, nwon ko ni ge wa, sugbon ni yara ewon ti o tutu bi yinyin, nigbati a ba ngbọn nitori otutu, iso yi a ya ọrun-ọwọ wa.

Nwon a so awọn Onigbagbọ pẹlu ẹsẹ wọn loke, bẹni nwọn nlu wọn tagbaratagbara tobẹ ti o fijẹ wipe ara wọn a ma fi lọ siwaju ati si ẹhin ni ilu lile yi. Nwon a gbe awon Onigbagbọ si inu apoti yinyin "yara ẹwọn ti a ti nmu nkan tutu" eyiti o tutu gan, ti otutu ninu ati omi oidi wa ni inu rẹ. A ju emi papa sinu ọkan pelu aṣọ diẹ lọrun mi. Awọn Onişegun ẹwọn a ma sọ ẹni ti o wa ninu yara wọnyi lati inu iho kan titi nwọn o fi ri ami wipe ẹni na ti fẹ gan ku, nigbana ni wọn o şe ikilo, awon Oluso yio si sa wọ 'le lati mu wa jade ati lati mu wa gbona. Nigbati a ba si ti gbona to, ẹsẹkẹsẹ ni nwọn o tun tari wa si inu yara tutu yi lati tun mu wa di - eyi ni nwọn nse ti nwon tun ntunse! Bayi ni nwon nyọ wa bi omididi ti nwọn tun nmu wa di titi ku nkan bi iseju kan tabi meji ki a ku, ti nwọn a tunyọ wa bi omi didi. Eyi ni nwọn nse ni ailopin. Loni papa igbamiran nko le rọju lati si apoti ti a fi nse omi didi.

Nwọn ngbe awa Onigbagbọ si inu awọn

apoti ti a fi pako kan ti o fi die tobu ju wa lo. Eyi ko fi aye silẹ fun wa lati yi 'ra pada. Ọpọlọpọ iso ti o mu ni a kan lati ita si gbogbo ara apoti yi ti osi yo si inu re. Niwọn bi a ba ti duro jẹ, o dara bẹ. Pelu ipa ni a ni lati fi duro ninu awon apoti wọnyi fun ọpọlọpọ wakati ailopin. Sugbon nigbati o ba re wa ti a ba si yirapada pelu arẹ, awọn iso wọnyi a wọ ara wa lo. Ti eran ara kan ba ja, iso buruku wọnyi a woo. Ohun ti Ijoba alasepo se si awon Kristiani koja oye eniyan.

Mo ti ri awọn ti-nwọn ngbe Ijọba alaṣepọ ti nwọn nda awọn Onigbagbọ loro bẹni oju awọn adaniloro wọnyi si kun fun ayọ. Bi nwon ti nda awọn Onigbagbọ wọnyi loro ni won nfi(igbe ke wipe, "Awa ni eṣu naa".

Awa Njijakadi ki i se pelu ẹran ara tabi ẹjẹ, sugbọn pẹlu awọn ijoye ati agbara ibi. A ri wipe eto Ijọba alaṣepọ ko ti ọwọ eniyan wa ṣugbon lati ọwọ eṣu. Agbara ẹmi ni agbara ibi-bẹni agbara emi ti o tun tobu ju eleyi ni o le tako, ani Ẹmi Olorun.

Mo wa nbere lọwọ awọn adaniloro nigbakugba 'pe: "Ẹ ko ni anu ninu okan yin ni?" Nwọn ma ndahun pẹlu ọrọ kan bi Lenin ti ṣe sọ pe "O ko le pọ eyin fun didin lai fọ korofo eyin ati wipe o ko le ge igi ki ẹrun igi ma fo." Mo tun wipe: "Emi na mọ ọrọ yi ti Lenin sọ Ṣugbọn sa iyatọ wa ni ibẹ. Nigbati o ba ge igi kekere kan, ko mọ nkannkan. Ṣugbọn sa ni 'bi awon omo eniyan ni o nda loro. Gbogbo ina kankan ni o nmu irora wa beni a ri awọn iya ti nwon nsun'kun." Asan ni o jasi. Igbagbọ won oju ti nkan aiye yi lọ. Loju ti won, ko tun

si nkan miran ti o wa lẹhin eyi ti a fi oju ri a si fi owo kan bẹni bi igi tabi korofo eyin ni eniyan ri loju wọn. Pẹlu igbagbọ yi, nwọn nri si inu iwa ika si ti o fi jẹ wipe iwa ika wọn ko see gbagbọ.

Iwa aigbagbọ 'pe Ọlọrun wa yi soro lati gbagbọ. Nigbati eniyan ko ba ni igbagbo ninu esan rere ti o ba se tabi iwa buburu ti o ba se, ko si idi ti o fi yẹ ki o se eniyan. Ko si idiwo fun ibi ti o wa ninu eniyan. Awọn adaniloro ti nwọn ngbe Ijoba alasepo a maa sọ wipe, "Ko si Olorun, ko si ohun ti yio ṣẹlẹ lẹhin eyi, ko si ijiya fun ibi. A le se ohun ti a ba fẹ." Mo ti gbo ti adaniloro kan tilẹ sọ wipe "Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun, ninu ẹniti nko gbagbọ wipe mo wa laiye titi di wakati yi nigbati aiye gbami lati fun gbogbo ibi to wa lokan mi jade." O wi eleyi ninu iroro ti ko se gbagbọ ati idaloro ti o nfi le awọn ẹlẹwọn lara.

Anu ṣe mi gidigidi ti Ọni baje eniyan, ṣugbọn nko le gan Ọni na. Ọni ni o jẹ. Ko ki ṣe ẹda ti o ni iwa. Bakanna a ko le gan awọn ala-fowo-sowopo pelu Ijoba alaṣepo. Eto Ijoba alasepo ti pa iwa rere gbogbo ti o wa ninu wọn rẹ. Nwon nsogo ninu wipe awọn ko ni anu ninu okan wọn.

Mo kọ ẹkọ lati ọdọ wọn. Bi wọn ti sai ṣi aye silẹ fun Jesu ninu ọkan wọn mo pinnu pe nko ni fi aye silẹ, bi o ti wu ki o kere to, fun ẹsu ni ọkan mi.

Mo ti se ijeri niwaju ajo Igbimo ti o nboju to abo ti inu ilu Oke-Okun (United States). Ni ibẹ, mo fi ọrọ sapẹrẹ awọn ohun ti o buru, bi ki a di awọn Onigbagbo mo agbelebu fun ọjọ mẹrin ati oru merin. Nwon a gbe awọn agbe-

lebu wọnyi silẹ, ogunlọgọ awọn ẹlẹwọn a si ma ṣe awọn ohun irira, bi wipe ki nwọn kan mọ agbelebu yi. Lehinna nwon a tun gbe agbelebu yi dide. Awọn ti nwọn ngbe Ijoba alasepo yi a si ma ṣe yẹyẹ, nwọn a ma ṣẹ lẹya pe: "E ki Kristi nyin! O ma lẹwa o! Orun didun ni ti o muwa lati Ọrun yi ma dara o! Mo fi oro sapere bi o ti se jẹ wipe lẹhin igba ti alufa kan ti fere siwere pẹlu idaloro, nwọn nfi ipa mu alufa yi lati ya igbẹ ati itọ eniyan si mimọ ki o si fi ṣẹ onjẹ ale Oluwa fun awọn Onigbagbọ bayi. Eyi selẹ ni ewon Rumania ti Pitesti. Mo bi alufa na

lẹhinna wipe kinni idi rẹ ti ko fi yan lati ku ju wipe ki oṣe ohun ẹgan yi. O dahun o ni: " Jọwọ maṣe da mi lejọ! Mo ti jiya ju Kristi lọ! Gbogbo apejuwe ọrun apadi ti o wa ninu Bibeli ati irora ti awọran ibi ipaiya ti Dante ko, ko je nkankan ti ba fi we idaloro ti ẹwọn Ijoba alaṣepo.

Apa kekere nikan ni eleyi jẹ ni ara ohun ti o ṣẹlẹ ni ọjọ isimi kan ati ni ọpọlọpọ ọjọ isimi miran ni ẹwọn ti Pitesti. Awọn nkan miran ko kan ṣe sọ. Okan mi yio tase ti mo ba ni lati maa tun won so. Nwon je ohun iberu pupo ati irira lati ko silẹ. Ohun ti awọn arakunrin yin ninu Kristi la kọja ti nwọn si nla kọja ni isin ni yen!

Ikan ninu awọn akọni ti o tobi nitọtọ ni ti Igbagbo yi ni alufa Mihan Haimovici.

Awọn ewọn wọnyi ti kun ju ti o fi je wipe awọn olusọ ko mọ orukọ wa. Nwọn a pe awọn ti a ti da lejo lati gba pasan marun-din-lọgbọn pẹlu ore nitoripe nwon ti tapa si ofin ẹwon. Fun igba aimoye ni alufa Mihan Haimovici lo lati gba ina yi ni ipo ẹlomiran. Nipa eleyi,

gbogbo awọn ẹlẹwọn to ku bu ola fun u ati fun Kristi aṣoju eniti o nṣe.

Ti mo ba ni lati maa sọ gbogbo ohun ipaiya ti awọn ti nwọn ngbe Ijọba alasepo le ṣe ati gbogbo ifi-ara-eni-rubọ ti awọn Onigbagbọ, nko ni ṣetan lai. Ki ise awon idaloro wọnyi nikan ni o jẹ mimọ. Awọn iṣe akọni na jẹ mimọ. Apẹrẹ akọni ti awọn ti nwọn wa ni ẹwọn fun awon ara ti o siwa ni ominira ni okun.

Ọkan ninu awọn oṣiṣẹ wa ni ọmọ'binrin kan ti Ijọ Abẹle. Awon Ọlọpa Ijọba alaşepọ ti jagbọn wipe ọmọbinrin yi ntan ihinrere ka, o si nkọ awọn ọmọde nipa Kristi ni Ikoko. Nwọn pinnu lati muu. Ṣugbọn lati mu ki eyi jẹ ohun ti yio mu ibanujẹ ati irora gẹgẹbi nwọn ti nfẹ wa, nwọn pinnu lati da mimu rẹ duro fun ọsẹ diẹ, ki o baa le ṣe gẹgẹ ọjọ ti yio ṣe igbeyawo. Ni ojo igbeyeawo re, omobinrin yi mura gegebi iyawo. Ọjọ iyanu julo ati ọjọ ayo ni igbesi aiye obinrin! Lojiji nwọn ṣi ilẹkun, awọn Ọlọpa inu si rọ wole.

Nigbati iyawo ri awọn Ọlọpa inu, o na ọwọ rẹ siwaju si nwọn lati fi sekesekẹ bọ o. Nwọn fi agbara ki sekeseke yi si ni orun ọwọ. Ọmọbinrin yi wo olufe rẹ, lẹhinna o fi ẹnu ko ẹwọn ọwọ rẹ o si so wipe "Mo dupe lọwọ ọkọ mi ti ọrun fun oruka iyebiye ti o fi ta mi lorẹ ni ọjọ igbeyawo mi. Mo dupe lọwọ Rẹ nitoripe mo yẹ lati jiya fun U". Nwọn wọ ọ lọ, nwọn si fi awọn Onigbagbọ ati ọkọ iyawo ti nwọn nsọkun silẹ. Nwọn mọ ohun ti o ma nsele si awon omobinrin Onigbagbo lọwọ awọn Oluṣọ Ijọba alaşepọ. Lẹhin ọdun marun nwọn jowo rẹ lọwọ, o si

dabi obinrin ti a ti run ti o si dabi eni wipe ojo ori re ti le ni ọgbọn ọdun. Ọkọ rẹ ti duro de e fun ọjọ pipe. Omobinrin yi sọ wipe ohun ti o kere ju ti oun le ṣe fun Kristi ni eyi. Iru awọn Onigbagbọ ti o dara bayi ni nwọn wa ni Ijọ Abẹle .

## OHUN TI YIILỌPỌLỌ-PADA JE

Awon eniyan Iwo Orun a ti gbo nipa iyilopọlọ-pada ni akoko ogun Korea ati ni isisiyi ni Vietnam. Emi pelu ti koja ninu iyilopolo pada yi. Oje idaloro ti o ni eru julo

Fun opołopo odun, a ni iati joko fun wakati meta-din-logun lo ojọ. A o si ma gbo.

Eto Ijoba alasepo dara!
Eto Ijoba alasepo dara!
Eto Ijoba alasepo dara!
Eot Ijoba alasepo dara!
Iwere ni Isin Igbagbo!
Isiwere ni Isin Igbagbo!
E tuba!
E tuba
E tuba!
E tuba

Fun wakati meta-din-logun lo ojọ· fun opolọpọ ojo ose ati osu.

Opolọpọ awọn Onigbagbọ ni nwon ti bere lowo mi bi eniyan se le tapa si iyilọpọlọ-pada. Ona kansoso ni o wa ti eniyan fi le tapa si iyilọpọlọ-pada Eyi ni "Okan-fifọ". Ti ọkan

ba wa ni fifọ nipa ifẹ Jesu Kristi, ati wipe ti ọkan ba fẹran Rẹ, o le tapa si gbogbo idaloro. Kini iyawo ti o kun fun ifẹ ni lati ṣe fun ọkọ ti o kun fun ifẹ? Kini iya ti o kun fun ifẹ ni lati ṣe fun ọmọ rẹ? Bi o ba fẹran Kristi gẹgẹbi Maria ti ṣe, ẹniti o ni Kristi lọwọ rẹ gẹgẹbi ọmọ tuntun, ti o ba fẹran Jesu gẹgẹbi iyawo ti nfẹran ok

ọkọ rẹ, nigbana o le tapa si iru awọn idaloro wọnni.

Ọlọrun yio da wa lẹjo, ki se nipa oye ohun ti a farada, sugbon nipa oye ifẹ ti a le fihan. Emi je ẹlẹri fun awọn Onigbagbọ ti nwọn wa ni ẹwọn awọn Ijọba alasepo wipe nwọn le fẹran. Nwọn le fẹran Ọlọrun ati eniyan.

Idaloro ati iwa ika yi tesiwaju lai si diwo. Nigbati nko ba mọ ohun ti mo nse mọ tabi kẹ ti mo ba di omugọ tobẹẹ ti nko le fun awọn adaniloro wonyi ni ireti ti ijẹwọ mọ, nwon o da mi pada si inu yara mi ninu ẹwọn. Nibe ni ngo dubule si, ko si eniti yio se itoju mi, ngo si ti ku sara, nwon o fi mi silẹ lati gba agbara die pada ki nwọn baa tun ṣiṣẹ lori mi. Ọpọlọpọ ni o maa nrọju pada wa. Ni awọn odun ti o tẹle, ni ọpọlọpọ ẹwọn ọtọtọ, nwọn ṣẹ egun ẹhin mi mẹrin ati ọpọlọpọ awọn egun miran. Nwon bu eran ara mi ni ibi pupo. Nwon da iho mejidinlogun si ara mi.

Awon Onisegun ni Oslo, nigbati nwọn ri gbogbo iwọnyi ati awọn apa oju arun fukufuku eyiti mo tun ni, ti so wipe wiwa-laiye mi loni ise-iyanu ni! Gegebi awọn iwe ti ogun won ti wi, oye ki nti ku ni ọpọlọpọ ọdun sẹhin. Emi na mo fun ara mi wipe ise-iyanu ni. Ọlọrun

Onise-iyanu ni Ọlọrun.

Mo ni igbagbo 'pe Olorun se ise iyanu yi ki iwọ ba le gbọ ohun mi ti mọ nke sita ni orukọ awọn Ijọ Abẹle ti nwọn wa ni ẹwọn. O fi aye silẹ fun enikan lati jade laye ki o si wa ke fun gbogbo eniyan lati gbọ iṣẹ ti o mu wa lati odo awon ara wa oloto ti nwon njiya.

OMINIRA DIE, LEHINNA A TUN MU MI:

Ọdun 1956. Mo tiwa ni ẹwọn fun odindi ọdun mẹjọ ati abọ. Mo wa fuye, mo ni apa egbo ti o burẹwa pupọ lara, a ti lu mi bẹni ati fi ipa gbe mi pelu iwa ika, a ti fi mi ṣe ẹlẹya, a ti fi ebi pa mi, a ti fun mi po. Nwọn ṣe ibere lọwọ mi pẹlu lati fi mi han titi o fi su wọn, nwọn dẹruba mi, nwọn si pa mi ti. Ninu gbogbo iwonyi, ko si eyi ti o mu ohun ti awọn ti o mu mi, nlepa jade. Nigbana, pelu irẹwẹsi, nwọn tu mi silẹ. Jube lọ, nwọn si nri ikilo gba lori fifi mi sinu ẹwọn.

Nwọn fun mi ni aye ati pada si ipo mi atijọ fun ọsẹ kan pere. Mo wasu ni emeji. Nwọn tun pe mi, nwọn sọ fun mi wipe nko le wasu mo tabi ki nṣe iṣẹkiṣẹ ti oba ṣe ti isin. Kini mo ti sọ? Mo ti gba awọn ẹgbẹ ti nse itoju awon alufa ni iyanju 'pe ki nwọn ni suru, suru, ati suru sii.'' Awon Olopa yi ba kigbe mo mi wipe ''itumọ ẹyi ni wipe o nsọ fun wọn wipe ki wọn sa ni suru ati wipe awọn eniyan Amẹrika

yio wa lati gba wọn sile." Mo tun so wipe keke a ma yi beni igba nyipada. Nwọn tun kigbe wipe: "O nsọ fun wọn wipe awọn ti nwọn ngbe Ijoba alasepo lẹsẹ koni jọba titi! Awon iro iṣọtẹ ti o lodi ni wọnyi." Iyẹn ni o sijẹ ipari iwasu mi fun gbogbo eniyan.

Boya awọn alaṣẹ ni igbagbọ wipe ẹru yio ba mi lati pẹ wọn nija ki nsi pada lo si isẹ ihinrere ti Abẹle. Ibiti nwọn ti ṣiṣe ni yen. Ni ikọkọ mo pada si iṣẹ ti mo ti nse tele. Ẹbi mi timi lẹhin.

Lẹkan si mo jẹri fun agbo ikọkọ nipa awọn ti nwọn se olọtọ, mo nlọ mo si nbo bi iwin ni abẹ abo awọn ti a le gbekele. Ni Akoko yi mo ni apa egbo lara mi lati fi ti iwasu mi lẹhin nipa ibi gegebi awon tiko gba Ọlọrun gbọ tiri ati lati mu awọn ọkan ti nsarẹ lọkan le lati gbẹkẹle Ọlọrun atipe ki nwon ni igboiya. Mo ndari eto iṣẹ pupọ papọ ti awon ajihinrere, ti nwọn nran ara won lọwọ lati tan ihinrere yika nipa aimọ awọn Ijọba alaṣepọ. Lori gbogbo eyi, ti eniyan ba ni lati fọju de ibi wipe ki o ma ri ọwọ Ọlọrun bi o ti nṣiṣe, boya ko ni le ri ti ajihinrere pẹlu.

Ni ipari, ifẹ aisimi ti awọn Ọlopa ni si gbogbo ise mi ati ibi ti mo wa ko jẹki nwọn mọ nkankan nipa awon Ajihinrere wọnyi. Lekan si nwọn wa mi ri, nwọn tun fi mi si ẹwọn. Fun awon idi kan, nwọn o fi ebi mi si ẹwọn ni ọtẹ yi, boya nitoripe gbogbo eniyan lo ti mọ mi. Mo ti lo odun mejo ati abo ni ẹwọn mo si ti ni ominira odun meta. Ni isin, nwon fe fi mi si ewon fun odun marun ati abo sii.

Ẹwọn ti a fi mi si ni ekeji, ni ona pupo,

je eyi ti o buru ju ti akoko lo. Mo ti mọ daju ohun ti o ye ki nreti. Ipo ara mi buru pupo lẹsẹkanna. Sugbon a tesiwaju pelu isẹ abẹle ti Ijo Abẹle ninu ẹwọn abẹle Ijọba alasepọ.

## A SE ADEHUN KAN - AWA NWASU, AWON NNA WA:

Ojẹ ohun ti o lodi si ofin lati wasu fun awọn ẹlẹwọn to ku. A si mọ wipe ẹnikẹni ti nwọn ba mu ti o nṣe eyi yio jiya gidigidi. Die ninu wa pinnu lati san idiyele rẹ lati ni anfani lati wasu, nitorina a gba ipinnu wọn. Adehun ni eyi jẹ. Awa nwasu, nwọn si nna wa. Inu wa ndun bi a ti nwasu. Inu awọn na ndun bi nwọn ti nna wa, nitorina inu gbogbo wa lo dun.

Ohun ti ngo wi yi sele ni opolopo igba ju bi mo ti le ranti lo. Arakunrin kan nwasu fun awon ẹlẹwọn to ku nigbati awọn oluso ja wole lairotẹlẹ ti nwọn si da ọrọ mọ ọ lẹnu pelu iyalẹnu. Nwon wọ ọ jade gba odẹdẹ lo si "yara ti nwon ya soto lati ma fi na eniyan." Lẹhin nina ti o dabi eni wipe koni dawo duro, nwọn mu u pada nwon si tari rẹ si ile iyara ẹwọn, nwọn si ti ṣe e lẹṣe, gbogbo ara re si kun fun eje. Pẹlu ẹsọ,ofi ara re ti o ti baje o dide, o si na aṣọ rẹ pẹlu irora, o ni "Nisisiyi, eyin ara, nibo ni mo ba de ki nwon to di mi lọwọ?" O si tun nwasu ihinrere re lo!

Mo ti ri awon ohun ti o dara! ·

Nigba miran, awọn ti nwọn nwasu kii se alufa. Awon okunrin ti oni imisi, Ẹmi mimọ maa nwasu daradara nigba pupọ. Gbogbo ọkan wọn ni o wa ni inu ọrọ wọn, nitori lati wasu ninu iru ayika ailera bayi koję nkan yẹpẹrẹ. Nigbana awon Oluṣọ, nwon si mu Oniwasu yi jade, nwọn a si naa ti yio fi fere ku.

Ni ẹwọn Gherha, nwọn da Onigbagbọ kan ti orukọ rẹ njẹ Grew ni ẹjọ wipe ki nwọn naa titi yio fi ku. Eleyi gba ọsẹ diẹ. Pẹlẹ pẹlẹ ni nwọn fi naa. Nwọn o fi oje ire ti oni kumo ni ori lu u ni atẹlẹsẹ, nwon o si fi silẹ fun igba diẹ. Lehin iṣẹju die, nwon a tun luu, lehin isẹju diẹ miran nwọn a tun luu. Nwon luu ni ẹpọn lẹhinna onişegun fun u ni abere. Ara rẹ pada bọ sipo nwọn si fun u ni ounje daradara lati mu ki agbara rẹ tun pada bọ sipo nwọn tun wa lu u titi o fi ku lọwọ nina ti o jẹ pẹlẹpẹlẹ ti nwọn tun na yi. Eniti o se asaju idaloro yi je ọmọ ẹgbẹ ajọ igbimọ ti gbogbo egbe awon eleto Ijọba alaṣepọ, ẹniti orukọ rẹ njẹ Rek.

Nisisiyi, ni iseju kan, Rek a sọ ọrọ kan ti awọn ti ngbe Ijoba alasepo ma nso nigbakugba si awọn Onigbagbọ: "O mo, emi ni Ọlọrun. Mo ni agbara iye ati iku lori re. Ẹniti o wa ni ọrun kole pinnu lati fi o si aiye. Ọwọ mi ni gbogbo ipa wa. Bimo bafe ki owa laiye timo bafẹ, ao pa o. Emi ni Ọlọrun!" Bayi ni okunrin yi nfi Onigbagbọ yi se ẹleya.

Arakunrin Grecu ninu ipo ti o banilẹru yi, fun Rek ni idahun ti o dara pupọ eyiti mo gbọ lenu Rek fun ara rẹ nigbati o ya. O wipe: Iwo ko mo titobi oro ti o so. Loto ọlorun ni ọ. Gbo-

tiwa gegebi idamewa fun Oluwa wa.

A da Onigbagbo kan ni ẹjọ iku. Ki nwọn gbo kokoro Labalaba ni ojẹ Labalaba, bi o ba dagba ni ona ti o tọ. A ko da ọ lati jẹ adaniloro, ọkunrin apaniyan. A da ọ lati jẹ eniyan-bi-Ọlọrun. Jesu sọ fun awon eniyan Ju ni igba tirẹ: "Ọlọrun kekeke ni nyin! emi Ọlọrun wa ninu okan re. Ọpọlọpọ ti o ti dabi rẹ, ọpolọpọ oninunibini, gẹgẹbi Aposteli Paulu, ti so ni igba kan 'pe ohun itiju ni fun eniyan lati hu iwa buburu, ati wipe nwọn le ṣe ohun ti o dara ju wọnyi lọ. Nipa bẹ nwọn tidi alabapin ninu iwa ti Ọlọrun. Gba mi gbọ Ọgbẹni Rek. iṣẹ ti a pe ọ si gan ni lati jẹ Ọlọrun kekere, iwa-bi-Ọlọrun, ki ise idaniloro."

Ni iseju kanna, Rek ko kọ ibi ara si oro tiẹ niti o nfi iya jẹ yi sọ, gẹgẹbi Saulu ti Tarsu ko ti kọ ibi ara si ijeri daradara ti Stefanu ti a pa ni oju rẹ. Ṣugbọn awọn ọrọ wọnyẹn ṣiṣẹ ni ọkan rẹ. Bẹ na ni oye ye Rek nigbati o ya wipe iṣẹ ti a pe oun si gan niyi.

Ẹkọ nla kan ti gbogbo nina yi, idaloro yi ati ipakupa ti awọn ti nwọn ngbe ijọba alaṣepọ yi mu jade: ni wipe ẹmi ni olori ara. Nigbakugba, nigbati a ba nda-wa-loro, a nmọ idaloro yi lara, ṣugbọn o ma ndabi ohun ti o jinna ti ko si papọ mọ ẹmi eyiti o kun fun ogo Kristi ati iwalaye rẹ pẹlu wa.

Nigbati nwọn nfun wa ni awe buredi kan ni ọsẹ ati ọbẹ ti o kun fun idọti ni ojojumo, a pinnu pẹlu otitọ wipe a o ma san idamẹwa wa papa nigbayẹn. Ni ọsẹ mẹwa-mewa, a mu awẹ buredi yi a si fun awọn ara tiko ni ilera to

to pa a, nwon fun ni anfani ati ri iyawo rẹ. Awon oro kehin re si iyawo re lo bayi: "O ni lati mọ wipe bi mo ti nku mofẹ ran awọn ti npa wa. Nwon ko mo ohun ti nwọn nṣe, ohun ti mo si nbere lọwọ rẹ ni wipe ki o fẹran won bakana. Ma se ni ikoro ni okan rẹ nitoripe nwọn pa olufe rẹ. A o pade ni ọrun rere." Awọn ọrọ wonyi dun mọ Oloye awọn Ọlọpa inu ti o lọ si ibi ti okunrin yi ati iyawo rẹ ti ni ọrọ pọ, nigbati o si ya, o sọ itan yi fun mi ni ẹwọn, nibiti a fi oun na si nitoripe o di Onigbagbọ.

Ni ewon ti Tirqu-Ocna, ẹlewon kan wa ti o jẹ ọdọ, oruko re a ma je Matchevici. Nwọn ti fi i si ewọn nigbati o wa ni omo odun meji-dinlogun. Nitori idaloro yi, o wa niipo aisan pupo. Ni ona kan awon ebi re mo wipe o se aisan gan, nwon si fi ogun ranse si i eyiti yio mu iyato wa larin iye ati iku. Olcye kekere na fihan o si so wipe: "Ogun ti o le gba emi re la nìyi. Sugbon aye ko si fun o lati gba eru lati ọwo awọn ẹbi re. Ni temi, ngo fe lati ran ọ lọwọ. Omode ni o'. Nko ni fe ki o ku si ewon. Ran-mi-lowo lati le ran-o-lowo! So oro fun mi nipa awon elewon elegbe re eyi yio si jẹki njare, lodo awon to ju mi lo, idi rẹ ti mo se gbe eru yi fun ọ." Matchevici dahun kankan, o ni: "Nko fe lati wa laiye ki nsi ma tiju ati wọ inu digi nitoripe ngo ri oju afinihan. Nko le gba iru ipinnu be. Mo yan lati ku." Oloye Olopa Abele yi gba ni owo o so wipe: Mo ba o yo. Nko reti idahun miran lati odo re. Sugbọn sa ngo fe da-imoran miran. Die ninu awon ẹlewon wonyi ni nwọn tidi Olufisun wa. Nwọn gba wipe awon ngbe Ijoba Communist lese, nwon si nsoro buburu nipa

nyin. Nwon nse agabagebe. A ko ni igbekele ninu won. A o fe mo bi nwọn ti se je olotito to. Ni oju nyin Ami ni nwọn je. Nwon nse ibi ti o po si nyin nipa sisọ ọrọ ati ise nyin fun wa. Oye mi wipe oko fe lati ṣe ofofo awon eniyan re. • Sugbon sa so fun wa nipa awọn wonyi ti nwon ntako nyin ki o baa le gba ẹmi re la!" Matchevici dahun kankan bi o ti se dahun ni akoko "Omo lehin Kristi ni mi, bẹni o ti kowa wipe ki a fẹran awọn ọta wa pẹlu. Awon okunrin ti nwọn nṣe ofofo wa yi nṣe ibi pupo si wa ṣugbọn nko lefi buburu gbesan buburu. Nko le sọ ọrọ ti o lodi si nwon papa mo sanu won, mo ngbadura fun nwọn, nko fẹ lati ni ohun kankan papọ pelu awọn ti ngbe Ijọba Communist. Matchevici pada wa lati ibi ti nwọn tijọ fi ọrọ we oro pelu oloye oran ilu, o si ku ni yara kanna ti mo wa. Mo rii ti o nku sibesibe o nyin Ọlọrun. Ife segun ongbe fun iye ti ara papa.

Ti talaka kan baje olufẹ orin pupo, yio fi owo ti o gbehin lọwọ rẹ silẹ fun awon akorin. Lehinna ko ni ni owo mo, sugbon ibanuje ko si fun u, o ti gbo awọn ohun daradara.

Nko wa pẹlu ibanujẹ nitoripe mo padanu opolopo odun ni ẹwọn. Mo ti ri awon ohun daradara. Emi fun ara mi ti je okan ninu awọn alailera ati awon ti ko ni lari ni ewon, sugbọn mo ti ni anfani ati wa ninu yara kanna pẹlu awon eniyan mimo nla, awon akoni ninu igbagbo ti nwon dogba pelu awon Onigbagbo akoko. Pelu ayo ni nwon fi ku fun Kristi. Didara ti igbe aiye awon eniyan mimo ati akoni igbagbọ bawonyi ko ṣe fi enu so.

Awon ohun ti mo wi ni ibi yi ki ise alatenumoju. Awon ohun ti oju ti iwa eda lọ yi ti di iwa eda fun awọn Onigbagbo fi Ijo Abẹle.

Ijo Abẹle yi ni Ijọ ti o ti wa si ifẹ akọkọ.

Ki nto wọ ẹwọn, mo feran Kristi pupọ. Nisisiyi, lehin igba ti mo ti ri "iyawo Kristi" - ara Re ti emi ni ewon, ngo so wipe mo feran Ijo Abele to bi mo se feran Kristi fun ara Re. Mo ti ri ẹwa Rẹ, ẹmi irubo Re

## OHUN TIO ṢELẸ SI IYAWO ATI ỌMỌ MI

Nwon mu mi kuro ni odo iyawo mi. Nko mo ohun ti o sele si i lehinna. Afi lehin ohun pupo ni mo gbo wipe nwon ti fi oun na si ewon. Awon obinrin Onigbagbo njiya pupo ju awon okunrin lo ni ewon. Pẹlu ipa ni awon olusọ fi nba awon obinrin sun. Egan ati iwa irira yi bani leru. Pelu ipa ni nwọn fi nmu awọn obinrin lati se ise ti o le ni ibi odo lila ti nwon ni lati ko, nwọn si nilati gbe ẹru kanna ti okunrin ma gbe. Nwon ni lati fi ọkọ tu ilẹ ni igba otutu. Awọn pansaga obinrin ni nwọn fiṣe alabojuto, nwọn si nyipada ninu idaloro awọn oloto. Iyawo mi ti je koriko bi eran osin lati le wa laye. Jijẹ ni ekute ati ejo ni ibi odo lila yi fun ẹlẹwọn ti ebi

npa. Okan ninu awọn ohun ti oma nmu inu oluṣọ dun ni ojo isimi ni lati so awọn obinrin si inu ọdo Danube ki nwon si tun wa won jade bi eja, lati rerin nipa nwọn, lati fin wọn se ẹleya nigbati nwọn ba ri ara won ti o re, lati so won sinu odo pada, ki nwọn si tun wa wọn jade bi eja. Nwon so iyawo mi si inu odo Danube ni ọna yi.

Nwọn fi ọmọ mi sile lati ma rin kiri titi lati igbati nwon ti mu iya ati baba re lo. Lati kekere wa ni Mihai ti je olufokansin gidigidi, beni osi ni ifẹ gidi si ohunkohun ti oba ti je ti igbagbọ. Lẹhinna, lati omo odun mesan, nigbati a ti mu baba ati iya re kuro lodo re, O koja larin akoko idamu ninu igbesiaiye re gegebi Onigbagbo. O koja larin ikoro, o si nse iyemeji nipa gbogbo isin rẹ. Ni ibiti o dagba de yi, o ni iyonu eyiti awon omode ki saba ni. O ni lati ronu nipa bi o ti sele ma ri owo ounje ojo re gba.

O je oran nla lati ran ebi awon Onigbagbọ ti o je ajeriku lọwo. Awon ọmọge obinrin mẹji ti nwon ran a lọwo ni nwon mu lehinna ti nwon si na won to bẹ ti o fije wipe nwon yaro papa di isisiyi lehin ọdun marun-din-logun. Nwon da obinrin kan lẹjọ ẹwọn ọdun mejo fun ẹṣẹ wipe o ran ebi awon elewọn lọwo, nitoripe o fi ẹmi re wu ewu nipa mimu Mihai lọ si ile re. Gbogbo ehin re pata ni nwon ta yọ. Nwọn ṣe awon egun re, ko ni le rin mo lai lai. Oun na yio je arọ titi aiye rẹ.

## "MAHAI GBAGBO NINU JESU!"

NI ọmo odun mọkanla, Mihai bere si gba owo ti o fi njeun gegebi ọsiṣẹ dede. Iya jije pupọ jẹ ki o ma ṣiyemeji ninu igbagbọ re. Sugbọn lẹhin ọdun meji ti a ti fi iyawo mi si ewon, nwon fun Mihai ni aye ati rii. Awon oro ti o kọko so ni wipe: "Mihai, gbagbo ninu Jesu!" Awọn oluso pelu ibinu ehanna, fa a kuro ni odo Mihai nwọn si mu u jade. Mihai sunkun bi o tiri ti nwon nfa iya re lo. Iseju yi ni iseju iyilokanpada re. O mo wipe ti Kristi ba ṣe eniti eniyan le feran ni abe iru ipo bayi, loto oun ni Olugbala toto. Lehinna, o sọ bayi pe: "Ti isin igbagbọ ko ba ni awon ijiya miran ni isaju rẹ ju wipe iya mi ni igabgo ninu re, eyiti to fun mi." Iyẹn ni ọjọ ti o gba Kristi ni kikun

Ni ile iwe, o ni lati ma a ja ni abele-abele lati le ye. Omo ile-iwe dada ni o je nitori idi eyi nwon fun u ni ẹbun aso tere pupa ti okunrin fi nse oso si orun - ami wipe eniyan je omo egbe awon odo Alamo sile ti Ijoba Alasepo. Omo mi so bayi: "Nko ni je wo aso tere ti oso orun ti awon ti nwon fi Baba ati Iya mi si ewon." Nwọn le e kuro ni ile-iwe fun eyi. Lehin igba ti o ti padanu odun kan, o tun wo ile-iwe, o si nfi otitọ wipe oun je omo elewon Onigbagbo pamo.

Nigbati o ya o ni lati ko iwe ti o dojuko Bibeli. Ninu iwe yi, oko bayi: "Awon ijiyan

ti o lodi si Bibeli ko lese nile beni awon oro ti

nwon so ti o lodi si Bibeli ko so oto. Dajudaju ojogbon yi ko ka Bibeli. Bibeli wa ni irepo pelu eko-ijinle," lekan si nwon tun le e jade Ni akoko yi o ni lati padanu odun meji ile-iwe.

Ni ikehin, nwon yonda re lati ko eko ni ile eko giga ti awon alufa. Ni ibi yi nwon ko o ni eko nipa "Imo Olorun gegebi Marx ti mo." Gbogbo alaye ni nwon se gegebi awose ti Karl Marx. Mihai se ikilo ni gbangba larin egbe re. Awon akeko le e ko si le pari eko re nipa imo Olorun.

Nigabkan ti o wa ni ile-iwe Ojogbon kan soro alaigbagbo pe Olorun kosi, Omo mi dide o si tako Ojogbon yi, o si nso fun u iru ohun ti o nse nipa mimu awon odomokunrin sina. Gbogbo awon omo egbe re si gba si lenu. Pataki ni wipe ki enikan ni igboiya lati koko soro. Lehinna gbogbo awon to ku a si gba si lenu. Lati le ni eko, ni opo igba abele-abele ni o ni lati maa fi otito wipe oun je omo Wurmbrand, elewon Onigbagbo pamo. Sugbon ni igba pupo ni asiri yi ntu, lehin eyi ti nwon yio pe e lo si yara alakoso ile-iwe, iyen yio si le e jade.

Mihai jiya ebi pupo. Awon ebi awon Onigbagbo ti a so si tubu ni ilu awon eleto Ijoba alasepo ma nfere ku nitori ebi. Ese nla ni lati ranwon-lowo.

Ngo so fun o iru ijiya kansoso ti ebi kan ti mo mo fun ara mi. Arakunrin kan wo ewon nitori ise re ni Ijo Abele. O fi iyawo kan ati omo mefa sile. Awon omo re agba obinrin meji, okan omo odun meta-din-logun, ekeji omo odun mokan-din-logun, ko ri ise. Awon kansoso ti nwon nfun ni ni ise ni ilu Ijoba alasepo ni Ijoba ilu, beni nwon ki i fun awon Omo

Onigbagbo "arufin" ni ise. Jowo, mase da ejo itan yi gegebi iwon ti iwa! Otito ibe ni ki o gba! Awom omo-binrin meji Onigbagbo ajeriku kan - Onigbagbo ni awon na bere si se agbere lati le pese owo fun lilo awon aburo won okunrin ati iya won ti ose alaisan. Nigbati aburo won okunrin ti oje omo odun merinla, ri eleyi, ofe ya were ti ofi je wipe ibi ti nwon ti ntoju awon asiwin ni nwon gbe e si. Nigbati o ya, lehin odun pupo, baba won ti nwon fi si ewon de, adura re kansoso ni wipe: "Olorun tun mu mi lo si ewon. Nko le roju lati ri eleyi." Adura re ti gba o si tun wa ni ewon nisisiyi nitoripe o jeri Kristi fun awon omode. Awon omo re obinrin kose agbere mo, nwon ti ri ise nipa gbigba ohun ti awon Olopa inu fe. Nwon ti di Olu-fisun. Gegebi awon omo Onigbagbo ajeriku, pelu eye ni nwon fi ngba won ni gbogbo ile. Nwon o teti sile lehinna nwon o so gbogbo ohun ti nwon ba gbo fun Olopa inu. Ma kan sa dede so wipe eleyi labuku ati pe o buru - loto ori be - sugbon bi ara re bi ko base ese re pelu ni pe iru awon oran ibinuje wonyi sele, wipe a ni lati fi ebi awon Onigbagbo bawonyi sile, laisi iranlowo lati owo enyin ti e wa ni ominira.

## ORI KETA

## OWO IDASILE, ATI ITUSILE FUN ISE IRANSE NI IWO ORUN.

Apapọ ọdun merinla ti ewon ni o koja fun mi. Larin gbogbo igba yi nko ri Bibeli kan ri tabi iwe miran. Mo ti gbagbe bi a ti nkọ iwe. Nitori ẹbi nla yi, ogun buruku ti a nmu ati idaloro wonyi, mo ti gbagbe ọrọ iwe Bibeli Mimọ. Sugbọn ni ọjo ti mọ mu odun merinla ṣẹ, lati inu igbagbe mi ni ese yi ti wa si ọkan mi: "Jakobu ṣise fun Rasheli fun odun mẹrinla beni ni oju re o dabi igba die nitoripe o fẹran Rasheli."

Laipe lẹhin eleyi, nwọn da mi sile nipa idasile gbogbo awọn elẹwọn ni ilu wa, idi eyi ti ọje nipa imọran gbogbo eniyan Amerika.

Mo ri iyawo mi lẹkan si. O ti duro ninu otito de mi fun odun merinla.

A bẹrẹ igbesi-aiye miran ninu ọṣi gidi nitoripe ti nwọn ba mu ẹnikan, gbogbo ohun ti o ba ni ni nwọn ngba lọwọ re.

Gbogbo awọn alufa ti a da sile ni nwọn le ri Ijo kekeke. Ijo kan ni ilu Orsova ni nwon fun mi. Egbẹ ti o nse akoso awọn Isin ti Ijoba alaṣepọ sọ fun mi wipe Ijọ yi ni Ọmọ ẹgbe marun-le-lọgbọn, nwon si tun so fun mi wipe mo ni lati jẹ aṣoju wọn ki nsi ma sọ nipa ọmọ ẹgbe kankan fun awọn Ọlọpa inu ati 'pe ki

nri wipe awọn odo ko de inu Ijo yi. Bayi ni awon ti ngbe Ijoba alasepo ti se nlo awon Ijo wonyi gẹgẹbi "irinṣe" akoso wọn.

Mo mọ, ti mo ba wasu, ọpọlọpọ ni yio wa gbọ. Nitorina nko tile gbiyanju papa lati bẹrẹ ni Ijọ ti abe ase yi. Mo tun ṣiṣe ni Ijo Abẹle, mo si nba won pin ninu awon ewa ati ewụ ti iṣe yi.

Larin awọn ọdun ti mo fi wa l'ewon, Ọlọrun ti ṣe iṣẹ nla tiyanutiyanu. Nwọn ko kọ Ijo Abẹle sile mọ beni nwon ko gbagbe re mo. Awon eniyan Amerika ati awon Onigbagbo miran ti bere si ran wa lowo, nwon si ngbadura fun wa.

Ni ọsan ọjo kan mo simi fun igba diẹ ni ile arakunrin kan ni agbegbe ilu kan. O ji mi o si sọ wipe: "Awọn arakunrin lati ilu Okere ti wa." Ni Iwọ Orun awọn Onigbagbo wa ti nwọn ko gbagbe wa ti nwọn kosi kọ wa silẹ.

Awọn egbe Onigbagbo ti se eto iranlọwo ni ikoko fun ebi awon Onigbagbo ajeriku nwọn si ngba ikọkọ ko awọn iwe fun awon Onigbagbo ati ohun iranlọwo wo ilu.

Ni yara keji mo ri awon arakunrin mefa ti nwon ti wa lati se ise yi. Nwọn ba mi sọrọ pupo. Lehin igba pipẹ nwọn sọ fun mi wipe awon ti gbo wipe ni ibugbe yi enikan wa ti o ti lo ọdun mẹrinla ni ẹwọn ati wipe awon yio fẹ ri i. Ni mo ba sọ fun won wipe emi ni okunrin na. Nwọn ni: "awon nreti lati ri enikan ti o kun fun ikanu. O ko le ṣe eni yi nitori o kun fun ayọ." Mo mu dạ wonloju wipe emi ni eni ti a ju si ẹwọn na ati wipe idi ayọ mi ni wipe nwọn ti wa ati wipe nwọn ko gbagbe wa mọ.

Iranlowo ti o duro sinsin ti o si se dede wa nwa si odo Ijo Abele. Nipa ona ikoko, a ri Bibeli pupo gba ati awon iwe Onigbagbo miran ati iranlowo fun ebi awon ajeriku. Nisisiyi ti nwon ti nran wa lowo, awa ti Ijo Abele le sise dada si.

Ki se wipe nwon fun wa ni oro Olorun nikan, sugbon a ri wipe nwon feran wa. Nwon mu oro itunu wa fun wa.

Larin awon odun iyi-lopolo-pada, a ti gbo wipe: "Ko si eni ti o feran nyin mo, ko si eni ti o feran nyin mo, ko si eni ti o feran nyin mo." Nisisiyi a ri awon Onigbagbo Amerika ati Oyinbo ti nwon fi emi won wu ewu lati fi han wa wipe awon feran wa. Nwon gba imoran lowo wa nwon si bere ona ise ikoko. Pelu ogbongbon ni nwon fi nwo ile ti awon Olopa inu yika. Awon Olopa ko si mo wipe nwon ti wole. Iye awon Bibeli ti nwon ngba koro ko wo'le ni ona yi ko le ye Onigbagbo Amerika kan tabi Oyinbo ti nwon "nluwe" ninu Bibeli pupo.

Ebi mi ati emi iba ti ye laisi iranlowo ohun ti ara eyi ti mo ri gba lati owo awon Onigbagbo ti nwon ngbadura fun wa lati okere. Bakanna ni pelu opolopo awon alufa ati ajeriku abele ni ile awon Ijoba alasepo. Mo le jeri lati inu iriri temi nipa nkan ti ara ati papa iranlowo ti ise ti o tun tobi ju eyi lo ti awon egbe Isin-Isoji ti awon Onigbagbo Oyinbo ti ilu Oyinbo (Great Britain) ti nfun wa. Fun wa, awon okunrin won dabi angeli ti Olorun ran!

Ni tori atunse ise Ijo Abele, mo wa ninu ewu nla ti mimu pelu ofin miran. Ni igba yi, egbe Onigbagbo meji - Egbe Isin-Isoji ti Norway

si awon ara Ju ati Egbe Ibasọre larin Orile-ede nipa majemu ti awon Onigbagbo Hebru san owo idasile ẹgberun meji abo poun (Egberun marun Naira) fun mi. Mo wa le fi Rumania sile.

## IDI RE TI MO SE KURO NI RUMANIA

Nko ba ti kuro-nitori awon ewu wonyi - ti awon asaju Ijo Abele o ba pase fun mi wipe ki nlo aye yi lati jade ni ilu, lati je "ohun" Ijo Abele si ara aiye ti o wa ni ominira. O wu won wipe ki nsoro si eniyan ti ila Iwo Orun aiye ni oruko won, nipa iya won ati ini won. Mo wa si Iwo Orun sugbon okan mi ko kuro lodo won. Ti ko ba se wipe oje oranyan wipe ki e mo nipa iya ati igboiya ise Ijo Abele yi ye mi, nko ba ti kuro ni Rumania lailai. Ise pataki ti a ran mi niyi.

Ki nto kuro ni Rumania, awon Olopa inu pe mi ni emeji. Nwon so fun mi wipe awon ti ri owo ti a san lori mi gba. (Nse ni Rumania nta awon omo ilu re fun owo nitori inira ti idamu aimo owo itoju eyi ti eto Ijoba alasepo ti mu wa sori ilu wa). Nwon so fun mi wipe: "Lo si iha Iwo Orun ki o si wasu Kristi ni iwon ti oba fe, sugbon mase kan wa! Mase so ro kan lodi si wa! A so oro atinuwa fun o, ero wa fun o ti oba so ohun ti o sele. Saju, fun edegbeta poun (Egberun Naira) a le ri awon egbe ti yio lu o pa, tabi a le ji o gbe. (Emi fun

ti Josua nreti, oye re si soro, o ni: "Beko". Ki wa ni itumo "Beko" yi?

O wa lati obirikiti eyi ti awon eda ko ki nwa fun lati lodi si, ṣugbọn ni ibiti oye ti ye gbogbo eniyan ati gbogbo ohun, ti nwọn si nwo ara won pelu anu ati ibakedun ti nwon si nferan pelu ina.

Iwon ti eda wa. Ni oju iwon yi, nwọn ni lati gbogun ti eto Ijoba alasepo gan ni, ni oju iwonyi yi, a ni lati gbogun ti awon ti ngbe Ijoba alasepo na, niwọn igbati o ti je awon ni nwon ngbe iwa ika ati ororo wonyi.

Ṣugbon awon Onigbagbọ ju eniyan sa, Omo Olorun ni nwon je, awon alabapin pelu ise ti Olorun.

Nitorina, awon idaloro ti mo fi nmọ'ra mi pelu ewọn Ijoba alasepo ko mu mi korira awọn ti ngbe Ijoba Alasepo. Eda Ọlorun ni nwọn. Bawo ni mo se le korira won? Bẹ nko le je ore won. Itumọ irepo ni okan kan ninu aiya meji. Nko wa ni ọkan kan pẹlu awọn ti ngbe Ijoba alasepo lese. Nwon korira imo Olorun. Mo feran Olorun.

Ti a ba bi mi pe: "O wa fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo lese abi o lodi si nwon?" Idahun mi yio je eyi ti o diju. Eto Ijoba Alasepo ni ohun eleru julo fun omo eniyan. Mo lodi si patapata, mo si fẹ lati doju ija kọ o titi a o fi bii ṣubu. Sugbon, ninu emi, mo joko ni Orun pelu Jesu, Mo joko ni obirikiti ti awon "Beko", ninu eyiti, ni aibikita pelu gbogbo ibi won, oye ye wa nipa awọn ti ngbe Ijoba Alasepo ti a si ni ifẹ won, obirikiti ninu eyiti awon eda bi Angeli wa ti nwọn ngbiyanju lati ran gbogbo eniyan

mo feran elese na. Mo feran awon ti ngbe Ijoba alasepo pelu gbogbo okan mi. Awon ti ngbe Ijoba alasepo yi le pa awon Onigbagbo, sugbon nwon ko le pa ife nwon si awon ti o tile npa won. Nko ni ikoro kankan, bi o ti wu ki o kere to, tabi irunu si awon ti ngbe Ijoba alasepo tabi awon ti nda mi loro.

## ORI KERIN

### SISEGUN IJOBA ALASEPO NIPA EMI IFE TI KRISTI

Awon ara Ju ni itan kan wipe nigbati a gba awon baba nla won la lati Egibiti ti awon ara Egibiti si ri sinu Okun Pupa, awon angeli dapo mo awon ara Israeli ninu orin ayo isegun ti nwon ko. Olorun si so fun awon Angeli wipe "Eniyan ni awon Ju nwon si le yo nipa ajabo won. Sugbon mo reti oye ti oju eyi lo lati odo nyin. Eda owo mi na ha ko ni awon ara Egibiti ise? Nko ha feran awon na pelu ni? Bawo ni e se kuna lati mo ibanuje mi nipa opin awon oloro yi lara?

Nigbati Josua wa ni eti Jeriko, o gbe oju re si oke osi wo o, si kiyesi, okunrin kan duro ni iwaju re, pelu ida re ti o fa dani, Josua to lo o si so wipe: Awa ni o wa fun tabi awon ota wa (Josua 5 :13).

Ti eniti Josua ba yi ba ti je okunrin sa, idahun re iba ti je "mo wa fun ota re" tabi nigbehin, "nko wa fun eni kankan." Awon wonyi nikan ni idahun ti eniyan le fun iru ibere bayi. Sugbon Eda ti Josua ba yi wa lati obirikiti miran, nitorina, nigbati a bi boya o wa fun Israeli tabi o sodi si i, idahun ti o so jina si eyi

ara mi ti wa ninu yara kanna ni ewon pelu Olori awọn alufa kan, oruko eni ti nje Vasile Leu, ti nwọn ji gbe ni Austria ti nwon si gbe wa si Rumania. Gbogbo ekanna re ni wọn fọ. Mo ti wa pelu awọn miran ti nwon ji gbe lati Berlin. Ni aipe yi nwọn ji awon eniyan Rumania kan gbe ni Italy ati Paris) Siwaju si nwon tun sọ wipe: "A tun le ba iwa re je nipa titan itan ka nipa iwọ pelu obinrin kan, ole jiya tabi awọn ẹse kan ti igba ewe re. Awon ara iha Iwọ Orun - papa awon eniyan Amerika - ni a le tete tanje."

Lẹhin ti nwọn dẹruba mi tan, nwọn yọnda mi lati wa si Iwọ Orun. Nwọn ni igbekele nla ninu iyilọpọlọ-pada eyi ti mo gba koja. Ni iha Iwo Orun, ọpọlọpọ ni o wa nisisiyi ti o ti gba arin ohun ti emi na ti gba koja wọnyi koja, sugbọn ti nwọn dakẹ. Awọn kan ninu wọn ngbe Ijoba Alasepo lehin igba ti awon ti nwọn ngbe Ijoba yi ti da wọn loro tan. Awon ti ngbe Ijoba Alasepo yi ti ni idaniloju wipe emi, pelu yio dake.

Nitorina ni ósu kejila ọdun 1965 ebi mi ati emi lo kuro ni Rumania.

Ohun ti mo ṣe gbehin ki nto kuro ni lati lọ si iboju ọgagun agba eni ti o pase wipe ki nwọn mu mi ti o si pase iye ọdun idaloro mi. Mo fi ododo kan si ori iboji re. Nipa sise eleyi, mo ya ra mi s'ọto lati mu ayọ Kristi eyi ti mo ni wa fun awon ti ngbe Ijoba alasepo ti o wa ni ofifo nipa ti emi.

Mo korira eto Ijọba alasẹpọ, sugbọn mo feran awọn eniyan re. Mo korira ẹse na, ṣugbọn

lowo lati le de opin igbesiaiye omo eniyan, eyiti o je lati le dabi Kristi. Nitorina ife mi ni lati tan ihinrere yi ka de odo awon ti ngbe Ijoba Alasepo, lati fun won ni ihinrere nipa iye ainipekun.

Kristi, eni ti ise Oluwa mi, feran awon ti ngbe Ijoba Alasepo O ti so fun ara re wipe Oun feran gbogbo eniyan ati wipe Oun ko ko lati fi agutan olododo mokan-din-logun sile ju wipe ki Oun yonda okan ti o sako lo lati segbe sibe. Awon Apsoteli Re ati gbogbo oluko nla ti Isin Kristi ti ko awon eniyan ni eko nipa ife fun gbogbo eniyan, eyi ti o wa ninu oruko Re. Macary mimo wipe, "Ti okunrin kan ba feran gbogbo eniyan pelu anu, sugbon ti o ba so wipe afi okunrin kan on ko feran eleyi ki ise Onigbagbo mo, nitori ife re ko fa gbogbo eniyan mora." Augustine Mimo ko pe. 'Ti gbogbo omo eniyan ba je olododo ti o si je wipe okunrin kan ni elese, Kristi yio ti wa lati roju jiya agbelebu kanna fun okunrin kan yi, o feran eni kokan pupo. Eko Onigbagbo ye mi. Eniyan ni awon ti ngbe Ijoba Alasepo beni Kristi feran won. Be na si ni okunrin kokan ti o ba ni emi Kristi. A feran elese na bi o tile je pe a korira ese na.

A mo nipa ti ife Kristi ti ngbe Ijoba Alasepo nipa ife tiwa si won.

Mo ti ri awon Onigbagbo ni ewon Ijoba Alasepo pelu osuwon ewon adota ni ese won, ti nwon si ndaloro pelu irin ti o gbona gan ti o si npupa ti nwon nfi ipa da ekun sibi iyo si won ni ofun lehin eyi ti nwon ki fun won ni omi, ti nwon nfi ebi pa, nwon a na won, otutu a si ma pa won, sibesibe nwon a ma gbadura fun

awon ti ngbe Ijoba Alasepo yi. Eniyan ko le se alaye eleyi! Ife Kristi ni eyi ti a tan kan sinu okan wa.

Lehinna, awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti nwon da wa loro si ewon pelu. Ni abe eto Ijoba Alasepo, awon ti won ngbe Ijoba yi papa awon papa awon alakoso won ni nwon nfi si ewon nigba pupo bi ti awon ota won. Nisisiyi eniti a daloro ati adaniloro jo wa ninu yara ewon kanna. Nigbati awon ti ki se Onigbagbo ba nfi iwa ikorira han si awon ti o nyo won lenu tele labe ofin, ti nwon si nlu won, awon Onigbagbo yio ma gbeja won bi o tile je pe awon na le jiya tabi ki nwon pe won ni elegbe eto Ijoba Alasepo. Mo ti ri awon Onigbagbo ti nwon nfi awe buredi won kansoso toro (ni akoko igba ye, awe buredi kan ni a ma nni ninu ose kan) beni nwon nfi ogun ti o le gba emi won la tore fun adaniloro ti Ijoba Alasepo ti o se aisan, eniti o ti di elewon elegbe won.

Oro ikehin Inlin Mamin. Oga julo ti Rumania nikan ri ti oje Onigbagbo ti o ku si ewon ni iwonyi: "Ti a ba ti awon ti ngbe Ijoba Alasepo subu ni ile wa, yio je ise mimo julo ti Onigbagbo kankan lati lo si awon titi ati lati gbeja, ninu fifi emi re wu ewu awon ti ngbe Ijoba Alasepo lowo irunu atari;opo eniyan ti nwon ti se ika si."

Ni awon ojo isaju lehin iyipada mi, mo ro wipe nko ni le wa laiye mo. Ti mo ba nrin ni titi, mo ma nni irora fun okunrin tabi obinrin kokanı ti o ba koja. Nse ni o ri bi obe ninu okan, ero wipe boya oje eni igbala tabi koje

nta mi lara. Ti omo egbe Ijo ba se, nao sun ekun fun wakati pupo. Ifojusona mi fun igbala gbogbo okan ti wa ni okan mi beni awon ti ngbe Ijoba Alasepo ko sai pelu.

Ni ihamo adagbe, a ko le gbadura mo biti tele. Ebi ti o npa wa ju eyi ti eniyan le ro: nwon tipa wa logun titi a fidi omugo. A je alailera bi egungun ara hangangan. Adura Oluwa di ohun ti ogun j-lo lati gba. Ako ni akoko to lati gba. Adura mi kansoso ti mo nwi leralera ni "Jesu mo feran Re."

Ati ni ojo ologo kan mo gba esi lati odo Jesu. "O feran mi? Nisisiyi ngo fi han o bi mo tise feran re." Lesekese, mo mo owo ina ninu okan mi eyiti o jo bi ina ti o ma nyin orun ka. Awon omo ehin ni ona Emmaus so wipe okan won jo nigbati Jesu ba won soro. Be na ni o ri pelu mi. Mo mo ife Eniti o ti fi emi Re lele ni ori agbelebu fun gbogbo wa. Iru ife bayi ko le yo awon ti ngbe Ijoba Alasepo kuro, bi o ti wu ki ese won buru to.

Awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti se ohun buburu beni nwon si nse e sugbon "Opolopo omi ko le pa ife run, beni ikun omi yi ko le mu ki o ri. Ife lagbara bi iku. Owu buru bi isa oku." Gegebi isa oku ti nfe lati ni gbogbo eniyan oloro ati talaka, omode ati agba, awon eniyan lati iran, awon orile-ede ati awon ti a da lebi nipa oran ilu, mimo ati arufin beni ife fa gbogbo re mora. Kristi, Eniti ise ife ninu eran ara, ko ni simi lai titi yio fi jere awon ti ngbe Ijoba Alasepo.

Nwon so Ojiṣe Ọlọrun kan si inu yara ti mo wa. O ti fẹrẹ ku tan. Ẹje nsan ni oju ati ara rẹ. Awọn ẹlẹwọn miran bu awọn ti ngbe Ijoba Alasepo. Pelu irora okunrin yi soro oni, "Ẹ jọwọ ẹ mase bu won! E dake! Mo fe gbadura fun won!"

## BI A TISE LE KUN FUN AYO - PAPA NINU EWON

Nigbati mo bojuwo ọdun merinla ti ewon, igbamiran ohun ayo ni. Awon elewon to ku ati papa awon oluṣọ, ni opọlọpọ igba ma nro pelu iyanu bi awon Onigbagbo se nkun fun ayo ninu awon akoko ibanilẹru bawọnyi.' Nwon kole diwa lọwọ lati korin bi o tilẹ jepe nwọn nna wa fun eleyi. Mo ro wipe awọn ẹiye olorin didun kan bayi ti ima nkorin lọsan ati loru yio korin, ti nwon ba tile mo wipe nwon opa awon ti awọn ba korin tan. Awon Onigbagbọ ni ewon ma njo fun ayo. Bawo ni inu wọn se le dun to bayi ninu ipo oloro bayi?'

Mo ma nronu ni ọpọlọpọ igba ninu ẹwon nipa ọro Jesu si awọn omo ehin Re: "Ibukun ni fun awon oju ti ori awon ohun ti enyin ri." Nisisiyi awon ọmọ ehin sese pada de lati irinajo , wọn ti o gba arin Palestini nibiti nwon ti ri ọpọlọpọ ohun ipaiya. Palestini je ilu ti a pọnloju pupọ. Gbogbo ibi ni ibe ni oje ibi irora buburu ti awon eniyan ti a nfi iya je. Awọn ọmọ ehin

ba aisan, ajakale-arun, ebi ati ibanuje pade. Nwon wo ile ninu eyi ti nwon ti mu awon olufe ilu lo si ewon nwon si fi awon obi tabi iyawo ti nwon nsunkun sile. kise aiye ti o dara lati bojuwo.

Sibesibe Jesu so wipe, "Ibukun ni fun oju ti ori awon ohun ti enyin ri." Eyi ni wipe nwon ko ri ijiya yi nikan. Nwon ti tun ri Olugbala gbogbo re, Olusepari ire ikehin, opin eyiti omo eniyan yio de. Ni igba isaju, awon aran die ti ko lewa, kokoro ti yio ma fa lori ewe, ni oye pe, lehin iwa ti aini alafia yi, aiye ti ewa yio wa labalaba pelu orisirisi awo, ti o si le fo lati ori ododo de ori ododo. Iru inu didun yi je ti wa pelu.

Ni ayika mi awon Jobu wa, awon miran ri iponju ju Jobu lo . Sugbon mo mo ipari itan Jobu; bi o tise ri ilopo meji ohun ti o tini tele gba. Ni ayika mi awon okunrin bi lasaru talaka wa ebi npa won beni nwon ni opolopo oowo ti ko si eniti o ba won toju. Sugbon mo mo wipe awon angeli yio gbe gbogbo won lo si iha Abrahamu. Mo ri won gegebi nwon o ti ri ni ehin-ola. Mo ri awon alaso akisa ti osi kun fun eri ati awon ajeriku alailera ti owa ni egbe mi gegebi awon eni mimo ti ade ni ade daradara ti ola.

Sugbon ki a ma wo awon okunrin bayi - ki se bi won ti wa, sugbon bi nwon yio ti ri. Mo tun ri larin awon oninubini bi Saulu ti Tarsu awon Paulu mimo ti ehin ola. Beni awon miran ti da bee ni toto. Awon Ijoye ti Olopa ikoko ti a jeri fun na di Onigbagbo beni inu won si dun lehinna lati jiya ni ewon

nitoripe nwon ti ri Kristi wa. Ninu awon Oluso Ogba ewon ti nwon nna wa, a ri awon ti o le dabi oluso ewon Fillipi ti o koko na Paulu mimo lehinna ti o wa di eni ti a yi lokan pada. A ero wipe laipe nwon yio bere wipe, "Kini ki emi se lati le ri igbala? " Ninu awon ti nwon nworan ti nwon si nse eleya nigbati nwon ba nde awon Onigbagbo ti a fi igbe yi lara mo agbelebu, a ri opo eniyan ti Golgotta ti ko nipe fi owo lu aiya won pelu iberu wipe awon ti se.

Ninu ewon ni a ti ni ireti fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo wipe nwon yio ri igbala. Ni ibe ni a ti gberi ogbon wipe a ni ise se fun won. Ninu idaloro lati owo won ni a ko eko ati feran won.

Opo ninu awon ebi mi ni a ti pa. Ninu ile mi ni a ti yi okan eniti o pa won pada. Ibe na ni o sije ibi ti o se dede julo. Nitorina ni ewon Ijoba Alasepo, a bi ero ise iwasu Onigbagbo si awon ti ngbe Ijoba Alasepo.

Olorun ni nkan ni ona miran ju bi awa se ma nri lo, gegebi awa ti ma nri nkan ni ona miran ju era lo. Lati oju iri omo eniyan, lati de awon eniyan mo agbelebu, ki nwon fi igbe ra won ni ara je ohun ti o buruju. Ni aika eleyi si, Bibeli pe ijiya awon ajeriku ni "Iponloju ti o fuye." Lati lo doun merinla ni ewon je akoko ti o gun fun wa. Bibeli pe ni "iseju kan ni eyi ti o nsise ogo ti o wuwo fun wa."

Eyi fun wa ni eto lati ro wipe awon ibi ti o roro ti awon ti ngbe Ijoba Alasepo yi nse, eyiti awa eniyan ko le yonda, eyiti a si ni lati doju ija ododo ko titi de opin, fuye ni oju Olorun ju bi o ti ri ni oju wa. Iwa ika won

eyiti o ti pe to adota odun, le ri niwaju Olorun, loju eniti egberun odun dabi ojo kan, bi iseju kansoso ti isimi. O si sese fun won lati di eni igbala.

Iya ni Jerusalem ti orun je osi nferan bi iya. Enu ona ode orun ko wa ni titi fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo. Beni a ko pa ina re fun won. Awon na le ronupiwada gegebi elomiran. A si nilati pe won wa si ironupiwada.

Ife nikan lole yi awon ti ngbe Ijoba Alasepo pada. (ife ti o nilati han gara yato si ife eto Ijoba Alasepo eyiti opolopo awon asaju Ijo nse). Ikorira nfo ni loju. Hitla je eni ti o lodi si Ijoba Alasepo, sugbon pelu ikorira ni. Nitorina, dipo eyiti iba fi segun won, o ran won lowo lati jere idameta aiye.

Pelu ife, ninu ewon, a gbero ise iwasu larin awon ti ngbe Ijoba Alasepo.

Nipa eyi na a ronu saju nipa awon alakoso Ijoba Alasepo.

O jo bi enipe awon alakoso ise iwasu die ko eko nipa itan Ijo Onigbagbo. Bawo ni a se jere Norway fun Kristi? Nipa jijere Oba Olaf. Russia koko gbo ihinrere na nigbati a jere Oba re Vladimir. Bakanna Hungary nipa jijere Stefanu mimo, oba re. Bakanna ni pelu Poalnd. Ni ile awon eniyan dudu, Afrika, nibiti nwon bati jere Ijoye eya kan, eya na a telee. A da Isin Isoji sile lati sa awon okunrin jo ti nwon le di Onigbagbo daradara, sugbon ti nwon ko ni agbara pupo ti nwon ko si le yi ipo nkan pada.

A nilati jere awon alakoso; i baa je ti akoso Oran ilu, Sisuna, imo ijinle tabi ti awon onise Ona sise ni ara aworan. Awon ni nwon nto

awon okan. Awon ni nwon nmo okan awon eniyan. Ti a ba le jere won, a jere awon eniyan ti nwon ns'amona ti nwon si ni ipa le lori.

Gegę bi oti ri ni oju awon Onise Olorun, eto Ijoba Alasepo ni anfani eyiti awon egbe ilana miran ko ni. Oni idari lati oju kan ju won lo.

Ti Olori ilu U.S.A. ba yipada si isin Mormony, Amerika kole titori re di Mormoni. Sugbon ti Mao-Tse-Tung ba yipada si isin Onigbagbo - tabi ti Breshner tabi Ceanshescu - gbogbo ilu won ni ole gba. Ase awon Olori rin le gan ni.

Sugbon nje o sese lati yi okan olori awon ti ngbe Ijoba Alasepo pada? Dajudaju, nitoripe inu re ko dun beni o wa ninu ewu bi eniti a nfi iya je. O fere se gbogbo awon alakoso Ijoba Alasepo ti Russia ni a ju si ęwon ni ikęhin tabi ti a yin ni ibon lati owo elegbe won. Bakanna ni o ri ni China. Awon asaju ilu ti o jina si eti okun papa biti lagoda, Yexhov, Beria, ti o dabi eni pe nwon ni igbagbo agbara ni owo wa si opin gegebi ti awon alodi isote ti o koja: eyi nipe nwon a yin'bon si nwon ni orun, osi pari pelu won ni yen. Ni aipe yi bi akisa ti o legbin ni nwon se ju Shelepin, olori apa oke "Soviet Union" ati Rankovic, Olori apa Oko Yugoslavia nu.

## BAWO NI A ṢELE DOJU IJA KO ETO IJOBA ALAṢEPO NIPA TI EMI?

Ijoba Alasepo yi ko mu inu enikeni dun titi kan awon ti nwon nsee lati jere nipa re.

Awọn wọnyi papa ma nbẹru wipe ni ale-kale oko awon Olopa inu le mu won lo nitoripe eto egbe ti yipada.

Mo ti mọ opọlọpọ awon asaju Ijọba Alasepo fun ara mi. Awon okunrin ti okan won wuwo gan ni wọn. Jesu nikan lole fun won ni isimi.

Lati jere awon alakoso Ijọba Alasẹpọ fun Kristi leje lati gba gbogbo aiye la lowọ iparun, o le gba ọmọ eniyan lọwọ ẹbi nitoripe nisisiyi pupo ninu owo ijoba ni nwon ni lati na si ori omo ogun. Lati jere awon alakoso Ijoba Alasepo le mu opin wa si iwa ifale ti owa larin awon orile-ede. Lati jere awon Alakoso Ijoba Alasepo nilati mu ayo kun inu Kristi ati awon Angeli. O leje ibori fun Ijo Onigbagbo. Gbogbo ibi ti awon Ojise Olorun ti-nsise pelu inira, bi iru New Guinea tabi Madagascar, yio tele pelu irọrun ti a ba le jere awon Alakoso Ijoba Alasepo nitori elèyi yio fun awon Onigbagbo ni okun titun patapata.

Emi fun ara mi ti mo awon ti ayi lọkan pada ninu awon ti ngbe Ijoba Alasepo. Emi fun ara mi je eni ti nja bi alaigba Olorun gbo ni igba ewe mi. Awon tiko gba Olorun gbo ati awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti ayi lokan pada feran Kristi pupọ, nitoripe nwon ti se pupo.

Ero ti o jinle ni a nilo ni ise Olorun. Bi a ba wo nipa ti igbala, ogba ni gbogbo okan. Ọse pataki julọ lati jere okunrin kan ti oni ipa lori opolọpọ, ti yio jere ẹgberun aimoye lehinna, ju lati soro si alaigbede kan ninu igbo pelu idaloju fun oun nikan. Nitorina Jesu yan lati pari ise ihinrere re ki se ninu ileto kekere kan,

sugbon ninu Jerusalemu, ibi ti ose ilu olori fun ti nkan emi ni gbogbo aiye. Fún idi kanna yi ni Paulu fi lakaka pupo lati de Romu.

Bibeli so wipe: "Iru omo obinrin na yio fo ori ejo naa." Nse ni awa nrin ejo na ni ikake ni kun, asi nmu ki o rerin. Ori ejo yi wa ni ibikan larin Moscow ati Peking, ki ise ni Tunis tabi Madagascar. Awon ilu ti Ijoba Alasepo ni o nilati je aniyan awon asaju Ijo Onigbagbo ati awon alakoso ise Olorun julo ati pelu-pelu Onigbagbo kankan ti oba lajo.

A ni lati pa ipa ona ise ti. A ti ko wipe "Ifibu ni fun okunrin na ti ofi etan se ise Oluwa. Ija ojukoju nipa ti emi lori eto Ijoba alasepo, lati owo Ijo Onigbagbo ni ose pataki. Ko si eniti o le bori ninu ogun nipa wipe o ngbeja ara re afi ti o ba nja. Sodo eto Ijoba Alasepo, Ijo Onigbagbo titi di isisinyi ti ngbeja ara re, nwon npadanu ilu kan lehin ikan si owo eto Ijoba Alasepo.

Eyi nilati yipada lesekese ninu gbogbo Ijo gegebi okan. Orin Dafidi kan wipe Olorun ge awon irin gboro na lagbedemeji. Kekere ni awon irin gboro ti a fi di oju ferese ati ilekun ni ewon je ni oju re.

Ijo ti isaju sise ni ikoko ati ni ilodi si ofin, o si bori. A nilati tun ko lati sise ni ona kanna.

Nko ni oye idi re ti a fi npe opolopo awon eniyan ti inu Majemu Titun ni oruko anije won titi di igba Ijoba Alasepo. Nwon a pe Simeoni ni Niger, Johannu ni Marku ati bebelo. Oruko ikoko ni a nlo ni ise wa nisisiyi ni awon ilu Ijoba Alasepo.

Nko mo idi re tele ti Jesu, nigbati o fe seto

ounje ajekẹhin re ko fi wasu sugbon ti o wipe, "Lo si inu ilu ki osi wa okunrin kan ti o ru ikoko iponmi." Nisisiyi oye wa ye mi. Awa ma nlo iru ami ikoko ti a le fi mo nkan ninu ise Ijo Abele.

Ti a ba fohun sokan lati sise bayi - lati pada wa si ilana isin Kristi, ni kutukutu - a le sise pẹlu iyorisi rere fun Kristi ninu awon ilu Ijoba Alasepo.

Sugbon nigba ti mo ba awon asaju Ijo ti iha Iwo Orun, dipo ife si awon ti ngbe Ijóba Alasepo, eyiti iba ti sunwon si iseto tipe fun ise iwasu ihinrere ni awon ilu Ijoba Alasepo, mo ri aye ise itoju ilu won ni isoju awon ti ngbe Ijoba Alasepo, mo ri aye ise itoju ilu won ni isoju awon ti ngbe Alasepo. Nko ri oju anu ti alanu ara Samaria si awon okan ti nwọn ti segbe ti ile Karl Marx.

Dajudaju eniyan ki igba ohun ti o ka ninu igbagbọ re gbo, afi awọn nkan wonni ti o setan lati ku fun.

Awọn Onigbagbọ ti Ijo Abẹle ti fihan pe awon setan lati ku fun igbagbo won. Nisisiyi mo tesiwaju pelu iru ise ti o le mu ki nwon tun so mi si ewọn ni ilu Ijoba Alasepo kan, idaloro titun ati iku nitori wipe mo nse amona ise Ọlọrun ni ehin irin gboro ti a fi si oju ferese ati ilẹkun, mo si nfi emi ara mi wu ewu. Mo gba awọn ohun ti mo ko gbo.

Mo ni eto lati bere pe: Nje awon asaju Ijọ Amerika ti nwọn wa ni irepo pẹlu eto ijọba Alaṣepọ ṣetan lati ku fun igbagbọ wọn yi? Ta lo di wọn lọwo lati fi ipo wọn nla silẹ ni iha Iwọ Orun lati di awọn alufa labẹ ase iha Iwọ Orun,

ki nwon wa ni ifọwọ-so-wọpọ nibe - ni oju kanna - pẹlu awọn ti ngbe Ijoba Alasepo? Ko si asaju Ijọ iha Iwọ Orun kan ti o ti sọ eri iru igbagbọ bayi.

Oro ọmọ eniyan ndagba lati inu pataki wipe ki awọn eniyan ni oye ara won ninu ṣiṣe odẹ, ati pipa ẹja bakanna ati lẹhinna ki nwọn jọ ma mu awọn nkan jade ti ose pataki fun igbe aiye ati pe ki nwọn se alaye imo wọn fun ara won. Ọrọ ọmọ eniyan kan kosi ti a le fi ṣe alaye ni kikun awọn nkan iyanu Ọlọrun ati giga igbesi aiye nipa ti ẹmi.

Bẹgẹgẹ, ọrọ omo eniyan kan kosi ti a le fi ṣe alaye ni kikun iwa ibi. Nję o le ṣe alaye ninu ọrọ ohun ti okunrin kan nro ti awọn Nazi fe ju sinu ileru tabi eniti ori ti nwon so omo re sinu ileru yi.

Nitorina kosi anfani wipe a fẹ ma sẹ alaye awon iya ti awọn Onigbagbo tije, ti nwọn si nje di bayi labẹ awọn ti ngbe Ijoba Alaṣepo.

Mo wa ni ẹwọn pẹlu Lucretin Patrascana, ọkunrin ti o mu Ijọba Alasepo gbilẹ ni Rumania. Awọn ẹlẹgbẹ rẹ san ẹsan fun nipa fifi si ẹwọn. Bi o tile jepe ara re le koko, nwon fisi awujo awon were titi oun na fiya were pelu. Bakanna ni nwon se si Anna Panker, Akowe Ijoba ilu won tele. Ni igba pupo ni nwon ma nse awon Onigbagbo bayi na. Nwon a jeki ina mona-mona ki o gbon won titi. Nwon gbe won si inu awon irin gboro.

Eru ba awon araiye nipa ohun ti o nsele ni igboro awon China. Ni oju gbogbo eniyan, Oluso pupa nse ise oru re. Nisisiyi gbiyanju lati woye ohun ti o nsele si awon Onigbagbo ninu

ewọn China, eyiti ẹnikankan ko ri!

Irohin ti a gbọ gbẹhin ni wipe ẹnikan ti oma nko iwe ihinrere ti o lokiki ati awọn Onigbagbọ miran, ti nwọn kọ lati sẹ igbagbọ wọn, ni nwọn ge . ni eti mejeji, ahọn ati ẹsẹ kuro.

Sugbọn nkan ti o buru julọ ti awọn ti ngbe Ijoba Alasepo nṣe ki iṣe wipe nwọn da awọn eniyan loro abi pe nwọn npa ara eniyan. Pẹlu ibajẹ ni nwọn fi npuro lati fi yi ero awọn eniyan pada ati pe ki nwọn fi oro pa ọkan awọn ọdọ ati awọn ọmọde. Nwọn ti fi awọn eniyan wọn si ipo asaju ninu awọn Ijọ lati dari awọn Onigagbọ ati lati pa awọn Ijo wọnyi run. Ẹko ti nwọn nko awọn odo ki se wipe ki nwọn ma ni igbagbo ninu Olorun ati Kristi nikan, sugbọn pe ki nwọn korira awọn orukọ wọnyi.

Ninu ọrọ wo ni ati le se alaye ọran ibinuje awọn ajeriku Onigbagbo lẹhin igbati nwọn ba ti wa si ile lẹhin opolopo odun ni ewọn, awọn omo won ngba won pelu egan, nitoripe awọn na fun ara wọn ti bere si gbagbo pe Ọlorun kosi!

Iba die ninu iwe yi ni afi takada ko. Eje awon okan ti o nseje ni mo fi kọ eyiti o ju.

Afi wipe, gẹgẹbi igba ti Danieli, awọn okunrin meteta ti aju si inu ileru, lẹhin igba ti a gba wọn la tan, ko run bi ina; bẹgẹgẹ ni awọn Onigbagbọ ti nwọn ti ni awọn ewọn Ijọba Alaṣepo ko run bi ikorira si awọn ti ngbe Ijoba Alaṣepo.

Ti o ba fi ese re gba ododo ni ori, yio san ẹsan fun o nipa fifun o ni orun didun re. Bẹgẹgẹ ni awọn Onigbagbọ, nigbati awọn ti ngbe Ijọba Alaṣepo ba da wọn loro tan nwọn nsan idaloro

yi pada pelu ife. Opolopo ninu awon ti ofi wa si ewon ni a mu to Kristi wa. Ife kan ni osi gaba le wa lori: eyi ni lati fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti nwon ti mu wa jiya ni ohun ti o darajulo ti a ni eyi ni igbala na ti o ti odo Oluwa wa Jesu Kristi wa.

Nko ni anfani na, eyiti opolopo ninu awon elegbe mi ninu igbagbo yi ni, lati ku iku ajeriku ni ewon. Nwon da mi sile beni mo tun le jade kuro ni Rumania wa si Iwo Orun.

Beni ni Iwo Orun mo ri wipe imo ti o lodi patapata si eyiti o wopo ni Ijo Abele ti o wa lehin irin gboro ati oparun ti a fi se ikole si oju ileku ati ferese ni o wa ninu opolopo ninu awon asaju Ijo. Opolopo awon Onigbagbo ni Iwo Orun ni ko ni ife fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo. Eri re ni wipe nwon kose ohunkohun fun igbala awon ti nwon wa ni awon ilu Ijoba Alasepo. Nwon nse iwasu fun awon Ju, iwasu fun awon Imole ati iwasu fun awon elesin Budda. Nwon nse iwasu lati yi Onigbagbo Ijo kan lokan pada lati wa si Ijo miran. Sugbon nwon ko ni iwasu kankan fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo! Nwon ko ni ife won. Bibeko iba tipe ti nwon o ba ti da iru ise iwasu yi sile, gegebi Carey bi o ti ni ife awon eniyan India ati Hudson Taylor ti oni ife awon eniyan China, ti olukuluku won fi da ise pataki sile.

Sugbon ko to wipe nwon ko feran awon ti ngbe Ijoba Alasepo ati pe nwon kose nkankan lati jere won fun Kristi. Nipa itelorun won, nipa aibikita nwon, ati nigba miran nipa sise bi elegbe ninu ife buburu gan, awon asaju Ijo miran ni Iwo Orun ma nfun awon ti ngbe

Ijoba Alasepo ni agbara ninu iwa aigbagbo won. Nwon nran awon ti ngbe Ijoba Alasepo lowo lati yoju si awon Ijo Iwo Orun ati lati je Olusamona ninu awon Ijo ati ni gbogbo agbaiye. Nwon nmu awon Onigbagbo sai mo ewu ti o wa ninu eto Ijoba Alasepo.

Ni aiferan awon ti ngbe Ijoba Alasepo ati ni aise ohunkohun lati jere won fun Kristi (ni abe iboju wipe a ko fun won ni aye ati se be, bi eni wipe awon Onigbagbo isaju gba ase lowo Nero lati tan ihinrere ka) nwon ko feran ara awon agbo ti won pelu. Nitoripe ti a ko ba jere awon ti ngbe Ijoba Alasepo fun Kristi, nwon yio segun iha Iwo Orun nwon yio si fa isin Kristi tu nibe pelu.

## AIKA AWON EKO INU ITAN SI

Ni awon ogorun odun ti isaju, isin Kristi gbile gan ni iha Airwa Afrika. Lati ibe ni Augustine mimo, Cyprian mimo Athamasium mimo ati Tertin Ilian ti wa. Awon Onigbagbo iha Ariwa Afrika se abibikita pelu ise kan: lati jere awon musulumi fun Kristi. Abajade re ni wipe awon musulumi wonyi gbogun si iha Ariwa Afrika nwon si fa isin Kristi tu fun opolopo ogorun odun. Ti awon musulumi ni iha Ariwa Afrika je titi di oni, beni awon egbe Iwasu Kristi npe won ni "Odi awon ti a ko le yi lokan pada."

**Ejeki a ko eko lati inu itan!**

Ni igba isodi iyipada, ife isin ti Huss, Luther ati Calvin se dede pelu ife ti awon

Oyinbo lati ṣegun ajaga ti Ijọba Ọlori awon Alufa ilu Romu, eyiti ojẹ agbara ti o nponi loju labe ofin ilu ati isunna. Bakanna ni ife Ijo Abele ni ti itan ihinrere ka fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo ati awon ti nwon nfi iya je se dede pelu ifẹ gbogbo awon eniyan ti o wa ni ominira ti o ṣe pataki ninu ti itẹsiwaju lati ma wa ni ominira.

**Kosi agbara ti akoso ilu kan ti ole bi eto Ijoba Alasepo subu. Awon ti nwon ngbe Ijoba Alasepo ni agabra ti o papo si oju kan, beni lati kọ oju ija si won nipa ti ogun a je lati bere ogun agbaiye titun pelu egberun aimoye ti yio jiya re. Bakanna ọpolọpo ninu awon Alakoso ti iha Iwọ Orun ni ati yi lopolo pada ti ofi je wipe nwon ko kan tie fe lati bi awon Alakoso Ijoba Alasepo subu. Nwọn ti wi be nigbakan. Ife won ni wipe ki iwa ogun kikojo, kike egbe odaran jo,** arun **buruku ti o ma npa eniyan ati arun ti o ma nba fukufuku ja pare, sugbon kise eto Ijoba Alasepo, eyiti oti pa ọpọlọpo emi ju ti gbogbo nkan emi wonyi papọ.**

**Ilya Ehrenburg, eniyan Soviet ti o ma nkọ we, so wipe ti Stalin oba se nkan miran ni gbogbo aiye ju wipe ki o ma ko oruko awon ti o njiya lailebi wonyi, igbesiaiye re iba ti gun lo lati se ise na pari. Kruscheve so fun ipejọ ti ogun ti awon egbe Ijoba Alasepo pe, "Stalin pa egberun aimoye awọn ti o ngbe Ijoba Alasepo ti nwon se olotọ ti nwon ko si ni ebi. Ninu awon omo egbe ati awon ti nwon fe wo inu egbe mokan-din-logoje ti ajọ igbimọ apapo ti nwon yan ni ipejọ keta-din-logun, meji-din-logorun, eyi ni adorin ninu ọgorun kokan ni**

nwon mu lehinna ti nwon si yin bon pa."

Nisisiyi woye ohun ti o se si awon Onigbagbo! Kruscheve se Stalin, sugbon ohun kanna ni o nse lo. Lati odun 1959 idaji awon Ijo ti Soviet Russia ti osi wa nisisiyi ni nwon ti ti

Ni China iwa ara oko titun kan wa nisisiyi ti o buru ju ti igba Stalin. Igbasiaiye ti Ijo ni gbangba ni nwon da duro patapata. Ni Russia ati Rumania, nwon sese nmu awon miran. (A sese gbo nisisiyi wipe nwon mu opolopo awon Onigbagbo ni Russia)

Pelu ipaiya ati etan,ni awon ilu ti nwon ni to adota oke lona adota oke eniyan ninu re, gbogbo awon odo ibe ni nwon lo lati ni ikorira si ohunkohun ti oba tise ti Iha Iwo Orun ati papa julo si isin Kristi.

Ki se ohun ti oje ajoji ni Russia lati ri awon Osise Ijoba Alasepo ti nwon duro ni enu ona awon ile isin ti nwon nso awon omode. Nwon a gba awon ti nwon ba ri ti o nlo si ile isin leti, nwon a si ju won si ita. Pelu eto ati eso ni nwon fi nto awon ti yio run isin Kristi ni iha Iwo Orun!

Agbara kan ni o le bi eto Ijoba Alasepo subu. Agbara kann yi ni ti omu awon ilu Onigbagbo gba ipo agbara Oba Keferi ti Romu, agbara ti o so awon ehanna bi Teutons ati Vikings di Onigbagbo, agbara ti o bi ilana ofin ti se ti eje nipa iwa ibi re subu. Agbara yi ni agbara ihinrere, eyiti Ijo Abele ti owa ni awon ilu Ijoba Alasepo duro fun.

Lati mu Ijo yi duro ati lati ran a lowo ki ise ohun isokan pelu awon ara ti o njiya nikan.

Oje iye tabi iku fun ilu nyin ati fun awon Ijo nyin. Lati mu Ijo yi duro, ki ise fun anfani awon Onigbagbo ti owa ni ominira nikan, sugbon o tun ni lati je akoso awon Ijoba ti owa ni ominira.

Ijo Abele ti jere awon alakoso Ijoba Alasepo fun Kristi. Gheorghiu keji asaju awon eniyan Rumania, ku bi eni ti a ti yi lokan pada lehin igba ti o jewo ese re. Ni awon ilu Ijoba Alasepo, awon omo egbe Ijoba Alasepo wa ti nwon je Onigbagbo ni ikoko. Eyi le tan ka. Nigbana a o le ma reti iyipada gidi ninu akoso awon Ijoba Alasepo - ki ise iyipada bi awon ti Tito ati Gomulka, lehin ase eyiti eto Ijoba ti ase kanna ti egbe awon alaigbagbo fi ntesiwaju - sugbon iyipada si isin Kristi ati ominira

Awon aye ti o han kedere wa nisisiyi fun eyi.

Awon ti ngbe Ijoba Alasepo, ti oje wipe nwon ma nse oloto ninu igbagbo won gegebi Onigbagbo wa ti ma nse oloto ninu igbagbo won, ngba inu isoro gidi koja.

Nwon ti gbagbo gan wipe eto Ijoba Alasepo yio mu idapo wa larin awon asaju won. Nisisiyi nwon ti ka ninu iwe-irohin ti won wipe apaniyan yio mu idapo wa larin awon asaju won. Sugbon nisiyi won ti ri wipe awon ilu ti oni eto Ijoba alasepo ma nni ikunsinu si ara won bi awon alailoye. Won ti gbagbo wipe Ijoba alasepo yi aye dabi Paradise, lodi si Paradise ti akori ti owa ni orun. Ati wipe ebi npa eniyan ti owa ni abe Ijoba Alasepo, won si nko ohun jije wo ilu won lati ilu awon Ijoba to fi aye gba ise adani. Nisisiyi nwon ti ka ninu iwe-irohin ti won wipe apaniyan gidi ni Stalin

ati pe asiwere ni Kruscheve. Bakanna ni pelu awon akoni orile-ede won bi Rakosi, Gero, Anna Panker, Rankovici ati bebe lo. Awon ti ngbe Ijoba Alasepo wonyi ko gbagbo mo wipe awon asaju won kole sise. Nwon dabi egbe Onigbagbo papo ti ko ni asaju.

Aye kan wa ninu okan awon ti ngbe Ijoba Alasepo. Kristi nikan lole kun aye yi. Okan omo eniyan gegebi eda nwa lati mo Olorun. Aye ti emi kan wa ti o sofo ninu, titi Kristi yio fi kun u. Eleyi je otito bakanna fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo. Ninu ihinrere agbara ife kan wa eyiti ole ni itumo gidi fun awon na. Mo ti ri i ti o sele. Mo mo wipe o le sese.

Awon Onigbagbo - ti awon ti ngbe Ijoba Alasepo ngan ti nwon si ndaloro - ti gbagbe, nwon si ti se idariji fun awon ohun ti a tise si awon fun ara won ati si ebi won. Nwon nsa ipa won de bi ti nwon le sa de lati ran awon ti ngbe Ijoba Alasepo lowo lati gba arin awon isoro na koja ki nwon si ri ona lo si odo Kristi. Fun ise yi nwon nfe iranlowo wa.

Ki si ise fun eleyi nikan. Ife Onigbagbo ma nko gbogbo eniyan mora. Pelu awon Onigbagbo iwa isojusaju ko si.

Jesu so wipe o orun Olorun ntan si ori eni rere ati eni ibi. Eyi kanna je otito nipa ife Onigbagbo.

Awon asaju Onigbagbo wonni ni Iwo Orun ti nwon wa ni irepo pelu awon ti ngbe Ijoba Alasepo, da ise yi lare nipa eko Jesu wipe a ni lati fe awon ota wa papa. Sugbon Jesu ko fi

igbakan ko wa wipe a ni lati feran awon ota wa nikan, ki asi ma gbagbe awon ara wa.

Nwon fi ife won han nipa gbigba awon ti owo won kun fun eje awon Onigbagbo towotese, ki se nipa fifun won ni ihinrere ti Kristi. Sugbon nwon gbagbe awon ti a npon loju lati owo awon ti nwon ngbe Ijoba Alasepo. Nwon ko ni ife won.

Awon Ijo Ajihinrere ati ti Katoliki ti iha Iwo Orun Germani, larin odun meje ti o koja ti fi egberun marun ole igba ole adota Onigbago Amerika fun won ni eyiti oju eleyi.

Opolopo eniyan lo wa ti ebi npa, sugbon nko le woye wipe eniti ebi npa to awon ajeriku Onigbagbo tabi ti o ni eto ju fun iranlowo lati owo awon Onigabgbo ti nwon wa ni ominira. Ti awon Ijo Germani ati awon Oyinbo ati awon eniyan Amerika ati ti Skandinavia ba da owo to po lekan fun iranlowo, o ye ki o to fun gbogbo eniyan ti o ba se alaini, sugbon saju fun awon ajeriku Onigbagbo ati awon ebi won.

Nje o nsele be loni?

Awon egbe Onigbagbo ni nwon san owo idasile mi, eyiti o se eri wipe a le da awon Onigbagbo sile. Ni aiko ibi ara si, temi nikan lose oran eni ti a da sile lati ilu wa nipa awon Onigbagbo. Beni otito idasile mi nilati ka ebi si awon egbe Onigbagbo ti iha Iwo Orun lorun nitoripe nwon se aibikita lati mu eto won se ninu awon oran to ku.

Awon Onigbagbo isaju bi ara won lere boya awon Ju nikan ni Ijo titun wa fun tabi fun awon Keferi pelu. Ibere na gba idahun ti

oto. Ni ona miran, oran yi ti tun jade wa. Isin Kristi ko wa fun iha Iwo Orun nikan. Kristi ko wa fun Amerika, ilu Oyinbo ati awon ilu mirar ti Ijoba ti wa ni owo awon eniyan nikan. Nigbati nwon kan mo agbelebu, okan ninu owo re wa si iha Iwo Orun, ekeji na si iha Ila orun. Ofe lati se Oba Ju, ati ti awon Kefer, Oba awon ti ngbe Ijoba Alasepo pelu, kii se ti apa Iwo Orun aiye nikan. Jesu so wipe: E lo sinu gbogbo aiye ki e si wasu ihinrere fun gbogbo eda."

O ta eje re sile fun gbogbo eniyan, beni gbogbo eniyan ni oye ki o gbo, ki o si gba ihinrere na gbo.

Ohun ti o nmu wa lokan le lati wasu ihinrere ni awon ilu awon ti ngbe Ijoba Alasepo lese ni wipe ni ibe, awon ti nwon di Onigbagbo kun fun ife ati itara. Emi kori omo Rusia kan ti oje kogbona-ko-tutu onigbagbo. Odo ti oje omo egbe Ijoba Alasepo (Communist) le di akikanju omo ehin Kristi, elese ti o si fe lati tu won sile ninu ese won. Awon asaju Ijo Iwo Orun miran fi nkan miran dipo iwa to to yi: itelorun pelu eto Ijoba Alasepo. Nwon ngbe ese na, nwon ran eto Ijoba Alasepo lowo lati bori ati nipa eyi nwon di igbala awon ti ngbe Ijoba Alasepo lowo, gegebi ti awon ti nwon ndaloro.

## OHUN TI MO RI NIGBATI A DA MI SILE

Nigbati mo tun wa pelu iyawo mi lekan si, lehin ti a da mi sile lati ewon, o bi mi lere ohun ti ero mi je fun ehin ola. Mo dahun wipe, "ohun ti o dara julo ti mo ni ni iwaju mi ni igbesiaiye ti emi ti o da wa." Iyawo mi dahun wipe ero kanna ni oun i.

Mo ti je akikanju ni igba ewe mi. Sugbon ewon, ati papa awon odun ti mo fi da nikan wa ni ihamo, ti yi mi pada si eni ti o nronu gan. Gbogbo iji okan mi ni oti dakeroro. Nko bikita nipa eko Ijoba Alasepo. Nko tile se akiyesi re. Nitori wipe oko iyawo ti orun gba mi mora nigbana. Mo gbadure fun awon ti nwon nda wa loro beni mo le ni ife won pelu gbogbo okan mi.

Ireti ti mo ti ni wipe nwon o da mi sile, sugbon nigbati o han si mi lati igba de igba lati ro ohun ti ngo se ti nwon ba ni lati da mi sile, mo ma ngbero pe ngo fara-sehin si ibi kan ki nsi ki nsi ma ba igbesiaiye idapo ti o dun lo ninu aginju pelu oko iyawo ti orun.

Olorun ni "otito na." Bibeli ni "Otito nipa otito na." Imo Olorun ni "otito nipa otito nipa otito na." Igbagbo ninu gbogbo Bibeli gegebi otito ni "otito ni" Otito nipa otito nipa otito nipa otito nipa otito na." Beni awon Onigbagbo ngbe ninu otito pupo yi nipa otito na, atipe nitori won, nwon ko ni

"otito na. Ninu ebi, nina ati riro ni ogun, ati gbogbo Imo Olorun ati Bibeli. Ati gbagbe "otito nipa otito na" nitorina igbesiaiye wa wa ninu "otito na." Ati ko wipe, "omo eniyan yio wa ni wakati ti enyin ko ro ati ni ojo ti enyin ko mo." A ko le ronu mo. Ni akoko idaloro wa ti o buru julo, Omo Eniyan wa si odo wa, o si nmu ki ogiri ile tubu wonyi dan bi okuta onyibiye julo, o si nmu imole kun inu tubu wonyi. Ni ibikan ti o jina, ni awon adaniloro wa wa ni isale wa ninu obirikiti ti ara. Sugbon emi nyo ninu Oluwa. Awa ko ba ti fi ayo yi sile fun ayo ti awon afin Oba.

Lati ko oju ija si enikan abi si nkankan? Ko si ohun ti o tun wa ni okan mi ju eleyi lo. Nko ni ife lati ja ogun kankan, ani awon ogun are. Ife mi ni lati ko awon ile isin elemi fun Kristi. Pelu ireti opolopo odun ti ironu idakeje niwaju ni mo kuro ni ewon.

Sugbon, lati ojo ti a da mi sile gan, opolopo iriri eto Ijoba Alasepo ni o ko mi ni irira gegebi gbogbo idaloro ti awon igba-ewon ko ti ri. Mo pade awon Oniwasu nla ati Alufa ti awon orisi Ijo ni okokan ati awon Olori Alufa papa, ti nwon kan jewo pelu ibanuje nla wipe olofofo ni awon je fun Olopa inu nipa awon agbo won. Mo bi won lere ti nwon ba setan lati jowo ofofo yi nisise, ti o ba tile je wipe nwon o so awon na si ewon nitori be. Gbogbo won dahun pe "rara", nwon si se alaye wipe ki se eru nitori ti ara won ni odi won lona. Nwon so fun mi nipa awon idagba titun ninu awon Ijo, awon ohun ti ko wa ki nwon to mu mi - wipe lati ko lati je Olofofo le je ki nwon ti

Ijo na.

Ni ilu kokan, asoju Ijoba ti o nse akoso awon "egbe isin" wa, okunrin Olopa inu ti Ijoba Alasepo. O ni ase lati pe Alufa ti o ba fe ni igba ti o ba wu u ki osi bi lere eniti o wa ni ile isin, eniti o ngba ounje ale Oluwa nigbakugba, tani eni ti o ni itara ninu isin, tani eniti o njere okan, awon eniyan won ni nwon njewo ese ati bebelo. Ti o ko ba dahun; nwon o le e lo nwon o si gba "Ojise Olorun" miran dipo re, ti yio so ohun pupo ju bi o ti nso lo. Nibiti asoju Ijoba yi koba tiri iru eniyan bayi (eyiti o sowon ), yio kan ti Ijo na.

Opolopo awon Ojise Olorun ni nwon nse ofofo fun awon Olopa inu, pelu iyato wipe awon miran nse be pelu ilora, nwon ngbiyanju lati fi awon nkan miran pamo, nigbati oje wipe awon miran ti so di iwa won beni eri okan won ti se. Sibesibe awon to ku ti jere iwa itara ti ofi je wipe nwon nso ju ibi ti abi won lo. Mo gbo awon ijewo lati enu awon omo ajeriku Onigbagbo ti nwon ti nilati se ofofo nipa awon ebi ti a ti gba won pelu inu-rere. Bi beko nwon a deruba wipe nwon ko ni ko eko won mo.

Mo lo si ipejopo awon Ijo Baptisi, ipejopo ti o wa ni abe eri Asia pupa, nibiyi, awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti pinnu awon ti yio se awon "Asaju ti a yan."

Mo mo wipe nisisiyi awon eniyan ti egbe Ijoba Alasepo yan ni o wa gegebi Olori awon Ijo ti o wa nipa ofin. Nigbanna ni mo mo wipe mo nri ohun irira ti isodahoro ni ibi mimo julo nipa eyiti Jesu nsoro.

Nigbagbogbo awon alufa ati Oniwasu dada ati buburu ni o ti ma nwa. Sugbon nisisiyi fun igba kini ni itan Ijo Egbe Apapo ti egbe awon ti o jewo pe Olorun ko si, ti o ti so ni gbangba ete nwon lati fa isin tu, ti pinnu eniti yio saju Ijo. Lati saju re fun ete wo? Dajudaju ati se iranlowo lati fa isin tu.

Lenin ko wipe: "gbogbo imo isin, gbogbo imo Olorun, papa fifi imo Olorun sire, je ohun ti o buru julo ti ko se wi jade, arun ti o nirira julo. Egberun aimoye ese, awon ise irira, awon ise ipa ati arun buburu ti ara ko buru to ogbon arekereke imo ati emi nipa Olorun kan."

Gbogbo awon egbe ti ngbe Ijoba Alasepo ti gbogbo agbegbe Soviet ni nwon ntele awon eko Lenin. Loju won, isin buru ju awon arun buburu ti o lepa eniyan lo. Beni awon na ni nwon pinnu awon ti yio se asaju isin. Beni awon asaju Ijo ti o wa nipa ofin yio sowopo pelu won, ti nwon si nfi ogbongbon jewo ninu igbagbo won.

Mo ti ri ibi ti nwon ti nsi awon omode ati odolona pelu eko aigba pe Olorun nbe, beni awon Ijo ti nwon wa nipa ofin ko gbodo tako ise yi. Kosi ile isin na ni Olu ile wa ti Bukarest tile ri awon odo pe nwon pade tabi ri ile eko ikorira ni ati nto awon omo awon Onigbagbo.

Nigbana - nibi mose ri gbogbo iwonyi - mo korira eto Ijoba Alasepo bi nko tise korira re labe idaloro won.

Mo korira re ki ise nitori ohun ti oti se simi, sugbon nitori ipalara ti o nse si ogo Olorun, si oruko Kristi ati si emi egberun lona merin

eniyan ti nwon wa ni abe ase re.

Awon agbe kekeke lati gbogbo ibi kakiri ilu ni nwon wa ri mi ti nwon si nso fun mi bi Ijoba tise gba gbogbo oko won lowo won ti osi di ti Ijoba. Nisisiyi nwon ti wa di eru ti ebi npa ni ori oko ati ogba ajara ti won teleri. Nwon ko ni ounje. Awon omo won oni wara, kosi eso - bẹni eyi nsẹle ni ilu ti oni opo ohun adanida ti ose gege pelu ti kanaani aiye atijo.

Awon ara jewo fun mi pe Ijoba Alasepo ti so gbogbo won di ole ati opuro. Ninu ebi nwon nilati ji nkan ninu oko ti oti se ti won ri, sugbon ti oti wa di ti gbogbo eniyan pupọ bayi. Nigbana nwon nilati puro lati fi bo ole won.

Awon Osise so fun mi nipa ijiya ni ibi ise won ati nipa ohun iyanu nla ti agbara - ise bi iru eyiti awọn ilu to lowo ko lala re. Awon koni ase lati kọ sile.

Gbogbo igbesiaiye ati ero idameta aiye ni ati parun tabi ti ati so di eke.

Awon odomobinrin wa lati dahun wipe ati pe nwon wa si Egbe Odo Ijoba Alasepo ati pe nwon ba won wi, nwon si deruba won nitoripe won fi enu ko enu pelu okunrin ti oje Onigbagbo, ati wipe nwon a fun won ni oruko eniti awon ma fi ẹnu ko ni ẹnu!

Gbogbo nkan ni odi iro ti osi burewa.

Nigbana nimo lọ ba awon ajija Ijo Abele - awọn elegbe ti igba pipe - lara won ti ako ti mu ati awon to ku ti nwon ti tun pada si enu ija na, lehin igba ti a da won sile lati ewon. Nwon pe mi lati tun pada si enu ija na, pelu won. Mo nlo si ipade ikoko won nibiti nwon ti nkorin lati

inu awon orin ti afi owo ko.

Mo ranti Anthony mimo ti o lokiki. Oti wa ni aginju fun ogbon odun. O ti fi aiye sile patapata, o ngbe igbesiaiye re gbogbo ninu awe ati adura. Sugbon nigbati o gbo wipe ija larin Athomasins mimo ati Arins nipa pe Kristi ni Olorun, ofi igbaseiaiye ironu sile osi wa si odo Alexandria lati ran otito lowo lati bori.

Mo pinnu lati se ohun ti gbogbo Onigbagbo nilati se: lati tele apere Kristi, Aposteli Paulu ati awon eni mimo nla, lati pa ero fifasehin ti ati lati tun pada si enu ija na.

Iru ija wo ni o ma je?

Awon Onigbagbo ni ewon ti ma ngbadura fun awon ota won beni won ti jeri daradara fun won. Ife okan wa ni wipe ki nwon di eni igbala, beni ama nyo nigbakugba ti oba ti ri be.

Sugbon mo korira iwa ibi ti ilana Ijoba Alasepo mo si ni ife lati fun Ijo Abele lagbara. agbara kansoso ti ole bi iwa ipa buburu yi subu nipa agbara ihinrere.

Nko ronu nipa Rumania nikan, sugbon nipa gbogbo awon ilu Ijoba Alasepo.

Sugbon moti ba opolopo iwa aibikita ni Iwo Orun pade. Awon ti nwon nko iwe kakiri agbaiye se ikilo nigbati awon elegbe won meji ti nwon ngbe Ijoba Alasepo - Siniavski ati Dainieli gba idajo ewon. Sugbon awon Ijo papa ko le taku nigbati a ba ju awon Onigbagbo elegbe won si ewon nitori igbagbo won.

Ta lo se ajo arakunrin Kuzyeh, ti aju si ewon nitori wipe o ru ofin nipa pipin iwe awon

Onigbagbo ti "Oloro", bi awon iwe kekeke ti Torrey ati awon ese lati inu Bibeli? Ta lo mo nipa arakunrin Prokofiev, ti a da lejo nitoripe o npin iwasu ti a ko si iwe? Ta lo mo nipa Onigbagbo Hebreru, Grunvald, ti a da lejo nitori awon ese iru kanna ni Russia ati lati owo eniti awon ti ngbe Ijoba Alasepo, ti gbe omo re kekere titi aiye?

Mo mo bi o tiri ni ara mi ni igbati nwon mu mi kuro ni odo Mihai mi. Mo si jiya pelu arakunrin Grunvald, Ivanenka, Granny Chevchak, Taisya Tkachenko, Ekaterima Vekazin, toko-taya Pilat ni Lativa ati bebe lo - oruko awon eni mimo ati akoni ti igbagbo ni igba yi! Mo teriba lati fi enu ko ewon won, gegebi awon Onigbagbo isaju. ti fi enu ko ewon awon Onigbagbo elegbe won nigbati aba nmu won lo lati loju won si awon eranko nla.

Awon asaju Ijo iha Iwo Orun ko bikita nipa won. Oruko awon ajeriku wonyi kosi ninu awon ti nwon ngbadura fun. Nigbati a nda-won-loro ti a si nda-won-lejo, awon asaju Ijo Baptisi ti Russia ati awon asaju ti oye li o ko ti Ijoba, ti nwon tise won, ti nwon siti fi won han, ni nwon gba pelu ola nla ni ilu "New Delhi", Geneva ati ni awon ipade miran gbogbo. Ni ibe, nwon fiye gbogbo eniyan wipe ominira isin ni kikun ni owa ni Russia.

Asaju'kan ninu ajo igbimo ti gbogbo Ijo ni agbaiye fi enu ko enu pelu Olori awon Bisobu ti Bolshevik, Nikodim, nigbati o so oro idaniloju yi. Nigbana ni nwon wa jo ni ase nla ni oruko ajo igbimo ti gbogbo Ijo ti agbaiye, nigbati awon eni mimo ti o wa ni ewon nje efo Oyinbo pelu ifun ti a ko fo, gegebi eni na tije

ni orukọ Jesu Kristi.

Nkan ko le wa bayi. Awon Ijọ Abẹle pinnu wipe ki nkuro ni ilu ti aye na ba si ṣilẹ, ki nsi sọ fun enyin Onigbagbọ nipa ohun ti o nṣelẹ.

Mo ti pinnu lati kọ "eto Ijoba Alasepo," bi o tile je wipe mo feran "awọn ti ngbe Ijọba yi." Nko ro wipe oto lati wasu ihinrere ni aiko eto Ijoba Alasepọ.

Awon miran nso fun mi wipe "Wasu ihinrere ti oda saka" Eyi ran mi leti wipe awọn Ọlọpa inu Ijoba Alasepo na so fun mi wipe wasu Kristi, sugbon ki nmase fi ẹnu kan eto Ijoba Alasepo. Be ni oha ri bi, wipe emi kanni ni o nmi si awọn ti owa fun ohun ti a npe ni "ihinrere ti oda saka" ati awon ti Ọlọpa inu ti Ijọba Alasepo.

Nko mọ ohun ti a npe ni ihinrere ti oda saka yi je. Iwasu Johannu Baptisti ha da saka bi? Ko so wipe "Ronupiwada nitori Ijoba Ọlọrun ku si dede" nikan. O tun so wipe "Iwo Herodu o da". A be ni ori nitoripe ko jeki iwasu re duro ninu oro nikan, o toka si aida. Jesu ko se wasu "ti oda saka" ti ori oke nikan, sugbon oso ohun ti awon asaju Ijọ miran yio pe ni iwasu odi. "Egbe ni fun nyin enyin Akowe ati Farisi, ẹnyin Alagabagebe... iran oloro!" Fun awon iwasu "aimo" bayi ni nwon se kan mo agbelebu. Awon Farisi kiba ti ko ibi ara si iwasu ori oke.

A nilati pe ese ni oruko re. Eto Ijoba Alasepo ni ese ti o buru julo ni agbaiye ni oni. Gbogbo ihinrere ti koba ko o ki ise ihinrere ti o mọ. Ijo Abele ko o, nwọn si nfi ominira ati emi won wu ewu. Ko siyẹ ki awa na ni Iwo Orun dakẹ lori re.

Mo ti pinnu lati ko eto Ijoba Alasepo ki ise bi awon ti a npe ni "asodi si Ijoba Alasepo" ti nse. Asodi si Ijoba Alasepo ni Hitla ise beni bi o ti le ribe ika eniyan ni. Awa korira ese na - a si feran elese na.

## IDI RE TI MO SE NJIYA NI IWO ORUN

Mo njiya ni Iwo Orun ju bi mo tise jiya lo ni awon ile Ijoba Alasepo. Lona kini, mo njiya nitoripe mo nlepa awon ewa Ijo Abele ti ko se fenu so, Ijo ti o nmu oro ede Romu se ti o wipe Nudis Audun Christi Sequi (eyin ti e wa ni ihoho, e tele Kristi ti o wa ni ihoho).

Ni ago awon Ijoba Alasepo, Omo Eniyan ati awon ti nwon je tire ko ni ibikankan ti nwon le gbe ori won le. Awon Onigbagbo ni ibe nwon ko ki i ko ile fun ara won. Fun anfani wo? Ijoba yio gba nigbati aba koko mu won, wipe ani ile titun leje ohun ti oma mu ki nwon fi e si ewon, nitori wipe Ijoba Alasepo fe igba ile na. Ni ibi o ko ni sin baba re, be o ko ni so wipe o dabo si awon ebi re ki o to tele Kristi. Tani iya re, arakunrin re ati arabinrin re? Ni ona yi, o dabi Jesu. Iya ati arakunrin re ni awon ti oba se ife Olorun. Nipa ti okun ti oso ebi po, nwon ha le ja mo nkankan mo nigbati oje ohun ti o nsele nigbakugba wipe ki iyawo ti a sese fe gbe ko oko iyawo, awon omo a ko obi won, awon iyawo ako oko won? Ipapo ti emi nikan ni o ma nku nigbakugba.

Ijo Abele talaka beni o si njiya, sugbon koni awon Omo egbe ti o lowowo.

Ipade isin ninu Ijo Ahele dabi okan ni edegba odun sehin ni awon Ijo isaju. Oniwasu ko mo eko nipa Olorun pupo. Ko mo nipa iwasu pupo, gegebi Peteru ko ti mo O. Awon Ojogbon ninu imo Olorun kankan ni iba ti fun Peteru ni ofo fun iwasu re ni ojo Pentikosti. A ko mo awon ese Bibeli dada ni awon ilu Ijoba Alasepo, nitoripe awon Bibeli se owon. Ati yato si eyi, Oniwasu le ti wa ni ewon fun opolopo odun, laisi Bibeli.

Nigbati nwon ba so igbagbo won ninu Baba kan, eyi ni itumo pupo nitori ise ti oda saka wa lehin itenumo yi. Ninu ewon ojojumo ni nwon ti mbere ounje ojo lowo Baba ti o lagbara julo, sugbon dipo eyi efo Oyinbo pelu irira ti ko se fi enu so ni nwon ri gba. Bi o tile ri be nwon gbagbo pe Baba ti oni ife ni Olorun. Nwon dabi Jobu ti oso wipe Oun yio gbagbo ninu Olorun ti oba tile je wipe yio pa oun. Nwon dabi Jesu ti ope Olorun ni "Baba", bi oba tile je 'pe a ko o ni ori igi agbelebu."

Enikeni ti oba ti ni ewa Ijo Abele ko le ni itelorun mo pelu iwa ofo ti awon Ijo Iwo Orun miran.

Mo jiya ni Iwo Orun ju bimo ti jiya ni ewon Ijoba Alasepo, nitoripe nisisiyi mo wa ri pelu oju temi wipe ilaju Iwo Orun nku lo.

Oswald Spengler ko ni inu iwe rẹ idinku ti Iwo Orun: 'E nkụ lo. Ninu nyin mo ri gbogbo awọn alebu Oba. Mo le fihan wipe oro yin nla ati osi nla, awon eto nipa eyiti efi nri owo pupọ ati Ijọba nyin ti o ndari gbogbo ohun ti o nmo 'wo wa, awọn ogun nyin ati awọn isọte nyin, aigbagbọ pe Ọlorun wa nyin ati iwa airo nkakan ni dada ati iwa ikanra nyin, iwa

idibajẹ nyin, igbeyawo nyin ti o tuka, iwa ifeto-siọmọbibi, ti o nṣe ẹjẹ lati idi nyin, ti osi npa nyin ni oke ni opọlo nyin - le fihan nyin wipe awọn wonyi ni iṣe ami ti awọn odun ti awon ilu atijo fi nku lọ - Alexamdra ti Greece ati Romu."

Ni odun 1926 ni ako eleyi. Lati igba yen, Ijọba ti agbara wa lowo awọn ẹniyan ati ilaju ti ku na ni idaji ilu awon Oyinbo ạtipapa titi de Cuba. Eyi toku Iwo Orun nsun.

Sugbon agbara kan wa ti ki sun eyi ni ti awọn Ijoba Alaṣepo. Niwọn ti oti jẹ 'pe ni Ila Orun awon ti ngbe Ijọba Alasepọ ti ni inuofo bẹru nwon ti padanu awon iruju won, ni Iwo Orun Ijoba Alasepo si wa pelu irunu gbigbona. Awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti nwon wa ni Iwo Orun ko kan gba awon irohin buburu nipa iwa ika ati osi ati inunibini ti owa ni awọn ilu Ijoba Alasepo gbo. Nwon ntan igbagbo nwon ka pelu itara aisare ni-ibi gbogbo ni irogboku awon eniyan jankan-jankan, ni egbe awon Ọjọgbon, ni awọn ile isin. Awa Onigbagbọ ki fi gbogbo ọkan gba gbogbo otito. Awon kẹ fi gbogbo ọkan si inu iro wọn.

Awọn Ojọgbọn ninu imo Ọlorun ni Iwo Orun si nfi ọro we ọrọ lori awọn ohun ti ko nilari na. Eyi ran mi leti pe, nigbati awọn ogun Mahomet II yi ilu Constantinople ka ni odun 1493 ti nwọn si nilati pinnu fun opọ-lọpọ ọdun ti oba ṣe awọn Onigbagbo tabi awon musulumi ni yio se Olori awọn eniyan Balkan, ajọ igbimọ ti Ijọ agbegbe kan ni ilu ti a yi ka yi ro awọn ọrọ wọnyi larin ara won: kini awọ ti oju wundia mimọ ni? Okunrin tabi obinrin ni awọn Angeli? Kini ohun ti yio sele ti

ti nwọn nfi wa bu. Bakanna, Dokita W.R. Mathews, eniti o fẹhinti lenu iṣẹ gẹgẹbi alakoso ile ẹkọ Paulu Mimọ ni ilu Oba (London) pari ọrọ rẹ nipa sisọ wipe iwa Jesu yi ko ba ọrọ rẹ mu, owa sọ wipe idi ti eleyi firi bẹ ni wipe Jesu ko mọ iwe!

Ero Montefiore nipa Jesu ko bọsi. Jesu fẹran awọn Farisi , bi o tilẹ jẹpe o tako won ni gbangba. Bakanna mo fẹran awọn ti ngbe Ijọba Alaṣepọ ati irin iṣẹ wọn ninu Ijọ, bi otilẹ jẹpe mo tako wọn.

Lati igba de igba nwọn nsọ fun mi pe: "Gbagbe awọn ti ngbe Ijoba Alasepo! Ṣiṣẹ ninu awọn nkan ti ose ti emi nikan.'

Mo pade Onigbagbọ kan ti awọn Nazi ti fi iya jẹ, o sọ fun mi wipe pẹlu gbogbo ara ni oun fi wa ni apa ọdọ mi ti mo ba le ma jẹri fun Kristi, ṣugbọn wipe ako gbọdọ sọ ọro kan ti o lodi si Ijọba Alaṣepọ. Mo bi lere bi awon Onigbagbo ti nwon doju ija ko Ijọba Hitla ni Jamani ba ṣe ohun ti ko tọ ati wipe nṣe ni nwọn ba ma sọro lati inu Bibeli nikan lailai sọ oro kan ti o lodi si eniti o nfi iya je wọn? Idahun ti o fun mi ni wipe, "Ṣebi Hitla pa ọgbọn okẹ awon Ju! Eniyan nilati sọrọ odi si." Mo dahun mo ni "Ijoba Alasepo tipa ọgọta ọkẹ awọn eniyan Russia ati ọkẹ aimoye awọn eniyan China ati awon miran. Bẹni nwọn tipa awọn Ju pelu. Se igbati nwọn ba pa awọn Ju nikan ni a nilati sọrọ ki a ma si sọrọ nigbati nwọn ba pa awọn eniyan Russia?" Idahun rẹ ni wipe "Ọrọ miran ni eleyi." Ko se alaye ọrọ rẹ yi fun

Ni osu kefa odun 1966 iwe irohin ti Soviet, Izvestia ati Derevenskais Jizn ba awọn Ijọ Baptisi ti Russia wi lori wipe nwọn nkọ awọn ara wọn lati pa awọn ọmodẹ fun iwẹnumọ ẹsẹ. Awọn ifi sin ti atijo ti ipaniyan nipa ilana isin eyiti nwọn ma nke si awọn Ju lọrun ni.

Şugbọn mo mọ itumọ eleyi. Mo wa ni ẹwọn Cluj ni Rumani ni ọdun 1959 pẹlu ẹlẹwọn ti orukọ rẹ njẹ Lazarovici, ẹniti a ka ẹsẹ wipe opa ọmọdebinrin kan si lọrun. Ọmọ ọgbọn ọdun pere ni okunrin yi, şugbọn irun ori re ti da funfun lenu ojo kan nitori idaloro o dabi arugbo. Ko ni ekanna. Nwon ti fa ekanna rẹ ya ki oba le jẹwọ ẹsẹ ti ko şẹ. Lẹhin odun kan ti idaloro ailẹsẹ rẹ wa han kedere, nwọn si wa da sile. Şugbọn ominira ko jamọ nkankan fun mo. O wa di eni alailera lai.

Awọn to ku ka awọn ti akọ si inu iwe irohin nwọn si le rẹrin wipe awọn ifisun ti o go ni ibiti nwọn ti tẹ iwe ilu Soviet nipa awọn Baptisti. Mo mọ ohun ti nwon nro nipa awọn ti a fi ẹsun kan.

Ohun ti o buru gba ni ojẹ lati wa ni Iwo Orun ati lati ma ri awọn nkan bawọnyi nigbagbogbo.

Nibo ni olori awon Bisobu Yermogen ti Kaluga (ni U.S.S.R.) ati awọn Bisobu meje toku wa, ti nwọn lodi si ifiowọsọpọ timọtimọ pelu Ijọba Soviet gegebi baba agbalagba Alexei ati olori awon Bisobu Nikodim ti nse, ti nwọn jẹ ohun elo ni ọwọ Ijoba Alaşepọ? Ti ko base wipe mo ri awọn Bisobu ti nwọn tako Ijoba Alasepo ni Rumania ti nwọn nku ni ẹgbẹ ọdọ mi ni ẹwọn ni, nko ba ti mọ lara pupọ

nipa awon Bisobu Oniwa bi Olorun wonyi. Baba agabalagba yi je awon Ojise Olorun. Nikolai Eshliman ati Gleb Yakumin ni iya nitoripe nwon bere fun ominira isin fun Ijo. Awon eniyan Iwo Orun mo gbogbo eleyi. Sugbon mo wa ni ewon pelu alufa agba lonan ti Vladimireshti, ni Rumania, eniti nkan kanna sele si. Ni Oju gbangba ni ona eto ni nwon fi nfi ofin Ijo ba awon alufa wi. Sugbon awon asaju Ijo tiowa nipa ofin Ijoba wa gegebi gbogbo awon asaju Ijo gbogbo ti owa nipa ofin gbogbo awon ilu Ijoba Alasepo, nsise ni ifowosowopo pelu Olopa inu. Awon ti nwon ba fi ofin Ijo bawi ni gbangba ni nwon tun nfi iya je "gidi" - nipa idaloro, ina, riro logun ninu ewon.

Mo wariri nitori awon iya awon ti nwon nse inunibini si ni ago awon Ijoba Alasepo. Mo wariri fun awon Onigbagbo Iwo Orun ti won ko ran awon ara won ti a nse inunibini si lowo.

Ni isale okan mi ngo fe lati toju ewa Ogba ajara temi ki nma si fa ara mi si inu ija nla bayi. Ngo fe ki nwa ni ibikan ni idakeje ati isimi. Sugbon ko sese. Eto Ijoba Alasepo ti bere. Nigbati awon ti ngbe Ijoba Alasepo do ti Tibe, nwon pa awon ti nwon ni ife si awon ohun ti emi. Ni ilu wa, nwon npa gbogbo awon ti nwon yo ara won kuro ninu ododo. Awon ile isin ati ibugbe awon ti nwon tije eje pelu Olorun ni nwon ka kuro ni ile, sugbon nwon fi awon die sile lati fi tan awon ti nwon ba wa lati ilu okere. Idakeje ati isimi timo nlepa yi yio je isalo kuro ninu ododo

bẹni yio sijẹ ewu fun ọkan mi pẹlu.

Mo ni lati saju ija yi bi otile jẹ wipe nkan ewu gidi ni fun ẹmi ara mi. Ti moba sa ẹjẹ koda nyin loju wipe awọn ti ngbe Ijọba Alaṣepọ ni nwọn jimi gbe. Nwon jimi gbe ni titi ni 1948, nwọn si fi mi si ẹwọn, nwọn wa yi orukọ mi pada. Anna Panker, Akowe Ijoba ilu wa ni igba yẹn, sọ fun aṣoju ilu Sweden ni ilu wa, Ọgbẹni Patrick Von Renterswaerde pe "Ah, Wurmbrand nrin bi o ti fẹ ni ori awọn titi Copenhagen." Asoju ilu Sweden yi ni iwe ti mo kọ si ti mo mu jade ni ẹwọn pẹlu iyege ni apo rẹ; o mo wipe irọ ni nwọn pa fun oun. Iru nkan bayi tun le sẹlẹ. Ti aba pa mi, yio jẹ wipe awọn ti ngbe Ijoba Alasepo ni nwọn yan eniti opa mi. Ko si ẹlọmiran ti oni ero lati pa mi. Timoba gbọ awọn ihin nipa biba mi ni orukọ jẹ, wipe mo ṣe ole, tabi 'pe mo ba okunrin ẹlẹgbẹ mi lo tabi pe moṣe pansaga tabi 'pe Ijoba kole gbẹkẹlemi, irọ pipa tabi ohun miran ti kọja ki nwọn to kọ itan wọnyi ati wipe awọn aṣọtẹlẹ inu Bibeli ti ṣẹlẹ ki nwọn to kọ wọn, wipe itan lasan ni itan wundia ti o loyun lai mo okunrin, bakanna nwọn ni irọ ni ajinde Jesu: wipe awọn ẹgun rẹ ti wa ni ibikan ninu iboji , wipe ko si otitọ kan ninu awọn iwe inu Majemu titun, wipe iwe asiwere eniyan ni jwe Ifihan jẹ, ṣugbọn wipe ki a mu gbogbo iwọnyi kuro, wipe iwe Mimo ni Bibeli jẹ! (Eyi je Iwe Mimọ ninu eyiti irọ pọ ju ti inu iwe irohin Ijọba Alaṣepo!)

eṣinṣin ba bọ sinu omi ti a ya si mimo? A ha ya esinsin ni si mimọ tabi omi yi ni odi mimo? O kan le fẹ itan atọwọdọwọ ti awọn igbani. Ṣugbọn fi akiyesi ka awọn iwe igba de igba ti awọn Ijo oni, o si ri wipe awọn ibere gẹgẹbi iru wọnyi na ni nwọn jọ nro. Pẹlu agbara kaka ni nwọn fi nfi ẹnu ba iwa idamu eto Ijọba Alaṣepọ ati ijiya Ijọ Abele.

Awọn ọrọ ti nwọn nsọ lori awọn nkan nipa imọ Ọlọrun nipa ilana isin ati nipa awọn ohun tiko nilari ko lopin.

Ẹgbẹ kan wa ni irọgbọku. Ẹnikan bere: "Ti Oba wa ninu ọkọ oju omi ti ori, ti osi le yọ ninu rẹ si ori erekusu ti o da wa, ti aye si si silẹ fun ọ lati mu iwe kanṣoṣo dani lati inu yara ti nwọn kọ iwe jopo si ninu ọkọ yi, Iwe ni iwọ yio yan? Ẹnikan dahun o ni "Bibeli", ẹlẹomiran ni "Iwe dahun pe: "Ngo yan iwe ti yio ko mi bi ngo tise kan ọkọ miran ti ngo le wọ de ebute. Ni ibẹ aye yio si silẹ fun mi lati ka iwe ti mo ba fẹ."

Lati tọju ominira fun gbogbo Ijọ ati gbogbo imọ Ọlọrun ati lati kabamo rẹ nibiti oba ti sonu, nitori inunibini awọn Ijoba Alasepọ, se pataki lati ẹnumọ Imọ Ọlọrun kan lọ.

"Ọtitọ ma nsọ ni di ominira," ni Jesu Kristi wi. Ṣugbọn bakanna, "Ominira, ani Ominira nikan ni o le fun ni ni Otitọ." Bẹni, dipo ki a ma sọ nipa ohun tiko nilari, nṣe loyẹ ki a fọwọsọwọpọ ki a kọ oju ija si awọn iwa ipa ti eto Ijoba Alaṣepọ fun ominira.

Mo njiya bakanna, bi mo se ni ipin ninu iya Ijọ ti nwọn wa ni ẹwọn ti o npọ si wipe mo ti gba arin awọn iya wọnyi, mo lefi oju inu wo wọn.

ni ofi gba Bisobu ti oba ronu pa iwada. Mosi ko orin igbagbo kan fun bayi ni okunrin ronupiwada olori yio je imuse gbogbo awon ideruba Olopa inu pe: "Ao ba iwa re je."

Enikan ti mo le gba oro re gbo so fun mi wipe awon ti ngbe Ijoba Alasepo ni Rumania ti pinnu lati pa mi lehin ẹri ti moje niwaju igbimo kan ni U.S. (United States ni America) Nwon yio gbiyanju lati pami nipa ti ara tabi lati pa oruko rere mi. Nwon yio gbiyanju lati sọrọ mi ni buburu (tabi deruba awọn ore mi ni Rumania. Nwon ni agbara lati se be.

Sugbon nko le wa ni idakeje. Eto re si ni lati ye ohun ti mo wi wo jeje. Ti oba ti lero wipe mo ti la koja, mo njiya, inunibini ti o diju o nilati bi ara re ohun ti agbara Ijoba Alasepo ti o leru yi je, ti o nmu awon eniyan re lati je awon iya ti o diju bawonyi. Iru agbara wo ni ti o nmu ki awon okunrin lati iha ila Orun Germani gbe omode papa ninu awọn ọko nla ti a fi nko iyepe gbẹ arin awon okun irin ti oni iso lara nipa eyiti ofi je wipe emi awon ati ebi won wa ninu ewu yinyin ni ibon?

Iha Orun nsun, a si nilati ji. Awon okunrin ti nwon njiya nwa enikan ti nwon yio di gbogbo ebi le lori. Lati ri iru eniyan bayi mu ki eru wuwo yi fuye die. Nko le se. Nkọ le di ebi na le ninu awon asoju Ijo Iwo Orun ti nwon tị nfowoso-sopo pelu eto Ijoba Alasepo. Ati odo won ko ni ibi yi ti nwa. O dagba ju bayi lo. Awon asaju wonyi papa ti jiya ibiti oti tun peju igba yen lo. Awon ko

ni won da ibaje yi sile ni inu Ijo. Awon na ba ni.

Lati igba ti mo ti wa ni Iwo Orun mo ti be awon ile eko imo Olorun pupo wo. Mo gbo awon eko ti nwon nko won nipa itan awon ago ati itan awon orin nipa eto adura, nipa Ibaniwi ninu Ijo eyiti ko si mo. Mo tiri awon eko nipa Imo Olorun ti nwon nko eko wipe ninu Bibeli itan nipa bi Olorun se da aiye ki se otito, ati wipe awon ohun ti ako nipa Adamu, tabi ikun omi, tabi awon ise iyanu ti Mose ko se otito nitoripe awon nkan wonyi Alufa papa ti o ba ronupiwada." Mo ko awon orin Onigbagbo fun okunrin yi si ironupiwada.

Mo wa ni ewon pelu alufa kan, eniti o ko awon ori wipe Olorun ko si pelu ireti wipe nwon o da oun sile. Mo ba soro osi fa awon ohun ti oti ko wonyen ya perepere nipa eyiti o sese ki nwon ma da sile.

Mo le wa eniti a o di ebi le lori sugbon nipa eyi nko le din eru wuwo ti okan ku.

Mo ni edun miran. Awon ore ti o sunmo mi pupo papa ntumo ohun ti mo nse ni ona miran. Awon miran nfi esun kan ni wipe mo ni iwa ikoro ati ibinu si awon ti ngbe Ijoba Alasepo, beni nkomo eleyi si otito.

Eni ti o nko iwe nipa akoko Mose. Chande Montefiore. so wipe iwa Jesu si awon akowe ati Farisi papa bi oti se ntako won ni gbangba lodi sin ofin re wipe ki a feran awon ota wa ati pe ki a sure fun awon

eṣinṣin ba bọ sinu omi ti a ya si mimọ? A ha ya esinsin ni si ımimọ tabi omi yi ni odi mimọ? O kan le fẹ itan atọwọdọwọ ti awọn igbani. Ṣugbọn fi akiyesi ka awọn iwe igba de igba ti awọn Ijo oni, o si ri wipe awọn ibere gẹgẹbi iru wọnyi na ni nwọn jọ nro. Pẹlu agbara kaka ni nwọn fi nfi ẹnu ba iwa idamu eto Ijọba Alaṣepọ ati ijiya Ijọ Abele.

Awọn ọrọ ti nwọn nsọ lori awọn nkan nipa imọ Ọlọrun nipa ilana isin ati nipa awọn ohun tiko nilari ko lopin.

Ẹgbẹ kan wa ni irọgbọku. Ẹnikan bere: "Ti Oba wa ninu ọkọ oju omi ti ori, ti osi le yọ ninu rẹ si ori erekusu ti o da wa, ti aye si si silẹ fun ọ lati mu iwe kanṣoṣo dani lati inu yara ti nwọn kọ iwe jopo si ninu ọkọ yi, Iwe ni iwọ yio yan? Ẹnikan dahun o ni "Bibeli", ẹlẹomiran ni "Iwe dahun pe: "Ngo yan iwe ti yio ko mi bi ngo tise kan ọkọ miran ti ngo le wọ de ebute. Ni ibẹ aye yio si silẹ fun mi lati ka iwe ti mo ba fẹ."

Lati tọju ominira fun gbogbo Ijọ ati gbogbo imọ Ọlọrun ati lati kabamo rẹ nibiti oba ti sonu, nitori inunibini awọn Ijoba Alaṣepọ, se pataki lati ẹnumọ Imọ Ọlọrun kan lọ.

"Ọtitọ ma nsọ ni di ominira," ni Jesu Kristi wi. Ṣugbọn bakanna, "Ominira, ani Ominira nikan ni o le fun ni ni Otitọ." Bẹni, dipo ki a ma sọ nipa ohun tiko nilari, nṣe loyẹ ki a fọwọsọwọpọ ki a kọ oju ija si awọn iwa ipa ti eto Ijoba Alaṣepọ fun ominira.

Mo njiya bakanna, bi mo se ni ipin ninu iya Ijọ ti nwọn wa ni ẹwọn ti o npọ si wipe mo ti gba arin awọn iya wọnyi, mo lefi oju inu wo wọn.

mi.

Awon Ọlọpa ti lu mi ni akoko Hitla ati ni akokò Ijọba Alaṣepo bẹni nko ri iyato kankan. Mejeji ni o dun mi.

Isin awọn Onigbagbọ nilati doju ija kọ orisirisi awon ẹṣẹ, ki ise eto Ijọba Alaṣepọ nikan. Isoro kanṣoso yi kọ lo wa lona wa.

Sugbọn eto Ijoba Alaṣepọ ni ojẹ ọta isin Onigbagbo julọ bẹni oun lo ni ewu julọ. A nilati pawapo lati doju ija ko ọ.

Ẹjẹki ntun sọ lekan si! Ohun ti eda nlepa ni lati dabi Kristi. Ohun ti awon ti nwọn ngbe Ijoba Alaṣepọ nlepa ni lati mu ki eleyi ma sese. Ni ọna kini nwọn lodi si isin. Nwọn gbagbọ wipe lẹhin iku eniyan a di iyọ ati ohun alumọni ilẹ ati pe kosi nkankan ju eyi lọ. Nwọn nfẹ ki eniyan gbe gbogbo igbesiaiye re lori ohun ti a fi oju ri nikan.

Isin kẹhin ti a nse fun oku nikan ni nwọn mọ. Ọrọ nwọn ni ọro ti ẹmi eṣu kan ninu iwe Majemu Titun nigbati abi lere oruko re ti oni "A po." Nwọn ti fọ agbara lati jẹ ti ara wa - ẹhun ti o tobi julọ ti Ọlọrun fun eniyan niwon ti gba kuro pata. Nwon tifi okunrin kan si ewon nitoripe nwon rẹ iwe kanimo nipa ti ara ẹni - ti Alfred Adler ko ni owo re. Awọn oloye Olopa ikoko kigbe pe, "Ah ti ara eni - ti ara eni nigbagbogbo! kinide ti gbogbo eniyan kose papo?

Jesu fẹ ki a le ni ara wa. Nitorina ko ṣeṣe ki a fọwọ-so-wọpọ pẹlu eto Ijoba Alaṣepọ. Awọn ti nwọn npe ni "Nauka i Religia" (eyi ni ẹkọ ijinlẹ ati isin) ni a tiri ka wipe

"Isin ko se papo mo eto egbe Ijoba Alasepo. O korira rẹ... Awon ohun ti nwon ko si inu eto egbe Ijoba Alasepo ni lati pa isin run ... Eto lati fi da agbo awon ti ko gba Olorun gbo ni, ninu eyiti awon eniyan ko ni ni nkankan lati se pelu ide isin."

Nje IsinIgbagbo le wa po pelu eto Ijoba Alasepo?. Nibi ni awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti dahun ibere yi ... "Eto Ijoba Alasepo nilati pa Isin run."

## ORI KARUN

### IJO ABELE TI O FARASIN TI OSI NTAN KALE

Ngo wa tun soro nipa Ijo Abele.

Pelu inira gidi ni o fi nsise. Aigbagbo ninu Olorun ni isin gbogbo awon ilu Ijoba Alasepo. O ribi enipe nwon kofi be di awon agbalagba ti o gbagbo lowo, sugbon awon omode ati odo ko gbodo gbagbo. Gbogbo awon nkan ni awon ilu wonyi - bi ero gbohungbohun, ero gbohungbohun alaworan re aworan, ile iworan, ibiti a ti nte iwe, awon ile ti ati nte iwe jade - ni ero lati mu igbagbo ninu Olorun kuro.

Ijo ti Abele ko ni agbara pupo lati doju ija ko awon agbara nla ti gbogbo ilu yi. Awon Ojise Olorun ninu Ijo Abele ti Russia ko ko eko nipa Imo Olorun. Ari awon Alufa tiko tika gbogbo Bibeli ri.

Ngo so fun o oye awon ti a yan ni Alufa. A ba odo Russia kan pade ti o tije Ojise Olorun ni ikoko. Mo bi lere eniti o yan ni Alufa. O dahun o ni "Ako ni olori awon Alufa (Bisobu) 'gidi ti ole yan wa si ipo Alufa. Bisobu ti Ijoba gan kole yan

enikani si ipo Alufa ti ẹgbẹ Ijọba Alaṣepọ ko ba fi ọwọ si. Nitorina awọn ọdọ Onigbagbọ mẹwa lọ si iboji Bisobu kan ti o ku gẹgẹbi ajeriku. Awa meji gbe ọwọ le okuta ti nwọn mọ le iboje rẹ. Awọn to ku ṣọgba yi wa ka a si ni ki Ẹmi Mimọ yan wa. A ni idaniloju wipe a yan wa nipa ọwọ Jesu ti a da lu."

Loju temi, iyan si ipo Alufa ti awọn ọdọ wọnyi je itẹwọgba lọwọ Ọlọrun!

Awọn okunrin ti a yan ni ọna bayi tiko si ti lọ kọ ẹkọ nipa Imọ Ọlọrun, ti o sijẹ wipe nwọn ko mo ọrọ inu Bibeli pupọ, ni nwọn nba iṣe Kristi lọ.

Gẹgẹbi Ijọ aiye atijọ ni o se ri. Iru ẹkọ wo ni awọn ti nwon doju aiye ko isale ni? Gbogbo wọn ni o ha mo iwe ka bi? Nibo ni nwọn si ti ri Bibeli? Ọlọrun nsọrọ si nwọn.

Awa ti Ijọ Abẹle, ako ni ile isin ti o tobi ti osi ni Bisọbu. Ṣugbon a ha ri ile isin nla bawọnyi, ti o lẹwa ju oju Ọrun eyiti a nwo nigbati aba pejọ ni ikọkọ ni aginju bi? Igbe awọn eiye ni o dabi duru fun wa. Orun didun awọn ododo ni ojẹ turari wa. Bẹni ẹwu ti oti gbo ti ajẹriku ti a ṣẹṣẹ da silẹ ni ẹwọn ba wọ lewa lọrun ju ẹwu Alufa. Osupa ati awọn irawọ ni nwọn jẹ fitila wa. Awon Angeli ni nwọn ba wa tan wọn.

Nko le sọ bi ewa Ijọ yi tito!

Ni igba pupọ, lẹhin igba ti aba ṣe isin wa tan ni ikọkọ, ọwọ a ba awọn Onigbagbo nwọn a si ran wọn lọ si ẹwọn. Ni ibẹ, awọn

Onigbagbo wo ṣekeṣeke pẹlu ayọ eyiti iyawo titun fi nwọ Oruka Olowo iyebiyi ti oba gba lati ọwọ Olufẹ rẹ. Awọn omi ẹwọn wa ni idakẹrọro. Nigbati o ba fi ẹnu ko e ni enu ti osi wa ẹ mọ aiya, oko ni gba aiye fun awọn ọba. Mo ti ri awọn Onigbagbọ ti nwọn kun fun ayọ ninu Bibeli ni Ijọ Abẹlẹ ati ni ẹwọn.

Nwọn nfi iya jẹ Ijọ Abẹle, ṣugbọn bakanna oni awọn ọrẹ pupọ - papa ni arin awọn Olọpa ikọkọ, ati papa ni arin awon Oloye Ijoba. Ni igbamiran awọn Onigbagbo ikọkọ wọnyi ma ntọju Ijọ Abẹlẹ.

Ni aipẹ yi, iwe irohin Russia nwijọ nipa awon "alaigbagbọ oju" ti nwọn npọ si. Awọn wọnyi, gẹgẹbi ile itẹwe jade ti Russia ti wi, jẹ awọn okunrin ati obinrin tiko niye ti nwọn nṣiṣẹ ni arin agbara Ijọba Alaṣepọ ni awọn ibi iṣẹ Ijọba, ni awọn ibiti a ti ngbe irohin lọ fun awọn eniyan ati ni ibi gbogbo - ti ọjẹ wipe ni oju, nwon ngbe Ijoba Alaṣepọ ṣugbọn ni inu nwọn jẹ Onigbagbọ ikọkọ nwọn sijẹ ọmọ ẹgbẹ Ijọ Abẹlẹ.

Iwe irohin Ijoba Alasepo sọ itan ọdọmobinrin kan ti o nṣiṣẹ ni ile irohin. Lehin igba ti oba jade ni ibi iṣẹ wọn, nwọn sọ wipe yio lọ si ile rẹ nibiti yio ti pade ọkọ rẹ ti o nti ibi iṣẹ rẹ bọ. Lẹhin ounjẹ alẹ, oun ati ọkọ rẹ yio ko awọn ọdọ jọ lati awon ile sakani nwọn, nwọn yio si kọ ẹko ninu Bibeli nwọn o si ni adura ni ipejọpọ ni ikọko. Eyi nṣẹlẹ kakiri gbogbo awọn ilu Ijoba Alaṣepọ. Egberun aimoye ni awọn "alaigbagbọ oju"

ti owa ni gbogbo ile Ijoba Alasepo. Nwon ro gegebi ohun ti o sunwon ju lati ma lo si awon Ijo ti oju nibiti awon kan yio ma so won, ti nwon o si ma gba iwasu ti ko mu ohunkohun dani. Dipo be nwon wa ni ipo agbara ati eto eyiti nwon wa, beni lati ibe nwon njeri fun Kristi dada.

Ijo awon Oloto ti Abele ni egberun aimoye iru awon eniyan bawonyi ni awon iru ipo wonyi. Nwon ma nni ipade ni awon kolofin bi yara ti o wa ni abe ile tabi ni abe orule ati ni ile ara won.

Ni Russia, ko si eniti o tun ranti awon ijiyan fun tabi lodi si isami fun omode tabi agbalagba, ati fun tabi lodi si asise ti Ijoba Olori awon Alufa Romu. Nwon koni igbagbo ninu akoko ti o saju tabi ti o tele egberun odun Ijoba Kristi. Nwon kole tumo asotele beni nwon ko ni ija nipa won, sugbon o ma nya mi lenu nigba pupo bi nwon tile yege to lati fihan awon tiko gba Olorun gbo wipe Olorun wa.

Awon idahun won fun awon tiko gba Olorun gbo kole titi: "Ti a ba pe e wa si ibi ase kan pelu orisirisi eran daradara, nje o gbagbo wipe kosi enikankan ti ose? Sugbon ase nla ni eda ohun gbogbo ti a pese sile fun wa! Orisirisi eso ni owa bi "tomato" "peach", eso ti o dabi oro Oyinbo, wara ati oyin. Ta lo pese gbogbo nkan wonyi fun eda? Afoju ni ohun ti eda. Ti iwo o ba ni igbagbo ninu Olorun kankan, bawo ni o se le se alaye bi afoju ohun ti eda se yege lati pese

awọn ohun ti a nilo ni opọ ati ni orisirisi wọnyi?"

Nwọn le fihan wipe iye ainipẹkun wa. Mo ti gbọ ti okan ninu wọn nba ẹnikan ti ko gba Ọlọrun gbọ soro oni: "je ti oba sẹsẹ fun wa lati ba oyun inu soro ninu iya re, lehin eyi ti yio wa gbe igbe aiye gidi, igbe aiye ti o gun. Bawo ni oyun inu yi yio ti dahun? Idahun re yio dabi ohun ti enyin alaigbagbo ninu Olorun nso fun wa nigbati a ba soro fun yinnipa Paradise ati Orun apadi. Yio so wipe igbese aiye isin ni gbogbo ohun ti o ku. Sugbon ti oyun inu yen ba le ronu, yio so fun ara re 'pe . "Ni ibi, awon owo mi nyo, nko ni ilo wọn. Nko kan tie le mi won. Nitori idi wo ni nwon se nlu? Boya fun akoko miran ninu wiwa mi ninu eyiti ngo fi wọn sise. Awon ese nyo, sugbon mo nilati jeki nwon wa ni kikako bi nwon se wa. Nitori idi wo ni nwon se nlu? Boya igbesi aiye ni aiye ti o tobu ju eleyi ni yio tele wiwa mi ni ibi yi ni ibi ti mo ti ma rin. Awon oju nyo bi o tile je wipe okunkun ni oyi mi ka beni nko ni ilo won. Nitori idi wo ni mo se nnì oju? Boya aiye ti o ni imole ati orisirisi awo ni yio tele wiwa mi ni ibi." Nitorina, ti oyun inu ba le ronu jinle nipa ke re, yio mo nipa igbesi aiye ti yio tele ti inu iya re,, ni aiti ri i. Bakanna ni ori pelu wa. Nigbati a ba si wa ni odo, a ni agbara, sugbon a ko ni emi lati lo ni ona toto. Lehin odun pupo ti a ba ti dagba ninu ogbon ati oye, keke oku a ma duro de wa lati gbe wa lo si

iboji. Nitori idi wo ni o fise pataki wipe ki a dagba ni nu ọgbọn ati oye eyi ti a ko le lo mọ? Nitori idi wo ni awọn apa, esẹ ati oju fi nyọ lara oyun inu. Nitori ohun ti yio tele ni. Bẹna ni o ri pẹlu wa ni ibi yi. A ndagba ni ibi ninu iriri, imo ati oye nitori ohun ti yio tele. A nmura silẹ lati le gbe igbesi aiye ti o tun ga ju eleyi lọ eyiti o tẹle iku.

Ohun ti Ijoba Alaṣepọ nkọ awọn eniyan nipa Jesu ni wipe ko fi igba kan wa. Pẹlu irọrun ni awon osise Ijọ Abẹle fi ndahun eleyi. Nwon a wipe: "Iwe Irohin wo ni o wa ni apo re? Se ti oni abi ti ana? Jeki nyẹwo, Aha! Ojọ Kerinla osu kini ọdun 1964. Igbawo ni a ti bẹrẹ si ka 1964? Se lati igba ẹni ti ko wa ti ko si se ohunkohun ni? Ẹnyin sọ wipe Jesu ko fi igba kan wa, ṣugbon ẹ nka awọn ọdun lati igba ibi rẹ. Akọkọ wa, ki Jesu to wa. Ṣugbọn ni igba ti owa, ni oju eniyan o dabi ẹni wipe gbogbo ohun ti a ti ṣe ki o to wa jẹ ofo ati wipe gbogbo nkan ṣẹṣẹ bẹrẹ nisisiyi ni. Iwe Irohin Ijọba Alaṣepọ nyin gan fihan wipe irọ kọ ni ọrọ nipa Jesu.

Awọn Alufa ni Iwọ Orun ma nro wipe gbogbo awọn ọmọ Ijọ wọn ni nwọn gba gbogbo otitọ nipa Isin Kristi, nigbati ko ri bẹ. Pẹlu agbara kaka ni o file ri iwasu ti o nfi otitọ Igbagbọ nhan. Ṣugbọn ni ewọn, awọn tiko ti kọ bi a ti nse bayi ri, ma nfun awọn ti nwọn ba ronupiwada ni ipilẹ ti o nipọn.

A ko le tete ri ohun bi ala ti a le sọ wipe

oya Ijo Abele, nibi ti agbara ati ijinle isin Kristi wa, ati Ijo ti o wa nipa ofin. Nwon wo ara won. Opolopo awon Alufa ti awon Ijo oju ni nwon tun nse ise ihinrere ni ikoko ti o jinle ju ohun ti Ijoba Alasepo fe ki nwon se.

Ijo ti owa nipa ofin yi, eyiti ise Ijo awon ti nwon nba Ijoba Alasepo sowopo, ni itan ti o gun.

O bere lehin igba ti Ijoba Russia sote si "Ijo Olorun ti o gbona." Alufa ti a npe ni Sergins ni o saju ote yi.

"Ijo Olorun ti o gbona" yi nwasu ni Moscow ni igba yen ni gbangba wipe: "ohun ti a nlepa ki ise lati tun Ijo yi ko sugbon lati mu wa si opin, ki a sifi opin si gbogbo Isin." Ni oju ti won, eyi je eto ti o dara pupo fun Ijo!

Ni gbogbo ilu ni a ti ri awon eniyan bi Sergins yi.

Ni Hungary, larin awon Ijo Katoliki, Alagba Balogh ni o saju ote yi. Oun ati awon Ojise Olorun ni awon Ijo miran ran Ijoba Alasepo lowo lati gba agbara ni gbogbo ilu.

Ni Rumania, agbara bo si owo Ijoba Alasepo pelu iranlowo Alufa kan ti oruko re nje Bardncea, eniti o lodi si Ijoba Alasepo ri, eniti iwa re tun wa le ju ti awon oga re lo. Alufa yi duro ni egbe Vishinski, akowe gbogbo ilu Soviet, o si rin erin ifowo-sowopo nigbati akowe ilu nsoro nipa fifi Ijoba Alasepo si ipo agbara ti o si nso 'pe: "Ijoba Alasepo yio ko Paradise ti aiye o ko sini fe

ti Orun mo."

Nipa Olori awon Bisobu Nikodin ti Russia, o ti wa ninu iwe wipe yio ma se ofofo fun Ijoba. Ogagun Deriabin eni ti o sa kuro lehin Olopa ikoko ti Russia, jeri sii wipe asoju ni Nikodin je fun Olopa Ikoko.

Bayi ni gbogbo nkan se ri ni gbogbo Ijo. Pelu agbara ni nwon fi yan eni ti oje asaju Ijo Baptisti ti Rumania ni isin. O se awon Onigbagbo toto. Ni Russia, bakanna ni eniti o nsaju Ijo Batisti nse. Alakoso Ijo ti o gbagbo ninu pipadabo Kristi ti Russia, Techici fi enu ara re so fun mi wipe oun ti je Oluwi fun Olopa Inu ti Ijoba Alasepo lati ojo ti agbara tide owo won gan.

Dipo eyiti nwon o ba fi ti gbogbo Ijo - bi otile je 'pe nwon ti ti egberun aimoye - Ijoba Alasepo pinnu lati yonda die gegebi ferese nipa eyi ti nwon le ma so ati se akoso awon Ijo wonyi ati ni ikehin ki nwon le fi pa awon Onigbagbo ati Isin Kristi run. Nwon pinnu pe yio dara ti nwon ba je ki Ijo yi wa ki nwon si wa yipada si irin ise Ijoba Alasepo lati fise akoso awon Onigbagbo ati lati fi tan awon alejo ti o ba wa si ilu won je. Nwon fun emi na ni iru Ijo bayi ni ori adehun wipe emi, gegebi Alufa yio ma se ofofo awon omo-Ijo mi fun Olopa Inu. O dabi enipe awon eniyan Iwo Orun, nigbati gbogbo "dudu ati funfun" ti mo won lara - eyi ni wipe ti gbogbo won o ba te si ibi nwon ate si ohun - kole ni oye eleyi. Sugbon Ijo Abele ko nije gba iru awon Ijo bayi, awon Ijo ti

Ijoba Alasepo nse akoso re dipo ihinrere ti o mu ogbon dani, ti o si muna "si gbogbo eda - ati odo pelu.

Sugbon ni awon Ijo ti Ijoba wonyi isin ti emi gidi wa leri gbogbo ideruba awon asaju pupo. (mo ni imo wipe ni opolopo Ijo ti Iwo Orun bakanna ni o ri pelu ti Ijoba Alasepo yi. Awon omo Ijo nse oloto nigbamiran ki ise nitori, sugbon leri iru eniyan ti awon Asaju nwon je).

Iwe ilana isin ti atijo ko yipada, beni o nbo okan awon omo egbe Ijo yi, bi otile je 'pe awon iwasu npon awon ti ngbe Ijoba Alasepo. Awon elesin Luther, Presbyter ati awon Ijo miran ma nko awon orin atijo kanna. Be si ni iwasu awon Olufisun wonyi papa nilati ni oro Olorun die ninu re. Awon eniyan nronupiwada nipa agbara awon eniyan ti nwon ti mo tele ni olofofo, nipa eyi ti nwon si mo wipe nwon yio se ofofo ironupiwada won fun Olopa Inu. Awon wonyi nilati fi igbagbo won pamo fun eniti o fun won ni igbagbo yi nipa iwasu re ti o ku-fun iyin fun Ijoba-Alasepo. Eyi ni ise iyanu nla Olorun nipa eyiti Lefitiku Keji ko ninu oro re 'pe: "Ti apa kan eran (eyiti o ti di aimo gegebi ofin Mose) ba bo si ori eso ti a fe gbin, yio di mimo."

Isoto na pelu mu wa lati so wipe ko ki se gbogbo awon asaju Ijo ti o wa nipa ofin ati pe ki ise gbogbo awon ti o wa ni ipo asaju ninu Ijoba ni nwon ngbe Ijoba Alasepo.

Awon omo egbe Ijo Abele na lokiki

ninu Ijo ti Ijoba da sile, afi awon die ti nwon nilati fi ara won pamo. Nwon si nri si i wipe Isin Kristi kodi yeye, sugbon ki oje igbagbo ti a nduro ti lehin. Nigbati Olopa inu wa lati wa ti ibugbe awon Ojise Olorun ti Vladimireshti ni Rumanis ati pupo ninu awon ti o wa ni Russia ko rorun fun won. Awon ti ngbe Ijoba Alasepo miran ti fi emi won di i nitori ipa ti nwon nsa lati di isin lowo.

Sugbon awon Ijo ti o wa nipa ofin Ijoba ndinku si i. Boya ni a leri egberun marun tabi mefa Ijo ti o si wa ni gbogbo agbegbe Soviet. (Ilu Amerika ti iye awon eniyan ti owa ninu re je okanna pelu ti agbegbe Soviet yi ni oke medogun Ijo). Beni awon "ile Isin" wonyi koju yara kekere kan lo -, ki ise ile isin gegebi ati le ro si ni okan wa. Awon alejo lati ilu okere nri ile isin ti o kun gidi ni Moscow - eyiti oje Ijo kansoso ti o wa ni gbogbo ilu Moscow - eyiti oje Ijo Moscow - nwon a si so wipe ominira isin wa ni ibe. "Nse ni awon ile isin won papa kun de enu!" - Bayi ni nwon se nrohin nigbati nwon ba pada si ilu won. Nwon ko ri oro ibinuje ti o wa ninu Ijo kansoso fun adota leni odunrun oke okan! Be si ni awon ile isin ti oje yara kekere kan wonyi papa jina gan si ile opolop awon eniyan Soviet. Yala ki a gbagbe awon ogunlogo eniyan wonyi ni - tabi ki a fi ona ihinrere abele mu oro Olorun wa fun won. Ko si ona miran mo.

Bi Ijo Alasepo ti ntesiwaju sii ni ilu kan, beni gbogbo ise Ijo nilati malo ni abele sii.

Awon ipade awon egbe ti o lodi si sin ni nwon wa dipo awon Ijo ti nwon ti.

## BI IJO ABELE TISE "MU ANFANI JADE" LATI INU IWE TI O KUN FUN A AINIGBAGBO NINU OLORUN

Sugbon Ijo Abele mo bi o se le lo awon wonyi pelu. Saju, o nmu anfani jade lati inu iwe ti o kun fun oro ti o lodi si Olorun, gegebi awon eiye tise wa ngbe ounje fun Elijah. Awon tiko gba Olorun gbo wonyi fi gbogbo ipa won sinu fifi oro inu Bibeli se yeye ati ti tako.

Nwon te awon iwe jade ti nwon pe ni Bibeli ti o panilerin ati Bibeli fun awon Onigbagbo ati alaigbagbo. Nwon gbiyanju lati fihan wipe awon ese Bibeli ko mu ogbon dani ati lati lese bawonyi nwon ko awon ese Bibeli pupo! Awon itako wonyi po to be ge tiko si eniti o kan kun ohunkohun. Sugbon oke aimoye iwe wonyi ni nwon nte jade beni o si kun fun awon ese Bibeli eyiti ewa re ko se fi enu so, papa nigbati awon ti ngbe Ijoba Alasepo ba nfi se yeye. Ni atijo iya ti nwon fi nje awon ti igbagbo won yato si ti Ijo ni 'pe nigbati nwon ba nmu won lo si ibi ti nwon ti ma sun won ni ina gegebi ilana ofin, nwon a wo aso egan si nwon lara pelu aworan ina orun .apadi ati awon aworan esu lara re,

nwon a wa to le won lehin bi won ti nrin lo si ibiti nwon ti ma sun won ni ina. Awon eni mimo wo wa ni awon ti a ka kun eniti o lodi si igbagbo Ijo! Beni awon ese Bibeli duro ninu otito, ti o ba tile je wipe esu ni o nso o.

Inu awon ti nwon nte iwe wonyi jade dun nigbati nwon nri egberun aimoye iwe gba wipe ki nwon tun te awon iwe won jade, ninu eyiti nwon te awon ese Bibeli si lati fi won se eleya. Nwon ko mo wipe odo awon Ijo Abele ni awon iwe wonyi ti wa, awon ti nwon ko tun ni anfani miran lati fi ri awon oro Olorun gba.

Bakanna, a mo bi a se le lo awon ipade awon ti ko gba Olorun gbo dada.

Ojogbon Ijoba Alasepo kan fihan ni ibi ipade kan wipe apidan lasan ni Jesu ise. Ojogbon yi gbe ikoko iponmi kan si iwaju re. O da etu si inu re, omi na si di pupa. O wa dahun wipe "Gbogbo ise iyanu na niyi. Jesu ti fi iru etu bayi pamo si abe apa aso re, O si wa ndibon wipe oun ti yi omi pada si oti waini ni ona iyanu. Sugbon emi fun ara mi le se ju bi Jesu ti se; mo le tun yi oti waini yi pada si omi." O si tun da etu miran si inu ikoko yi, "oti waini" yi si tun dabi omi pada. Lehin na o tun da etu miran si, o si tun yipada si pupa.

Onigbagbo kan wa dide o ni, "O ti se ohun ti o ya wa lenu, ojogbon elegbe wa, nipa ohun ti o le se yi. A o bere nkankan si ni owo re: mu die ninu oti waini re!" Ojogbon na dahun wipe "Eyi ni nko le se.

Majele ni etu yi." Onigbagbo yi ba tun dahun o ni "Eyi ni iyato larin iwo ati Jesu. Jesu, pelu oti wiani re, ti fun wa ni ayo fun egberun meji odun, sugbon nse ni iwo fun wa ni majele pelu oti waini tire." Onigbagbo yi lo si ewon. Sugbon irohin nipa isele yi tan ka o si mu igbagbo awon eniyan le.

Awon Dafidi kekeke ti ko lokun ni wa. Sugbon a lagbara ju Goliat ti aigbagbo ninu Olorun, nitoripe Olorun wa ni apa odo wa. Awa ni a ni otito.

Ni igbakan ri, Oluko Ijoba Alasepo kan nko eko lori aigba Olorun gbo. Gbogbo awon osise ibi ile yi ni nwon nilati lo gbo oro yi beni ninu awon osise wonyi Onigbagbo pupo wa nibe. Gbogbo won joko jeje nwon ngbo awon ijiyan okunrin yi ti o lodi si Olorun ati iwa omugo ti o wa ninu gbigba Kristi gbo. Oluko yi nsoro re lo nipa fifi han wipe ko si ohun ti yio tele wiwa wa ni aiye yi. Ohun ti a ri lasan ni omo eniyan je, ko si emi. Bi o ti nso be ni o ntunso wipe ohun ti a ri nikan ni owa.

Onigbagbo kan duro o si toro gafara lati soro. Nwonyonda re. Onigbagbo yi gbe ijoko re ti o se ka, o si so o mo ile. O duro die, o nwo ijoko yi. O si rin jade, o gba oluko Ijoba Alasepo yi ni eti. Inu bi Oluko yi gidi. Oju re si di pupa. Pelu ibinu, o kigbe pelu ami itiju o si ni ki awon elegbe re mu Onigbagbo yi. O wa bi lere o ni, "Bawo ni o se laiya lati wa gba mi leti? Kini idi re?

Onigbagbo yi dahun o ni "o ti fi ara re

han gegebi opuro. O so wipe kosi ohun ti tun ju eyiti a fi oju ri. Kose nkan miran. Mo gbe aga mi mo ju lu 'le. Loto ohun ti a fi oju ri nikan ni. Nigbati mo gba e ni eti, o ko se bi aga yi ti se. Ohun ti o se yato. Ohun ti a fi oju ri lasan ko le ya were tabi ko o binu, sugbon iwo binu. Nitorina, ojogbon elegbe mi, oro ti o so ko bosi. Omo eniyan ju ohun ti a fi oju ri nikan lo. Eda elemi ni wa!"

Ni awon orisirisi ona bayi ni awon Onigbagbo Ijo Abele ma afi iro inu awon ijiyan ninu Olorun wonyi han.

Ni ewon, Oloye Ijoba eto ilu bi mi lere pelu ibinu wipe, "Bawo ni yio ti se pe to ti o fi ma se isin ego re? Mo dahun wipe "Mo ti ri opolopo awon ti ko gbagbo pe Olorun wa ti nwon wa ti nwon nkabamo ni oju iku ni ori ibusun won wipe awon ti sai ni Olorun; nwon nkepe Kristi. Oha le ro wipe Onigbagbo le kabamo, nigbati iku ba sunmo tosi wipe oun ti je Onigbagbo ki o si wa kigbe pe Marx tabi Lenin lati gba oun lowo igbagbo oun? Okunrin yi wa bere si rerin o ni: " idahun Ologbon". Mo tun tesiwaju mo ni "Nigbati Ojogbon nipa ise ero ba ti ko afara kan tan, ododo wipe ologbo le koja lori afara yi ko fihan wipe afara yi dara. Oko oju irin nilati gba ori re koja lati fihan bi gbara afara yi tito. Ododo wipe iwo le saigba Olorun gbo nigbati gbogbo nkan rorun ko fi otito aigbagbo ninu Olorun yi han. Ko le duro ni akoko rogbodiyan

gidi." Mo si fi awọn iwe Lenin lati fi han wipe lehin igbati odi alakoso gbogbo ilu Soviet, Lenin papa gbadura nigbati awọn nkan ba yiwọ.

Awa ni idakeji beni a le fi suru duro fun idagbasoke awọn nkan. Awọn ti ngbe Ijoba Alasepo ni nwọn kole se suru ti nwọn si nsoro nipa itako isin. Nipa eleyi nwọn fi ohun ti Augtustine mimo so han wipe: "Ni aisimi ni okan wa titi yio fi simi ninu Re."

### idi re ti a file jere awọn ti ngbe ijọba alasepo papa

Ijọ Abele, ti enyin Onigbagbo ti ẹ wa ni ominira ba ran lọwọ yio jere awọn ti ngbe Ijoba Alasepo yio si yi oju aiye pada. Yio jere won, nitoripe koje iwa eda lati je ala-fowo-so-wopo pelu Ijoba Alasepo. Aja papa fe ni egun tire. Okan awọn ti ngbe Ijoba Alasepo yi ntako ohun ti nwọn nilati se ati awọn ohun odi ti nwọn nilati gbagbo.

Nigbati enikokan awọn ti ngbe Ijoba Alasepo ti gba wipe ohun gbogbo ni eyi ti a le ri ti a si le fi owo kan, wipe awọn ogun kan ti a se ni ona kan ni a je ati wipe lehin iku a o tun di iyo ati ohun alumoni ile pada, o to lati bi won lere wipe, "Bawo ni o ti se je wipe awọn ti nwọn ngbe Ijoba Alasepo ni awọn ilu pupo ti fi emi won fun ohun ti o

jo won loju pupo? Se "ekun owo ogun" le ni ohun ti o jo loju bi? Nje ohun alumoni ile le fi ara won rubo fun anfani awon ti o ku? Si awon oro wonyi, nwon ko ni idahun.

Ati lehin na, iwa iroro won! Olorun ko da eniyan ni eranko beni ko le fi mora lati ma huwa bi eranko fun igba pipe. A ti ri isubu awon Alakoso igba Nasi, ninu won pa ara won, sugbon awon miran ronupiwada nwon si jewo ese won.

Ohun kan wa ti a dara ninu imutipara ti o buru pupo ti o wa ni awon ilu Ijoba Alasepo. Ninu re, ongbe igbe aiye ti o fe wa, eyiti eto Ijoba Alasepo ko le fun won. Eto Ijoba ko jinle. Eni ti ngbe Ijoba Alasepo nwa igba aiye ti o jinle, nigbati ko ba si ri ni ibomiran, yio bere si wa mu oti. Ninu oti mimu yi ni o ti nse alaye ipaiya re nipa igbe aiye eranko ati ti etan eyi ti o nilati gbe. Fun iseju die oti yio fun ni ominira, gegebi otito yio ti fun ni ominira titi aiye, ti o ba le mo.

Ni Bucharest, nigbati awon eniyan Russia ngbe ibe, ofa okan kan ti nko le bori mu mi wo ile oti kan. Mo pe iyawo mi lati ba mi lo. Nigbati mo lo si inu re mo ri ogagun Russia kan pelu ibon ni owo re, ti o fi nderuba gbogbo eniyan, ti o si nbere oti si ti yio mu. Nwon ko fun ni oti nitoripe o ti yo gidi. Gbogbo awon eniyan wa ninu idagiri. Mo lo si odo eni ti o ni ile ita oti - oje eni ti o mo mi - mo si so fun wipe ki o fun Ogagun yi ni oti, mo si se ileri wipe ngo joko si egbe odo re lati ri wipe o wa ni idakeji. Bi igo oti

kan ti ntan ni nwon nfun ni omiran. Ni ori tabili wa, ago meta ni o wa nibe. Pelu owo ni ogagun yi fi nro oti si meteta yio si mu meteta. Iyawo mi ati emi ko mu. Bi o tile je 'pe o ti yo, emi re sise. Oti mimu ti mo lara Mo ba soro nipa Kristi o si fi eti sile lati gbo dada.

Ni ikehin, o so wipe: "Nisisiyi, o ti so fun mi eni ti iwo je, ngo so fun e eni ti emi na je, okan ninu awon Alufa Ijo atijo ni mi, mo si je okan ninu awon ti o koko se igbagbo mi, nigbati inunibini nla bere labe Stalin. Mo nlo lati ileto de ileto lati so fun awon eniyan wipe ko si Olorun ati wipe gegebi Alufa, mo ti je eletan. "Eletan ni mi be si ni gbogbo awon Ojise Olorun to ku pelu, ni ohun ti mo nso fun won. Nwon feran mi pupo nitori itara mi, nitorina mo wadi Oloye ninu egbe Olopa inu. Iya mi lati odo Olorun mi wa ni wipe pelu owo mi yi ni mo npa awon Onigbagbo lehin igba ti mo ba tida won loro tan. Nisisiyi mo wa nmu oti gan lati le gbagbe ohun ti mo ti se. Sugbon ko ri be."

Opolopo ninu awon ti ngbe Ijoba Alasepo ni nwon npa ara won. Be ni awon Akewi jankanjankan ninu won bi Essemia ati Maiakovski se se. Be ni Ojogbon ninu iwe kiko won Fadeeve se se. O sese pari iwe re kan ti o pe ni Inudidun ninu eyi ti o ti se alaye wipe inudidun wa ninu sise ise pelu aisimi fun eto Ijoba Alasepo. Inu oun fun ara re dun pupo nitori re de ibi ti o fi yin ibon pa ara re nigbati o ko iwe yi tan. O nira

ju fun okan re lati gba iru iro bayi. Joffe, Tomkin - awon asaju Ijoba Alasepo ti o gborin ati awon ti nwon nja fun eto Ijoba Alasepo ni akoko Czarist ko le roju lati wo bi eto Ijoba Alasepo ti ri ni otito. Awon na pa ara won gbehin ni.

Inu awon ti ngbe Ijoba Alasepo ko dun. Be si ni inu awon Alase won na ko dun. Bawo ni inu Stalin ti baje to! Lehin igbati o ti fe pa gbogbo awon elegbe re tan, eru nba nigba gbogbo wipe boya nwon le wa funoun ni majele je tabi ki nwon pa oun na papa. Yara mejo ni o ni ti o si se ti gegebi awon ibi ti a nko owo pamo si ni ile ifowopamo. Ko si eni ti o mo inu eyi ti o nsun ninu awon yara wonyi ni ale kan. Ko ni jeun afi ti eniti o se onje na baje ninu ounje na ni oju re. Eto Ijoba Alasepo ko mu ki enikeni ni inudidun, titi kan awon alase re. Aini nwon ni Kristi.

Ti a ba le bi eto Ijoba Alasepo subu ki ise awon ti eto Ijoba Alasepo nfi iya je nikan ni a ma da sile, sugbon a tun da awon ti ngbe Ijoba Alasepo yi fun ara won sile.

Ijo Abele ni o nse asoju ini awon ti o wa ni oko eru. E ran lowo!

Ohun ti o tayo ni ise Ijo Abele ni igbagbo otito re.

Ojise Olorun kan ti o parada nipa yiyi oruko re si "George" nso ninu iwe re nipa Ijo Abele ti Olorun ohun ti o sele.

Ogagun Russia kan wa si odo Ojise Olorun kan ni Hungary, o si so wipe oun fe ri i ni koro. Omokunrin yi je odo o si nkanju, beni o si mo eto ara re gegebi Olusegun. Nigbati nwon mu u lo si yara ipade kan ti nwon si ti ilekun, o te ori re ba si agbelebu kan ti o wa ni ara ogiri.

O so fun Ojise Olorun yi 'pe "O mo wipe iro ni kini yen. Ohun etan kekere kan ni ti enyin Ojise Olorun nlo lati fi tan awon talaka lati le fi mu ki o rorun fun awon Olola lati le fi mu won saimo. Ma bo nsisiyi, awa nikan ni a wa ni ibi yi! Gba fun mi wipe o ko fi igba kan gbagbo ni otitio wipe Olorun ni Jesu Kristi.

Ojise Olorun yi rerin muse. O ni " Sugbon iwo arakunrin mi, dajudaju mo gbagbo Otito ni."

Ogagun yi wa dahun wipe "Nko ni jeki o lo iwa etan yi le mi lori! Eyi le. Mase fi mi rerin!"

O fa ibon re yo, o si mu dani sunmo tosi ara Ojise Olorun yi.

"Afi ti o ba gba fun mi wipe iro ni ngo yinbonpa o e!" Nko le gba be nitori ko ki ise otito. 'Omo Olorun nitoto ni Oluwa wa," ni idahun Ojise Olorun yi.

Ogagun yi ju ibon re si ile o si gbe eniyan Olorun yi mo ara. Omi si nbo ni oju re.

O kigbe o ni "otito ni! Otito ni, mo gbagbo bee na sugbon nko ni idaniloju wipe eniyan le ku nitori igbagbo yi titi mo fi wadi

fun ara mi. A o seun! o ti mu ki igbagbo mi le si. Nisisiyi, mo le ku fun Kristi. Ọ ti fi han mi bi mo tise le se."

Mo ti mọ awọn miran bayi. Nigbati awon eniyan Russia gba Rumania, awọn omo ogun meji wo inu Ijo kan pelu ibon won ni owo won. Won so wipe: "A ko ni igbagbo ninu igbagbo nyin. Awọn ti ko ba ko o sile nisisiyi ni a o yin ibon pa! Enyin ti e ko igbagbọ nyin ẹ bọ si apa ọhun! " Awon kan bo si apa otun. Nwọn pase fun awọn wonyi ki nwon kuro ni ile isin yi ki nwọn si ma lo si ile. Nwon sa asala fun emi won. Nigbati o ku awọn eniyan Russia wonyi nikan pẹlu awon Onigbagbọ to ku, nwọn fa wọn mọra nwọn si so fun won pe: "Onigagbo ni awa na sugbon a fe ni ipejopo pẹlu awon ti nwon ka otito kun ohun ti a le ku fun."

Iru awon eniyan bayi ni nwon nja fun ihinrere ni awon ilu wa. Beni nwon ko ja fun ihinrere nikan. Nwọn tun nja bakanna fun ominira.

Ni ile awon Onigbagbo ti Iwo Orun, ọpolopo wakati ni nwọn nlo lati fi gbo awon orin aiye. Ni ile wa na, a le gbọ ariwo orin. Sugbon lati fi mu ki awon aladugbọ ma gbo oro ihinrere ati ise Abele ti a nse ki nwon ma ba lo se ofofo fun Olopa Inu.

Nko le so bi inu won ti dun to nigbati nwon ba ri Onigbagbo kan lati Iwo Orun ti o se Onigbagbo tooto!

Eni ti o nkọ awon oro wonyi koje nkankan.

Sugbon emi ni ohun awon ti ko ni ohun: awon ti a di lenu ti nwon ko si ni asoju ni Iwo Orun. Ni oruko won ni mo bere fun itara ninu igbagbo ati ni sise ohun gbogbo ti o baje ti isin Kristi. Ni oruko, won ni mo bere adura nyin ati iranlowo ti e ba le se fun Ijo Abele Oloto ti nwon njiya ni awon ile Ijoba Alasepo.

A o bori awon ti ngbe Ijoba Alasepo. Saju Olorun wa ni apa odo wa.

Lona keji nitori oro ti a fe ma ba won so ni o je ohun ti okan ko le sai ni.

Awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti nwon ti wa ni ewon ni akoko Nazi jewo fun mi wipe awon gbadura nigbati nkan ko ba rorun. Mo kan tie ti ri awon Oloye Ijoba Alasepo ti nwon npe "Jesu, Jesu" bi nwon ti nku lo.

A o bori nitoripe gbogbo ini oju lila awon eniyan wa ni o wa ni apa odo wa. Awon eniyan Russia le lodi si gbogbo awon ohun ti awon Onigbagbo akoko yi nko. Sugbon awon iwe Tolstoi ati Dostoievski wa, beni awon eniyan si nri imole Kristi ninu won. Be ni o si ri pelu Goethe ni Ila Orun Jamani, Szienkiewicz ni Poland ati awon miran. Sadoveanu ni eni ti o nkowe ti o lokiki julo ni Rumania. Awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti te iwe re ti a npe ni "Igbesiaiye awon Eni Mimo" jade pelu oruko miran ti nwon fun. Eyi ni "Itan awon Eni Mimo." Sugbon pelu oruko yi papa, apere igbesi-aiye awon Eni Mimo wonyi fun wa ni okun.

Nwon ko le yo ohun ti a ko nipa "Raphael," "Michelango," ati "Leonardo da Vinci"

kuro ninu awon itan na ti a se sinu iwe yi. Awon aworan wonyi nsoro nipa Kristi.

Nigbati mo ba nba okan ninu awon ti o ngbe Ijoba Alasepo soro nipa Kristi, awon ongbe okan re gan ni mo nba sore - Oluranlowo mi. Ohun ti o nira ju fun ni lati ma dahun awon ijiyan mi. Ohun ti o nira fun ni lati pa eri okan re, ti o wa ni apa odo mi lenu mo.

Emi fun ara mi ti mo awon Ojogbon ti nwon nko eko nipa Marx, awon ti oje wipe, ki nwon to ko eko nipa aigbagbo ninu Olorun, nwon a gbadura si Olorun lati ran won lowo ninu oro ti nwon fe so! Mo ti mo awon ti nwon ngbe Ijoba Alasepo ti nwon nlo si ipade ikoko ni ona jinjin. Nigbati owo ba te won, nwon a puro wipe awon ko wa ni ipade Abele. Nigbana ni nwon yio wa sun'kun , nwon o si ma kabamo wipe awon ko ni igboya lati duro fun igbagbo ti o mu won lo si ibi ipade yi. Eniyan ni awon na pelu.

Nigbati enikan ba ti gba igbagboiyi - bi o ti wu ki igbagbo na kere to - igbagbo yi yio ma dagba si i. O da wa loju wipe yio bori nitoripe awa ti a wa ni inu Ijo Abele ti ri ti o nbori lati igba de igba

Kristi feran awon ti ngbe Ijoba Alasepo. A le jere won fun Kristi, beni a nilati se be. Ijo Abele ti o wa ninu ewon nikan ni nwon le jere won. Enikeni ti o ba fe te ife Kristi lorun fun igbala awon okan gbogbo eda nilati ran Ijo Abele lowo ninu ise re. Jesu so wipe " E ko gbogbo Orile-ede". Ko so wipe e duro ninu ewon. Ise otito si Olorun ati ti ise nla ti a ran wa

fi ipa mu wa lati waasu koja ewon - si enikokan ninu awon meta ti o wa laiye ti a so si ewon lati owo eto Ijoba Alasepo. Ihinrere yi le de odo won ti a ba nran Ijo Abele ti o wa ni ibe lowo!

## AWON EGBE META NI NWON PAPO TI NWON NSE IJO ABELE: EKINI – AWON ALUFA ATI AWON OJISE OLORUN MIRAN GBOGBO TI IJOBA ALASEPO TI MU KURO NI IPO WON"

Awon egbe meta ni nwon papo ti nwon nse Ijo Abele ni ile awon ti ngbe Ijoba Alasepo. Egbe kini ni awon egberun aimoye Alufa ati awon Ojise Olorun ti a ti le kuro ninu awon Ijo won ati awon agutan won nitoripe nwon ko lati se ihinrere ni amulumala pelu eto Ijoba Alasepo. Opolopo ninu Alufa ati awon Ojise Olorun wawonyi ni nwon ti so si ewon fun opolopo odun ti nwon si ti daloro nitori igbagbo nwon. Nwon ti da won sile .. lesekese ni nwon si ti tun bere ise ihinrere nwon - ni ikoko ati pelu itesiwaju ni nwon nse ihinrere nwon lo ninu Ijo Abele. Bi o tile je 'pe awon ti ngbe Ijoba Alasepo ti awon Ijo won tabi ke wipe nwon mu elomiran ti won le "gbekele" ropo awon Alufa ati Ojise Olorun wonyi, awon Alufa ati Ojise Olorun wonyi nba ise nwon lo ni itesiwaju gidi ju ti tele lo nipa wiwaasu ninu

orule tabi eyi ti o wa ni abe ile, ni awon igbo kokiro ni ale - tabi ni ibikibi ti awon Onigbagbo ba ti pejo ni ikoko. "Ajeriku ti o nye" ni awon okunrin wonyi ti nwon ko ni dawo ise ihinrere won duro ti o sį ni ewu ati tun bo si owo awon ti ngbe Ijoba Alasepo fun idaloro ti o tun po si.

## EKEJI – AWON OMO IJO

Apa keji Ijo Abele ni opolopo awon okunrin ati obinrin ti nwon je omo Ijo toto. Ę jeki oye nyin wipe ko si eni ti o kan nje Onigbagbo lasan, tabi eni ti ko fi gbogbo okan sin tabi Onigbagbo ti o lowowo ni ilu Russia tabi China. Ohun ti nmu awon Onigbagbo lati se igbagbo ko kere rara. Ohun ti o tun ye ki a tun ranti ni wipe nse ni inunibini nmu ki awon Onigbagbo dagba si ninu igbagbo won - nwon a di Onigbagbo ti o njeri fun Kristi. Onigbagbo ti o njere okan fun Kristi. Inunibini Ijoba Alasepo ti se ise ti awon adaniloro yi 'o fe ki o se. Ó tije ki awon Onigbagbo gbona si ti o fije wipe iru awon Onigbagbo bayi sowon ni awon ilu ti ominira wa. Awon eniyan bawonyi ko mo idi re bi eniyan se leje Onigbagbo ti ko nife jere okan gbogbo eniyan ti oba pade.

Irawo pupa (eyi ni oruko iwe irohin Russia) ko oju ija si awon Onigbagbo ilu Russia, nwon si so wipe, "awon olusin Kristi ni ife lati fi

ekanna nwon mu gbogbo eniyan tiworatiwora." Sugbon igbesiaiye awon Onigbagbo ti o ndan jeki gbogbo awon elegbe won feran won ti nwon si bu ola fun won.

Ni iletokileto tabi ilukilu, awon Onigabgo ni nwon feran ju lati je alabagbe Nigbati ara iya kan o ba ya to be ge tiko le toju awon omo re, iya Onigbagbo ni yio wa ti yio si ba toju awon omo re. Nigbati ara okunrin kan koba ya tobe ge ti ko lege igi re, okunrin Onigbagbo ni yio ba ge igi na. Igbesi aiye Onigbagbo gidi ni nwon ngbe-nigbati nwon ba si bere si jeri fun Kristi, awon eniyan wonyi a teti sile nwon a si gbagbo - nitoripe nwon ti ri Kristi ni igbesiaiye won.

Nigbati o tije wipe Ojise Olorun ti a fun ni ase nikan ni o le soro ninu Ijo, oke aimoye awon Onigbagbo toto ni gbogbo koro awon ilu Ijoba Alasepo ni nwon njere okan fun Kristi, nwon jeri fun Kristi ni arin oja, ni idi awon ero omi ati ni ibikibi ti nwon ba lo. Awon iwe irohin Ijoba Alasepo so wipe awon Onigbagbo alapata ma nfi iwe ihinrere pelebepelebe si arin iwe ti nwon fi nii eran fun awon onibara won. Iwe Irohin Ijoba Alasepo so wipe awon Onigbagbo ti nwon je Oga ni awon ile itewe ma npada wa ni ale nigbati ko si enikankan nitosi, nwon a si lo ero itewe lati te awon egberin awon Onigbagbo die - nwon a si tun ti ilekun, nwon a lo ki ile to mo. Bakanna, iwe irohin Ijoba Alasepo so wipe awon omo Onigbagbo ni Moscow ti gba ihinrere lati "ibikan" nwon a si fi owo ko ninu re. Awon omo wonyi a fi awon ti nwon fi owo ko yi si apo ewu awon Oluko won ti awon

Oluko won fiko si awon ibi kolofin ni ile iwe. Apapo gbogboawon okunrin ati obinrin ti nwon je omo Ijo wonyi je awon onise ihinrere agbara ti nwon njere okan ti nwon si wa ni gbogbo awon ilu Ijoba Alasepo, beni ise won ntesiwaju pelu agbara.

Ni ilu Ijoba Alasepo ti a npe ni Cuba, awon Onise ihinrere ti nwon ti wa ni ibe tele ti so wipe "Ijoikoko kan ti ngberi nigbati oje wipe gbogbo awon Ojise Olorun toto ni nwon ti mu tabi ti nwon ti nse inunibini si, ti nwon si wa fi awon "Ojise Olorun" ti Ijoba Alasepo dipo won.

Awon oke aimoye Onigbagbo toto wonyi ninu Ijo yi ni a ti so di mimo nipa ina inunibini gan eyiti awon ti ngbe Ijoba Alasepo ro wipe yio pa won re.

## EKETA – AWON ALUFA ATI OJISE OLORUN TIKO NI JEKI A KO WON NI IJANU TABI KI A PA WON LENU MO

Apa keta Ijo Abele ti o se pataki ni opolopo ni awon Alufa oloto ninu awon "Ijo" ti Ijoba yan, ti nwon si ti ko ni ijanu ati pa lenu mo. Ijo Abele ki ise ohun ti a ya soto patapata kuro lara Ijo ti Ijoba. Ni opolopo awon ilu Ijoba Alasepo gegebi Yugoslavia, Poland ati Hungary, opolopo awon Alufa awon Ijo ti Ijoba wonyi ni nwon nsise ni ikoko ninu Ijo

Abẹle. Ni awọn ilu miran ifọwọ-sọ-wọpọ wa larin awọn mejeji. Nwọn ko gba fun awọn Alufa wọnyi lati sọrọ nipa Kristi ni ita yara kekere ti nwọn fi nse ile isin. Nwọn ko yọnda fun wọn lati ni ipade awọn ọmọde tabi ti ọdọ. Eru nba awọn alaigbagbọ lati wa. Nwọn ko yọnda fun Alufa Ijọ wọnyi lati gbadura fun awọn ọmọ Ijọ ti nwọn wa ni ailera ni ile wọn. Ofin Ijọba Alaṣepọ lo yi wọn ka eyiti o mu ki "Ijọ" wọn sai ni itumọ. Ni igba pupọ awọn Alufa wọnyi, ti ofin ti mu to bẹ ge ti o wa je ẹgan fun "Ominira Isin" nfi igboya fi ominira wọn wu ewu nipa siṣe iṣe ihinrere ni ikọko eyiti o jinle ju bi Ijọba Alasepo ti fe lo. Awon Alufa wonyi nba ise ihinrere lo ni ikọko fun awon omode ati awọn ọdọ. Nwon njihinrere ni ikokọ ile awọn Onigbagbo ati ni yara ti o wa ni abe ile. Nwọn ngba iwe awon Onigbagbo ni ikoko nwon si npin fun awọn okan ti ebi pa. Nwon nfi ominira won wu ewu nipa fifi oju fo awon ofin Ijoba Alasepo ti nwon si nwasu fun awon ọkan ti ebi npa ni gbogbo ayika won. Ni oju o dabi enipe nwon ntele ofin Ijoba Alasep, nwon nfi emi wọn wu ewu lati tan ọro Ọlọrun ka ni ikọkọ. Ọpọlopo awọn ọkunrin bawọnyi ni aipe yi ni asiri wọn ti tu ti Ijọba si ti mu ni Russai. Nwon da won lejọ opolopo ọdun ninu ewon.

Awọn ni apa keta ti o ṣe pataki ni ara Ijo Abelẹ.

Awon Ojise Olorun ri - ti Ijoba Alasepo ti le kuro ni Ijo ti nwọn si ti ṣe inunibini si, awon ọmo Ijo, awọn Alufa ti Ijoba yan ti nwon tun nba ise ihinrere miran lọ ni ikọko ti o gbona

ju bi Ijọba Alaṣepọ ṣe yonda rẹ - gbogbo awon wọnyi ni nwọn nṣiṣẹ ni Ijo Abele. Bẹni Ijọ Abẹlẹ yi yio wa titi a o fi bori eto Ijọba Alaṣepọ. Ni awon ile miran, apa kan nsise ju apa miran lọ - ṣugbọn gbogbo wọn ni nwọn wa ni ibe ti wọn nṣiṣẹ fun Kristi pẹlu ewu nla.

Ọkunrin kan ti o ma nrin irin ajo ni igbakugba ni awọn ilu Ijoba Alasepo, ti o si ni ifẹ ninu awọn ibere ti o ba jẹ mọ isin, de ni igbakan o si ko wipe oun o fi igba kan ri Ijọ Abele.

O dabi igbati eniyan ba rin irinajo ni arin Orile-ede Afrika, larin awon ti ko ka iwe, ti o si padạ de lati so wipe: "Mo ti wadi dada. Mo ti bi gbogbo nwọn lere ti nwọn ba nsoro li ona tara laise bi orin. Gbogbon nwọn so fun mi wipe awon o ki soro be." Otito ibe ni wipe, gbogbo won ni nwon nsọro ni ọna yi laimọ wipe ọna ti awon fi nsoro niyẹn.

Awon Onigbagbo isaju ko ko wipe Onigbagbọ ni awon. Ti oba bi wọn nipa isin wọn, idahun wọn iba ti ṣe wipe Ju ni awọn, tabi pe Ọmọ Israeli ni awon ti nwon ni igbagbo ninu Jesu gegebi Kristi, arakunrin, eni mimo ati wipe ọmọ Ọlorun ni awọn. Fun igba ekini ni Antioku ni awọn miran ti nwọn ri nwon fun won ni oruko "Onigbagbọ."

Ko si ninu awon ti ntelee Lutther ti o wipe oun ntẹle Luther. Luther fun ara re ni.o kọ orukọ yi pẹlu agbara.

"Ijọ Abẹlẹ ni oruko ti awon ti ngbe Ijoba Alaṣepo fun wa. Bena si ni pẹlu awon ti nwon wa lati Iwo Orun lati se iwadi nipa ipo isin ni ila Orun si ẹgbẹ ikoko kan ti a da sile lairo tele ni gbogbo awọn ilu Ijoba Alaṣepo.

Awon Omo egbe Ijo Abele ko pe egbẹ wọn pelu oruko yi. Nwọn npe ara won ni Ọmọ lẹhin Kristi, Onigbagbo, Ọmo Olọrun. Ṣugbon nwon nsaju ise Abele ni ikoko ni awọn ti npade, nwon ntan ihinrere ka ni awon ipade ikoko, beni awon alejo lati awon ilu miran ti nwon njiyan wipe Ijo Abele yi wa ma nwa si ibi ipade wonyi. Oruko ti o ba wa mu ni eyiti ota wa fun wa ati ti awon ti nwọn nwọ egbẹ ikokọ yi pelu iyanu ati ifẹ lati ita fun wa.

O le fi opọlopọ ọdun rin irinajo kakiri Iwọ Orun ki a ma ba ibujoko awọn ami lati Soviet pade, eyi ko fi han wipe ko si ibujoko awọn ami rara. Ohun ti o wa ni ibẹ ni wipe ko gọ lati fi ara rẹ han fun awon arinrinajo ti nwon ba fẹ mo.

Ni ori ti o tẹle egbe mo ko awon oro lati inu iwe irohin Soviet ti o nfi han wipe Ijo Abele yi wa ati bi pataki re ti ndagba si.

## ORI KEFA

### BI ISIN AWON KRISTIANI SE NSEGUN IJOBA ALASEPO

Mo ti sọ nipa iriri ti wa ninu ihinrere Kristi ni ikoko ni arin awọn Omo Ogun Soviet ati ni arin awon ti ngbe Ijoba Alasepo ni ilu Rumania

Mo ti be nyin lati se iranlọwo ninu wiwasu Kristi si awon ti nwon ngbe Ijoba Alasepo ati awon eniyan ti nwon nfi iya je.

Ipenija mi haje "ero lẹsan" ti "ko sese" bi?

Nje o ni itumo?

Nje Ijo Abele wa nisisiyi ni Russia ati awon ile miran ? Nje ise Abele sese nibe nisisiyi?

Si awon ibere wonyi a le dahun pelu irohin ayo.

Awon ti ngbe Ijoba Alasepo nse ariya wipe Ijoba Alasepo ti pe adota odun. Sugbon a ti bori isegun wọn. Isin Kristi ti bori - kise eto Ijoba Alasepo. Ile itewe Russia, eyiti egbe wa ntun yewo dada, kun fun irohin nipa Ijo Abele. Fun igba kini, Ijo Abele ti ni agbara to be ge ti ofi nse idaji ise re ni gbangba, ti o si nderuba awon ti nwon ngbe Ijoba Alasepo. Beni awon irohin ti a ngbo lati awon ona miran fi awon

irohin ile itewe Ijoba Alasepo mule.

Ranti pe Ijo Abẹlẹ dabi omi didi ti o lefo sori omi! Gbogbo iṣe re ni o fẹ wa ni abẹle, ṣugbọn die ninu ise yi ma nwa ni gbangba.

Nị awọn oju iwe ti o wa ni iwaju, mo ko die jo ninu awon irohin ti o se pataki.

## SONSO OMI DIDI TI O LEFO SI ORI OMI YI.

Ni ojo keje oṣu kọkanla ọdun 1966, ni Suhumi (Cancasus), ijọ Abẹlẹ ṣe ipade nla kan ni gbangba. Ọpọlọpo awon Onigbagbọ ni nwọn wa lati awọn ilu nla miran gbogbo si ibi ipade yi. Lẹhin igba ti a pe awon eniyan wa si iwaju fun ijewo ẹse tan, awon odo meta-din-ladota ni nwon gba Kristi sinu okan won ti a si se iribomi fun won ni ẹsekese ninu okun Dudu, gegebi ti Ijo Isiwaju.

A ko ya akoko kankan saju eleyi fun kiko eko ki a to se iribomi. Lehin adota odun ti Ijoba Alasepo ti npase, awon Ojise Olorun Ijo Abele ko ko ijinle eko nipa oro Olorun nitori ko si awon ile eko ti nwon ti le ko eko sii nipa oro Ọlọrun, bẹni ko si Bibeli tabi awon iwe kika fun awọn Onigbagbọ. Ṣugbon Philipi papa ti a yan ni Diakoni ko ni ijinle eko nipa oro Olorun. Bẹni nigbati Iwefa kan, ti o ti ba sọro boya fun wakati kan pere bii lere wipe: Wo, omi ni eyi, kini o le mu ki o sai se iribọmi fun mi? Philipi dahun o ni "Ti iwo ba gbagbo pelu gbogbo okan re, mo le se e." Nigbana, ni ẹsekese nwon sokale si inu omi, a si se iribomi fun Iwefa yi. (Ise awon Aposteli, ori kejo ese 36 -38).

Omi wa ni okun Dudu to, beni Ijo Abele ti bere awon ise Ijo Isiwaju.

Uchitelskaia Gazeta (iwe irohin awon Oluko) ti ojo keta-le-logun osu kejo odun 1959 mu irohin wa wipe ni Rostov-on-Don, awon omo Ijo Baptist ti nwon ko lati ko oruko awon omo Ijo won sile gegebi ofin ti a fi le ile ati lati ma se awon ohun ti "asaju Ijo" ti Ijoba yan ba wi bere si yan kakiri titi nwon si nso wipe awon ko fe awon asaju wonyi.

Oje ojo kini osu karun odun. Gegebi Jesu ti se awon ise iyanu re ni ojo isimi lati pe awon ara Pharisi ti nwon lodi si iru ise bayi ni ojo isimi, nija, Ijo Abele na yan awon ojo ti Ijoba Alasepo nija.

Ojo kini osu karun odun je ojo ase ninu eyi awon ti ngbe Ijoba Alasepo ma nse ariya gan, beni ofin so wipe gbogbo eniyan ni o nilati wa si ibi ariya yi. Sugbon ni akoko yi, agbara ti o se ekeji ti o tobi - eyi ni Ijoba Abele - na a jade si titi ni ojo yen.

Edegbejo awon Onigbagbo ni nwon wa. Ohun ti o fi ipa mu won ni ife won si Olorun nikan. Nwon mo wipe ninu ewon, ebi ati idaloro nduro de won.

Gbogbo Onigbagbo ni Russia ni o mo "ofin ikoko" ti awon Onigbagbo Onihinrere ti Barmani te, ninu eyi ti nwon so nipa bi arabibrin Hmara ti abule Kuluada, se gbo irohin wipe oko re ti ku ni ewon. Nisisiyi, opo ni o je, beni o ni awon omo kekere merin. Nigbati o gba oku oko re, o ri ami pampe ni owo re. Ina ti jo awon owo, ika ati atelese re gan. Oju obe wa ni apa isale ikun re. Ese re otun wu. Oju nina wa ni

ese re mejeji. Gbogbo ara re kun fun egbo lati owo nina pelu ibaje.

Gbogbo awon Onigbagbo ti nwon wa si ifihan ni gbangba yi ni Rostov-on-Don mo wipe o le se ohu ti yio sele si oun na niyi. Sibesibe nwon wa.

Sugbon nwon tun mo bakanna wipe ni oju ogunlogo awon Onigbagbo ni nwon sin ajeriku yi ti o ti fi emi re fun Olorun lehin osu meta ti o di Onigbagbọ. Beni nigbati nwon nse isinku rẹ, gbogbo won gbe awon pali dani ti ako si wipe:

"Fun mi lati wa laiye, fun Kristi ni ati lati ku ere ni"

"Maṣe bẹru awọn tị nwon npa ra, sugbọn ti nwọn ko le pa ẹmi!"

"Mo ri ni abẹ pẹpe awon ti a pa nitori oro Olorun."

Apẹrẹ ajẹriku yi fun awon ti nwon wa ni Rostov-on-Don ni okun. Nwon wa ni ori titi nwọn si yi ile kekere kan ka. Awon eniyan wa ni ibi gbogbo - awon miran wa ni ori orule ni itosi, awon to ku wa ni ori igi, gegebi Sakeu ni igba atijọ. Awọn ogorin eniyan ni o di Onigbagbo, awọn odo lo si poju ni arin awon ogorin yi. Ninu awon ogorin yi, meta-le-logun ni nwon jẹ omo odọ Don, nibiti nwon ti se iribomi.

Awọn ọkọ, ninu eyiti awon Olopa Ijoba Alasepo kun, de, nwọn si yi awon Onigbagbo wonyi po ni eti odo yi. Nwon nfe lati mu awon arakunrin ti nwon nsaju gbogbo awon Onigbagbo yi. (Nwon ko le mu gbogbo ẹdegbejo eniyan!) Gbogbo awon Onigbagbo wonyi ba wole ni ekun wọn, nwon si gbadura si Olorun

lati gbẹja awọn eniya Rẹ, ki o si jẹki o ṣese fun wọn lati se isin wọn ti ọjo yen. Nigbana ni awọn arakunrin ati arabinrin - bi nwon ṣe duro ni ẹgbẹ-kan-ẹgbẹ - yi awọn ẹlẹgbẹ won ti nwon nsaju isin na, nwọn si nni ero lati di awọn Ọlopa wonyi lọwọ lati mu won. Gbogbo nkan wa le gan.

Uchitelskaia Gazeta rohin wipe ẹgbẹ Baptisi "ti o lodi si ofin" ti o wa ni Rostov ni ile itewe kan ni abele ("Baptisi" ni Russia tumọ si awon Ijo Ajihinrere ati ti awọn Pentikosti). Nwon ma nte iwe jade ninu eyiti nwon ma npe awon odo lati duro fun igbagbọ won. Ninu ọkan ninu awon obi onigbagbo se ohun ti emi na ro wipe oje ohun ti o dara gan: "lati mu awon omo lo si awon isin isnku nitọri ki nwon le ko lati ma damu nipa awon ti nrekoja lọ." Bakanna nwon ni ki awọn obi Onigbagbo fun awon omo won ni eko nipa Igbagbo ki eyi si wa gegebi aporo fun aigbagbo ninu Olorun ti nwon nko won ni ile-iwe Ijoba Alasepo. Uchitelskaia Gazeta pari ọro re pelu ibere wipe: "Kini idi rẹ ti awon Oluko fi nfi iberu dapo ni igbesaiye awon ebi nibi ti ati nso awon omode di omugo (pelu isin?)"

"Iwe Irohin awon Oluko" yi tun so ohun ti o ṣele ni ibi ipelejo awon osise abele ti nwon ti se iribomi fun awon eniyan ni ikoko.

"Awoǹ odo ti o gbagbo ti a pe lati jeri ni ile ejo fi ile ejo Ijoba Alasepo pe okan. Nwon huwa pelu ibinu beni igbona won nipa isin ti poju. Awon odo obinrin ti nwon wa woran nwo awon ti a pe ni ejo pelu iyin beni iwo ti nwon nwo gbogbo awon eniyan ti ko gba

Olorun gbo fi han wipe inu won ko dun si ise won."

Awon egbe Ijo Abele ti sai ko pe nwon o na awon tabi pe nwon o so awon si ewon, nwon si ti bebe nigbangba fun ominira niwaju ile Olori egbe Ijoba Alasepo ti Russia.

A ni iwe ase ikoko nipa ti egbe Ijo Baptisiti Ajihinrere ti idapo ilu Soviet ti o "lodi si ofin", eyi ti o lodi si "idapo-Ijo-Baptisi" ti Ijoba Alasepo nse akoso ti afinihan Karev nsaju; eniti o nyin inurere awón Ijoba Alasepo ti nwon npa awon Onigbagbo bi ewure, beni o si ngbe "Ominira" ti leko ni igbesiaiye Soviet ti o ni ga (Ekefa, odun 1963). Nwon ti yo iwe ase yi mu wo Iwo Orun nipa ona ikoko.

Ninu re a so fun wa nipa ifihan ni gbangba awon akoni, eyi ti o sele ni Moscow gan.

Mo ntumo lati inu ikede ni gbangba yi:

"Oro pataki

"Enyin Olufe wa okunrin ati obinrin, ibukun fun nyin ati alafia lati odo Olorun, Baba wa ati Oluwa Jesu Kristi.

"Pelu ikanju ni a fi so fun yi wipe awon asoju awon Onigbagbo Ijo Baptisi Ajihinrere, ti nwon je edegbeta ni iye, ti nwon lo si Moscow ni ojo kerin-din-logun osu karun odun 1966 lati bo sarin Ijoba alagbara, lo si ile apapo gbogbo egbe ti egbe Ijoba Alasepo ti U.S.S.R. pelu ebe wipe ki nwon gba won ki nwon si gbo won.

"A fun Akowe gbogbo egbe wonyi, Brezhnev, ni awon ebe wa ti ako si inu iwe.

Ninu ikeda oro egbe wa yi, nwon tun so siwaju si, wipe awọn edegbeta eniyan wonyi duro fun gbogbo ojo niwaju ile yi. Oun loje ifihan ni gbangba ti akoko ti a fi lodi si eto Ijoba Alasepo ,ni Moscow. Beni awon asoju Ijo Abele ni won se e. Ni owo irole, nwon mu iwe ebe keji ti nwon ko si Brezhnev fun u, ninu eyi ti nwon so wipe "elegbe won" kan ti oruko re nje Stronganov ko lati mu ebe won wa si odo Brezhnev, ati wipe o si tun deruba won.

Awon asoju edegbeta yi wa ni ori titi fun gbogbo oru. Awon oko ti nkoja ntu eruku si won lara beni o nta ere si won lara, beni awon eniyan nbu won. Bi o tile je 'pe ojo ro ati wipe a fi iya je won bayi, nwon duro si iwaju ile yi titi ile fi mo!

Ni ojo keji, enikan da imoran wipe ki gbogbo awon edegbeta eniyan wonyi wo inu ile kan lo lati lo ba awon Oloye Ijoba Alasepo kek-eke, sugbon "ni mimo ti nwon mo wipe nina ni nwon ma nna awon Onigabgo ti o ba lo ba awon alase nigbati nwọn ba wo ile kan ni ibi ti ko ba si awon ajeri, awon asoju yi pa enu po lati ko aba yi ati lati duro titi Breghnev yio fi wa da won lohun.

Nigbana ohun ti a ko le bo lowo re sele.

Ni ago meji ku iseju medogun osan, awon oko meji-din-logbon wa, esan ti ko se ifaraba wa bere lori awon Onigbagbo wonyi. "A di ọwọ ara wa mu yipo, a si ko orin wipe: Awon ojo ti o dara julo ni igbesiaiye wa ni awon ojo ti a ba le gbe agbelebu wa. Awon eniyan Olopa Inu wonyi bere si lu wa, ati odo ati agba. Nwọn mu won jade kuro larin agbo yi, nwon a si lu

nwon ni oju, ni ori, beni nwon a ju won si ori titi. Nwon fa awon miran ninu awon arakunrin ati arabinrin wonyi ni irun ori lọ si inu awon oko wonyi. Nigbati awon miran ba gbiyanju lati lọ, nwon a lu won titi nwon a fi daku. Lehin igbati nwon tiko gbogbo Onigbagbọ wonyi sinu awon oko wonyi, nwon gbe won lo si ibiti enikan ko mo. Awon eniyan ngbo awon orin ti awon arakunrin ati arabinrin wa nko lati inu awon ọko Olọpa inu wonyi. Gbogbo iwonyi sele ni oju ọpo eniyan."

Nisisiyi, ohun ti o tun wa lewu gidi ni o sele Lehin igbati a mu awọn edegbeta wonyi ti a si da wọn loro tan, arakunrin G. Vins ati arakunrin asaju kan, Horev (awon Oluso-agutan agbo Kristi gidi), si ni igboya lati lo si ile apapo egbe Ijoba Alasepo kanna yi - gegebi igba ti a mu Johannu Baptisi mimo, Jesu bẹre iwasu gbangba Re ni ibikanna ati pelu oro kanna eyiti Johannu Baptisi njiya nitori re "E ronupiwada, nitori Ijoba Orun ku si dede."

Vins ati Horev bere ibi ti awon elegbe won ti a mu wa, nwon si bere fun idasile won. Awon arakunrin meji ti nwon ni igboya yi kan ra ni. Lehinna, a gbo irohin wipe nwon wa ni ẹwọn ni Lefortovskaia.

Eru ha ba awon Onigbagbo Ijo Abele yi bi? Rara! Awon miran ni ẹsẹkẹse tun fi ominira won wu ewu, nwon si tun tẹ ero agbo wa ti a ni niwaju wa jade, nwọn si sọ itan gbogbo ohun ti o ṣẹle, nwon si so 'pe fun awon arakunrin ati arabinrin wọn, "nwon ni ore-ofe lati ni igbagbo ninu Kristi, ati lati jiya fun '" (Philip 1 :29) Nwon gba awon arakunrin wonyi ni iyanju pe

"ki enikeni mase damu nitori awon iponju wonyi, nitori eyin fun ara yin mo wipe ohun ti a yan fun wa ni." (1 Thes. 3:3). Nwon tun toka si Hebru 12:2 nwon si so fun awon Onigbagbo lati wo "Jesu Olupilese ati Olupari Igbagbo wa , eniti o ti tori ayo ti a gbe si iwaju Re o fi iku agbelebu mora, ko si ka itiju ibe si."

Ijo Abele ti lodi si fifi aigbagbo ninu Olorun ko awon odo ni Rostov, ati Moscwo - ati yipo gbogbo Russai. Nwon nba iwa fifi oro (eyi ni eko aigbagbo ninu Olorun) fun awon odo ja, bakanna nwon doju ija ko awon asaiu Ijo ti Ijoba da sile ti nwon je alarekereke. Nwon ko nipa re si okan ninu awon iwe ikede ero wa wipe: "Ni akoko tiwa, satani npase beni Ijo si ngba gbogbo awon ase wonyi ti nwon lodi si awon ofin Olorun." (Lati inu Pravda Ukraini ti ojo kerin osu kewa odun 1966).

Pravda Vostoka te ipelejo ti a mu kan Alexei Neverov, Boris Garmashow ati Aler Zubov, ti nwon nko awon egbe jo lati gbo ihinrere ti a nfun kakiri lati Amerika ni ori ero gboungboun.

Nwon nko awon iwasu wonyi sile pelu ero, eyiti nwon wa nmu yi arin ara won kakiri.

Nwon tun fi esun kan won wipe nwon nse eto ipade lati wasu ni ikoko nipa siso wipe awon nse ijade lo sire tabi ki nwon so wipe "egbe awon ti nya aworan" ni o pejo. Nipa eyi Ijo Abele nsise - gegebi awon Ijo isaju ti nsise ni awon odede ti o wa ni abe ile nibi ti a nsi oku si.

Sovietskaia Moldavia ti ojo kedogun osu kesan odun 1966 rohin wipe Ijo Abele nte awon

iwe kekeke jade. Nwon npejo ni ibiti awon eniyan po si, bi o tile je wipe eleyi lodi si ofin, nwon a si ma lo lati ibikan de ekeji lati jeri fun Kristi.

Iwe Irohin Kanna yi ni o tun wipe ninu oko oju irin lati Reni si Chisinan, awon odomokunrin meta ati odomobinrin merin ko orin Onigbagbo kan wipe "E jeki a ya igba odo wa si mimo fun Kristi. Onirohin yi jewo wipe oun na sote nitoripe awon Onigbagbot wonyi nwasu "lori titi ni ibi iduro oko ile, ninu oko oju irin ati papa, ni awon ile eko Ijoba" lekan sii Ijo Abele niyi, ti o nşise loni ni Russia.

Nigbati nwon nse ejo awon Onigbagbo wonyi ti nwon da won lebi lori esun wipe nwon nko orin Onigbagbo ni gbangba larin awon eniyan, awon ti a da lejo na wole ni ekun won nwon si so wipe: "A jowo ara wa si owo Olorun A dupe lowo re Oluwa, nitoripe Iwo yonda wa lati jiya fun igbagbo yi." Nigbana ni Madan ti "ara re gbona ju nipa igbagbo" le orin ti a titori re da awon elegbe won lebi ewon ati idaloro, awon ti nwon si wa si ile ejo si gbe onn na.

Ni ojo kini osu karun, awon Onigbagbo awon ileto meji kan, Copceag ati Zaharovka, nigbati nwon ko ni ile isin, se eto fun isin ti o kun fun agbara Olorun ni ikoko ninu igbo!

Bakanna nwon ndibon wipe awon nse ajoyo ojo ibi, nwon a si ma fi eyi se eto isin. (Opolopo ebi awon Onigbagbo ti nwon to merin tabi marun a ma ni "ojo ibi" to bi merindin-logoji ninu odun lati fi bo awon ipade ikoko won).

Ko si ewon tabi idaloro ti o le deruba awon Onigbagbo Ijo Abele. Gegebi ti Ijo Isaju, nse ni inunibini nmu ki awon Onigabgo jinle si ninu isin won.

Pravda Ukraini ti ojo kerin osu kewa odun 1966 so bayi nipa Arakunrin Prokofiev - okan ninu awon asaju Ijo Abele ti Russia - wipe o ti lo si ewon ni emeta, sugbon bi a ba ti ndasile, yio tun ma se eto ile eko ojo sisimi ni ikoko. Nisisiyi nwon ti tun mu u.

O ko bayi si inu okan ninu awon ero wa ti ikoko wipe: "Ni gbigba awon ofin eniyan (o nso nipa awon ofin Ijoba Alasepo), Ijo ti Ijoba da sile ti padanu ibukun Olorun."

Ma si se ro ewon gegebi o ti ri ni Iwo Orun nigbati enyin yio gbo nipa arakunrin Russia kan ti a ju si ewon. Ewon ni ibe tumo si fifi ebi paniyan, idaloro ati yiyi ni ni opolo pada.

Manka i Religia (eyi ni imo eko ijinle ati ti isin) kesan ti odun 1966 fi sun wipe awon Onigbagbo npin awon iwe ihinrere fun awon eniyan ninu pali ehin iwe Ogoniok - iwe irohin igba de igba bi ti "Look" tabi - Time". Nwon nfun awon eniyan ni iwe pelu ehin iwe kan ti a npe ni Anna Karemina, iwe ti Leo Tolstoy ko. Ninu re, ese Bibeli kan yio wa ni ibe!

Nwon nko awon orin. Ohun orin ti nwon si fi nko dabi ti orin ti nwon fi npon Ijoba Alasepo, sugbon awon oro re nfi iyin fun Kristi! (A ka eleye ninu Kazakstanskaia Pravda ti ojo ogbon osu kefa odun 1966).

Ninu iwe ikoko kan ti a te jade ni kutunda

(Siberia), awon Onigabgo so wipe awon asaju "Ijo Baptisi" ti Ijoba yan "ti ba Ijo ati awon Onise re toto kakiri aiye je, ni ona kanna gegebi awon Alufa agba, awon Akowe ati awon Farisi se fi Jesu Kristi han fun Pilatu." Sugbon Ijo Abele ti oje oloto nsise lo!.

Iyawo Kristi nsin Kristi lo! Ijoba Alasepo fun ara won gba wipe oto ni mo wi nigbati mo ba fi ye won 'pe Ijo Abele njere awon ti ngbe Ijoba Alasepo fun Kristi. A le jere won!

Bakinskii Rabohi Osise Baku) ti ojo keta-dinlogun odun 1966 te iwe kan jade ti Tania Gugunova (omo egbe Adehun awon odo Ijoba Alasepo) ko, eniti Kristi jere. Awon Alase Ijoba Alasepo gba iwe yi. Iwe na lo bayi:

"Egbon mi Nadia owon, ńo ḿu ibukun lati

odo Oluwa Olufe wa ranse si nyin. Egbon mi Nadai, mo ni igbagbo wipe itumo awon oro wonyi ye nyin: "Fe awon Ota re, bukun awon ti nwon nfi o bu, se rere si awon ti nwon korira re beni ki o si gbadura fun awon ti nwon nlo e ni ilo ibaje."

Nigbati nwon gba iwe yi, Peter Serebre-rrikov, arakunrin re ti o mu Taniaati opolopo awon odo Ijoba Alasepo to Kristi wa nilati lo si ewon. Iwe irohin Ijoba Alasepo te die ninu awon iwasu re jade nibi ti o ti so wipe: "A nilati gba Olugbala wa gbo gegebi awon Oni-gbagbo isaju se gbaagbo. Fun wa, ofin ti o tobi julo ni Bibeli. A ko ka nkan miran si. A nilati se kiakia lati gba awon eniyan la lati inu ese won, papa julo awon odo." Nigbati nwon so fun

u wipe ofin ilu Soviet ko yonda wipe ki a so fun awon odo nipa Kristi o dahun o ni: "Fun wa, ofin kan soso ti o wa ni Bible." - idahun ti o to nibiti osika tiko gbagbo pe Olorun wa ti npase fun ilu.

Nigbana ni iwe irohin Ijoba Alasepo wa soro nipa awon "eniyan-keniyan". Awon odo okunrin ati obinrin ma nko awon orin emi. Nwon ngba iribomi gegebi ilana isin nwon si nse ibi won lo, eyi ni eko wipe ki eniyan feran otare."

Bakinskii Rabocii so wipe opolopo awon odo okunrin ati obinrin, ti nwon npe ara won ni omo egbe Adehun awon odo Ijoba Alasepo nse be lati fi boju ni, wipe nitoto Onigbagbo ni nwon! O pari iwe ti o ko yi pelu awon oro wonyi: "Awon ile eko Ijoba Alasepo na sai lagbara o, o ma kun fun ara ke beni ko si imole nibe.. to be ge ti awon Alufa fi le gba awon omo ehin re lati abe inu awon Oluko ti ko bikita."

Kazakstanskaia Pravda ti ogbon ojo osu kefa odun 1966 mu oro yi jade lati inu awon iwe pelebe ti Ijo Abele ko si awon obi wipe: "E jeki a sa ipa wa ati adura wa po lati le ya igbesiaiye awon omo wa soto fun Olorun lati igbati nwon ba si wa ninu ite won! E jeki a gba won omo wa lowo agbara aiye."

Awon ipa wonyi ti yori si rere! Iwe Irohin Ijoba Alasepo jeri si i! Isin Kristi ntesiwaju mo arin awon odo! (Iwe Irohin kan lati Celiabinsk, ni Russia so bi omobinrin kan, omo egbe Adehun awon odo Ijoba Alasepo, ti oruko re nje

Mina se di Onigbagbo. Nipa wiwo inu apejo awon Onigbagbo ti nwon ni ni ikoko ni.

Sovietskaia Justitia ede san ti odun 1966 nso nipa iru ipade Abele yi. "Ni oru ni nwon ma nse ipade yi. Ni ikoko, ni isora papa fun ojiji ara won, awon eniyan nwa lati ona pupo. Gbogbo won a si kun inu yara ti o sokunkun yi eyiti ko ga soke pupo. Nwon po to be ge ti ko fi si aye lati kunle. Nitori aisi ategun to, ina atupa ti nwon nlo a ku. Oogun a si ma san ni oju gbogbo awon ti nwon wa ni ibi ipade yi. Ni oju titi, okan ninu awon Ojise Olorun yi a ma sona fun awon Olopa." Sugbon Mina so wipe ni iru ipejopo bayi, nwon ni, gegebi emi na ti ni nisisiyi, igbagbo nla ti o kun fun imole - igbagbo ninu Olorun. Olorun ngbe wa si abe abo Re. Jeki awon omo egbe Komsomol ti nwon mo mi koja ni egbe mi lai ki mi! Jeki nwon fi egan wo mi, ki nwon si pe mi, bi eni ngba mi ni eti, ni "Baptisi"! Je ki nwon se be! Nko ni won fi se.

Opolopo awon odo Ijoba Alasepo, bi Mina ni nwon ti pinnu lati sin Kristi titi de opin.

Kazakhstan Pravda ti ojo keji-din-logun odun 1967 so nipa ipelejo awon arakunrin Klassem, Bonder ati Teleghin. Nwon ko so fun wa ejo ti nwon da fun nwon, sugbon nwon se ese won. Nwon ko awon odo nipa Kristi.

Sovietskaia Kirghizia ti ojo kedogun osu kefa odun 1967 wipe awon Onigabgo "ni nwon se ohun ti a fi nfi ofin lile mu won." Nitorina awon Alase Ijoba Alasepo ti owo won mo,

nigbati a nmu won bimu nigbagbogbo de ibi wipe ki nwon mu awon Onigbagbo ti nwon nse orikunkun ti nwon ko ni itelorun pelu wiwa ni ominira, ti tun mu awon miran. Ese won ni wipe nwon fe ni ile itewe, ti o lodi si ofin, ti yio ni ero itewe medogun ati ero ti o fi nse awon iwe odindi mefa, ni ori eyi ti nwon ti fe ma te awon iwe Onigbagbo.

Pravda ti ojo kokan-le-logun osu keji odun 1968 awon esun wa wipe egberun awon agbagba obinrin ati odomobinrin ni nwon ni ti nwon nlo igbanu ati aso tere ni ori eyi ti a ti nte awon ese Bibeli ati adura. Awon Alase se iwadi nwon si ri wipe eniti o mu iru ona titun bayi wa, eyiti mo le so wipe ki nwon ma lo ni Iwo Orun na, ni Onigbagbo kan ti oje okan ninu awon Olopa Ijoba Alasepo, arakunrin Stasink ti Linbertz. Iwe Irohin fi lo wipe nwon mu u.

Lati orun ni awon idahun ti awon Onigbagbo Ijo Abele ma nso , nigbati a ba mu won lo si ile Ejo Ijoba Alasepo, ti nwa. Adajo kan bere o ni: "Kini idi re ti e fi ma nfa awon eniyan si egbe yin ti o lodi si ofin?" Arabinrin Onigbagbo kan dahun o ni: "Ohun ti a nlepa ni lati jere gbogbo aiye fun Kristi."

Ni ipelejo miran, Adajo ibe so wipe: " Isin nyin lodi si Imo Ijinle." Akeko omobinrin ti a fi esun ka yi dahun o ni: "Iwo ha mo Imo Ijinle yi ju Einstein ati Newton bi? Onigbagbo ni nwon. Oruko Einstein ni aiye wa yi nje. Mo ti ko eko ni ile eko giga wipe oruko aiya wa yi ni Aiye Einstein. Einstein ko iwe bayi pe: Ti a ba fo Isin awon ara Israeli ti awon Woli ati

Isin Kristi gegebi Jesu ti ko ati ohun ti o wa lehin na papa lati se akoso nkan ti aiye, a o ri isin ti o le gba gbogbo aiye la lowo gbogbo awon iwa ibi ti aiye. Eto mimo gbogbo eda ni lati sa ipa re de gongo lati mu ki isin re bori! Si ranti Ojogbon ninu Imo Ise gbogbo ohun alaiye wa Pavlov! Awon iwe tiwa ko ha wi fun wa wipe ONigbagbo ni ise? Marx papa, ninu oro itumo kekere ti oko si ibere iwe ti a npe ni Das Kapital so wipe "Isin Kristi, ati papa ona ti awon Onigbagbo ti nwon ya ra won kuro lara Ijo ti Romu gbe gba, ni Isin ti o pe ju lati fi tun awon iwa ti o ti baje nitori ese se." Mo ni iwa kan ti ese baje. Marx ti ko mi lati di Onigbagbo lati le fi tun iwa yi se. Bawo ni enyin, ti e ntele ilana Marx se fe da mi lejo fun eleyi?"

Ororun lati ri dii re ti Adajo yi ko fi le soro.

Si esun kanna wipe awon Onigbagbo ni Isin ti o lodi si Imo Ijinle, Onigbagbo kan dahun ri ile Ejo bayi pe: "O da mi loju, ogbeni Adajo, pe Imo Ijinle tire ko to ti Simpson, eniti o jagbon awon orisirisi ogun. On, nigbati a bi lere wipe kini o ro wipe ose ohun ti o tobi julo ti oun jagbon re? O dahun o ni: "Ki ise ogun ti a fi nmu eniyan sun wora ti a ba fe se ise abe fun. Ohun ti mo jagbon re ti o tobi julo ni wipe mo mo ara mi ni elese ati wipe ore-ofe Olorun nikan ni ole gba mi.

Igbesiaiye ifi ara eni rubo eje eyi ti nwon setan lati ta sile fun igbagbo won, ni oje ijiyan ti o tobi julo fun Isin Kristi eyiti Ijo Abele na si iwaju. O je ohun ti Onise Olorun ni ile Afrika,

Albert Schweitzer, pe ni "Idapo mimo awon ti nwon ni ominira", idapo eyiti Jesu, okunrin ibanuje, pelu. Ide ife ni o so Ijo Abele ati Olugbala re po. Ide yi kanna ni o so awon omo Ijo yi pelu ara won. Ko si enikan ni aiye ti o le bori won.

Ninu iwe kan ti a yo mu jade ni ikoko, Ijo Abele so bayi pe: "A ko gbadura wipe ki a je Onigbagbo ti o dara ju eyi lo, sugbon wipe ki a le je iru Onigbagbo kan soso na ti Olorun fe ki a je: Awon Onigbagbo bi Kristi, eyi nipe, awon Onigbagbo ti nwon nfi tifetife gbe agbelebu won fun ogo Olorun."

Pelu ogbon ejo, gegebi Jesu ti ko wa, awon Onigbagbo ma nko nigbati a ba bi won lere ati niwaju ile Ejo lati so eniti awon asaju won ise.

Pravda Vostoka (Ododo iha Orun) ti ojo kedogun osu kini odun 1966 so fun wa gegebi enikan ti a fi esun kan, Maria Sevcink, nigbati a bi lere eniti o mu to Jesu se dahun wipe: " Olorun fa mi sinu Ijo Re." Nigbati a bi elomiran wipe: "Tani Asaju nyin?" O dahun wipe "A ko ni Asaju ti o je eniyan."

A bi awon omode Onigbagbo wipe, " Talo ko nyin lati fi awon asaju nyin sile ki e si bo okun pupa orun nyin?" Nwon dahun wipe "Ko si eni ti o ko wa. Fun ara wa ni a roo ti a si see.

Bi o tile je 'pe ni awon ibikan ibi sonso "Omi didi to nfo loju omi" ma nhan, ni awon ibomiran, awon Onigbagbo ma nse iribomi fun ara won ki a ma ba mu awon asaju won. Ni

awon ibikan, nwon ma nse iribomi ni inu odo, ẹniti a nse iribomi fun ati eniti o nse iribomi na a si wo nkan lati fi bo oju won ki enikeni ma ba le ya aworan wọn.

Uchitelskaia Gazeta ti ojo ogbon osu kini odun 1964 so nipa eko kan ti a ko awon eniyan ni Abule Voromin ni adugbo Volnecimo-Korskii, nipa aigbagbo ninu Olorun. Bi eko yi ti pari gele, "awon Onigbagbo ibe bere si tako awon ohun ti nwon so ninu eko na ni gbangba nipa opolopo ibere," eyiti Oluko ti oko eko yi ko le dahun. Nwọn bere wipe "Nibo ni ẹnyin ti e ngbe Ijoba Alasepo ti mu awon eko nipa ihuwa dada ti e nso, sugbon ti e ko tele jade - gegebi 'Iwo ko gbodo jale, ati mase paniyan? Awon Onigbagbo wonyi so fun Oluko yi pe gbogbo awon eko wonyi wa lati inu Bibeli eyiti awon ti ngbe Ijoba Alasepo doju ija ko. Gbogbo nkan daru mo Oluko yi loju, eko na si pari pelu isegun fun awon Onigbagbo!

INUNIBINI SI IJO ABELE NDAGBA SI I

Awon Onigbagbo Ijo Abele njiya si loni ju ti atehinwa lo. Gbogbo isin ni nwon nse inunibini si ni Russia. Fun awon Onigbagbo, o je ohun ibanilokanje lati mọ iya ti awon Ju nje ni awon ilu Ijoba Alasepo. Sugbon Ijo Abele gan ni nwon doju inunibini wonyi ko julo. Iwe Irohin Soviet nso nipa opolopo awon ti nwon mu ti nwon si npe lejo. Ni ibikan, meji-le-logorin awon Onigbagbo ni nwon so si ibi ti nwon nko awon asiwere si. Merin-le-logun loku lehin ojo die nitori "adura agba-isimi"! Lạti igba wọ ni a ti gbo wipe adura agba-isimi, npa eniyan? Nje o le woye ohun ti nwon nla

kọja?

Iya ti o buru julọ ti nwọn fi nję wọn ni wipe, ti nwọn ba jagbọn wipe nwọn nkọ awon ọmo won nipa Kristi, nwon yio gbe awon omo wọnyi lọ kuro ni odo won titi lai - beni nwon ko gbodo wa ki won ni ibiti nwọn ba wa.

Egbe Soviet fi owo si iwe kan ti "United Nations" gbe jade ninu eyi "ti nwon lodi si ifiiyato si arin ara wa nipa eko", eyiti o so wipe: "Awon obi nilati ni eto lati ko awon omo won ni eko nipa isin ati ihuwa si gegebi o ba ti lo to ni oju wọn." Afinihan Karev, aṣaju ęgbę Ijo Baptisi ti Egbe Soviet, ninu iwe ti a so nipa re, saju, so wipe awon gba eto yi towo-tese ni Russia - awon ti a si ntanje gbagbo! Nisisiyi, e teti si ohun ti iwe irohin Soviet wi:

Sovietswaia Russia ti ojo kerin osu kefa odun 1963 tun so gegebi omo Ijo Baptisi, Makrinkowa se ni omo mefa ti a gba lowo re, nitoripe o kon won ni igbagbọ awọn Onigbagbo ati wipe o so wipe nwon ko gbodo wo okun tere pupa ti awon asaju won si orun.

Nigbati o gbọ idajọ yi, o dahun o ni: "Mo njiya nitori igbagbọ mi ni." O nilati san owo ijoko ni ọgba awon omo ti nwon gba lowo re. Nisisiyi, nwọn ti nfi ọro aigba Olorun bo won. Enyin iya Onigbagbo, e ronu leri irora rẹ!

Uchitelskaia Gazeta so fun wa wipe ohun kanni ni o sele si Ignatii Mullin ati iyawo re. Adajo pase wipe ki nwọn fi igbagbo sile. Adajo na so wipe "E yan ọkan ninu Olọrun ati ọmobinrin nyin. Ọlọrun ni e ha yan bi? Ọkunrin yi dahun, o ni: "Emi ko ni jọwọ igbagbọ mi."

Paulu wo wipe: "Ghogbo ohun ni nsise po fun rere..." Mo ti ri iru awon omo bawonyi ti a ko ni ona igbagbo ti a gba lowo awon obi won ti a si fi si ile eko Ijoba Alasepo. Dipo ki nwon gba eko aigbagbo ninu Olorun ti a fi ko won, nwon ntan igbagbo ti a ko won ni ile si awon omo to ku!

Bibeli so wipe enikeni ti o ba feran awon omo re ju Jesu, ko ye fun Kristi. Awon oro wonyi ni itumo ninu awon ewon wa.

Gbiyanju ki o gbe ose kan lai ri awon omo re! Nigbana ni o mo awon iya ti awon elegbe wa ni Russia nje.

Ki a ma gba eto awon obi lowo won si nlo titi di oni papa. Awon ododo ti a gbo gbehin lati inu iwe irohin Soviet fun ara re so fun wa nipa iya Afin Sitsh lati owo eniti, gegebi Znamia lumosti ti ojo kokandin-logbon osu keta odun 1967, a gba omo re Vsetsheslar nitoripe o ko o lati ma ni iberu Olorun ati Iya Afin Zabavina ti Habarovsk ti a gba omo omo re Tamia ti awon obi re ti ku nitoripe o fun u ni eko igbagbo "ti ko ba iwa eda mu." ( a ka a yi ninu Sovietskaia Russia ti ojo ketala osu kini odun 1968).

Ko ni dara to ti a ba so nnipa awon Onigbagbo ti nwon ya ara won kuro lara Ijo Romu ti nwon wa ninu Ijo Abele nikan.

Awon Onigbagbo, ti igbagbo won ba ti Ijo Romu isaju mu, ti nwon wa ni Russia ti yipada patapata. Oke aimoye won ni nwon ti gbe ewon koja. Ninu ewon wonyi, nwon ko ni ileke, tabi ere Kristi lori agbelebu, nwon ko ni

awon aworan mimo, ko si turari tabi abela. Awon omo Ijo wa ni ewon lai si Alufa ti a ta ororo le lori. Awon Alufa ko ni ewu, ko si akara ojumo, ko si oti waini lati ya sí mimo, ko si ororo mimo, ko si awon iwe ti a ti ko adura si ti nwon yio ka. Nwon si ri wipe awon le ma se isin won lai si awon nkan wonyi nipa tito Olorun lo tara ninu adura. Nwon bere si gbadura, Olorun si nda Emi Re le won lori: Atunji lati oju orun emi ti o mule, eyiti o fe re ba ti ipilese isin Kristi mu. nsele larin awon Onigbagbo ti isin won ba ti Ijo Romu mu ni Russia.

Be na ni o si ri wipe ni Russia, ati ni gbogbo awon ilu ti o wa ni ayika re, Ijo Abele ti isin won ba ti Ijo Romu atijo mu, wa, ti o si je wipe isin won jinle ninu ihinrere, o dabi ti ipilese, beni nwon si sunmo Olorun gidigidi. Die ninu ilana isin Ijo Romu atijo ni nwon nmuse gegebi ohun ti o ba won lara mu. Talo le so ibiti alagba asaju won Bisobu, Yermogen ti Kalugu wa nisisiyi? O fi igboiya tako ifowo-sowopo ti o wa larin Bisobu alagba julo ti Ijo Romu ati Ijoba Alasepo.

Adota odun ti Ijoba Alasepo ti njoba! Iwe irohin Russia si kun fun isegun Ijo Abele. O ngba arin irora ti ko se fi enu ba, sugbon o duro sinsin... o si ndagba.!

Awa ti a wa ni Rumania ti gbin irugbin ihinrere nipa ise ikoko wa ni arin awon omo ogun Russia. Be si ni awon ti nwon wa ni Russia fun ara re ati awon ilu Miran gbogbo ti awon eniyan Russia ngbe ogun de . Awon irugbin

wonyi ti so eso.

A le jere gbogbo awọn ti nwọn ngbe Ijọba Alaṣepọ fun Kristi. Awọn ti nwọn ngbe Ijoba Alasepo le di Onigbagbọ. Bẹ si ni awọn ti nwọn nfi iya jẹ, ti a ba le ran won lọwọ.

Eri wipe otitọ ni ohun ti mo sọ ni wipe Ijọ Abẹle ngbile ni Ẹgbẹ Soviet, ni China ati papa o fẹ kari ni gbogbo awon ile Ijoba Alasepo.

Lati fi ẹwa awon Onigbagbo, ẹlẹgbe wa han ti nwọn njiya gidi, mo kọ die ninu awọn iwe ti awon Onigbagbọ Russia nkọ si ara wọn lati inu ẹwọn ni nwọn ti kọ awọn ti o gbẹhin.

## BIVARIA, ỌMỌBINRIN IJOBA ALAṢEPO SE RI KRISTI, TI O SI NJẸRI FUN KRISTI O SI WA DI ẸRU - AṢIṢẸ

Awon iwe meta isaju wa lati owo Maria omobinrin ti o mu Varia to Kristi wa.

Iwe kini

".. Mo si ngbe ihin. A fe mi pupopupo. Okan ninu awon omọ ewon Komsomol, ( Egbe adehun awon odo Ijoba Alasepo) na feran mi gidigidi. O so fun mi 'pe 'oye iru ẹda ti oje ko le ye mi. Nibi, opolopo ni nwọn nbu e ti nwọn si nfi iya je e, sibesibe, o feran gbogbo wọn. Mo dahun wipe Ọlọrun ti kọ wa wipe ki a feran gbogbo eniyan, ki iṣe awọn ọre nikan, ṣugbọn awọn ọta pelu. Tẹlẹ ọmobinrin yi fi iya jẹ mi pupọ, ṣugbon pẹlu itara ni mo fi gbadura fun u. Nigbati o bi mi wipe boya mo le fẹran

oun na pẹlu, mo fa a mọra, awa mejeji si bẹrẹ si sọkun. Nisisiyi a jọ ngbadura ni.

Jọwọ gbadura fun Varia ni orukọ rẹ.

Nigbati o ba tẹti si awọn ti nwọn nsẹ Ọlọrun ni gbangba, o dabi ẹni wipe o de inu won, ṣugbọn igbesiaiye fihan wipe opolopo, bi o tilẹ je 'pe nwon nbuỌlorun pelu ete won, ni ongbe ngbe ni okan. O si ma gbo igbe irora okan won.. Awon okunrin wonyi nwa ohun kan bẹni nwọn nfe lati bo ofifo inu wọn pẹlu aini Ọlọrun won.

Arabinrin rẹ ninu Kristi, Maria.

Iwe keji

"Ninu iwe ti mo kọ gbẹhin, mo so fun o nipa ọmọbinrin kan, Varia, ti ko gba Ọlọrun gbọ. Nisisiyi mo kanju lati sọ fun nyin, ẹnyin Olufẹ mi, nipa ayọ wa nla: Varia ti gba Kristi gbo ti o si mọ ayọ ti o wa ninu igbala, oun, nigbakanna, kun fun ibanuje. O kun fun ibanujẹ nitori tẹlẹ o ti nso fun awon eniyan wipe Ọlọrun ko si. Nisisiyi, o ti pinnu lati ṣetutu fun ẹbi rẹ.

Emi ati Varia jọ lo si ibi ti awọn ti ko ni Ọlọrun ti pejọ. Bi o tilẹ jẹ 'pe mo kilọ fun u wipe ki o dakẹ, ofo ni eleyi jasi. Varia lọ emi na si ba a lọ lati wo ohun ti yio ṣẹlẹ. Lẹhin igbati awọn ti ngbe Ijọba Alaṣepọ korin tan (Varia ko ba won ko ninu orin yi), o gba aṣe lati sọrọ. Nigbati o kan lati sọrọ, o jade si arin gbogbo eniyan. Pẹlu igboiya ati pẹlu itara, o jẹri niwaju gbogbo awon ti nwon pejọ nipa Kristi gẹgẹbi

Olugbala rẹ, o si tọrọ idariji lọwọ awọn elegbe rẹ tẹlẹ wipe oju emi oun ti pade tele ati wipe oun ko mọ wipe oun fun ara ara oun nlo sinu iparun ati wipe oun tun nfa awon miran lo be. O bẹ gbogbo awọn ti nwọn pejọ ki nwọn kuro ni ona esẹ ki nwọn si to Kristi wa.

Gbogbo won dake ko si si eniti o di lowo bi o ti nsoro. Nigbati o soro tan, o fi ohun re didara ko orin Onigbagbo ti o wipe: "Oju ko timi lati kede Kristi na ti o ku, lati gbe awon ofin rẹ ati agbara igi agbelebu Re.

Ati lẹhinna ... lehinna, nwon ngbe Varia wa lọ.

Ọjọ kẹsan osu karun odun ni oni je. A ko mọ ohunkohun nipa re. Sugbon Olorun ni agbara lati gba a la. E gbadura!

Iwe keta Marin nyin"

"Lana ojo keji osu kejo odun, mo ba Varia olufe wa soro ni ewon. Okan mi ns'eje nigbati mo ba ronu nipa re. Loto omode ni o si je. Omo odun mokan-din-logun ni o si je. Gẹgebi Onigbagbọ ninu Oluwa, omo owo ni o si je nipa ti emi pelu. Sugbon o feran Oluwa lati inu gbogbo okan re o si lọ lese kanna ni ona ti o lewu. Ebi npa omodebinrin yi. Nigbati a mọ wipe o wa ninu ewon, a bere si fi awon eru ranse si i. Sugbon die ṇiu awon ohun ti a fi ranṣe si i ni o ri gba.

Nigbati mo ri lana, o ru, awo re ti nyipada bẹni nwọn ti lu u gan. Oju re nikan ni o tan pẹlu alafia Olorun ati pelu ayo ti ki ise ti aiye yi.

Beni, enyin olufe mi, owon, awon ti ko tini iriri alafia iyanu Kristi ko le mo ohun ti anso... Sugbon bawo ni ayo awon ti nwon ni alafia yi to .. fun awa ti a wa ninu Kristi, ko si iya na ati arẹ ti o yẹ ki o da wa duro.

Mo bere lati oju ferese ti ati ko rin di, mo ni: "Varia, o ko ha kabamo ohun ti o se bi? O dahun o ni "Rara o, beni ti nwon ba dami silẹ, ngo tun lo lati lo so fun won nipa ife nla ti Kristi. Mase ro wipe mo njiya. Inu mi dun pupọ wipe Oluwa feram mi tobe ti o si fun mi ni ayo lati le ni iforiti nitori oruko Re."

Mo bere wipe ki e gbadura lati okan nyin wa fun u. Boya nwon le ran lo si Siberia. Nwon ti gba awon aso re ati gbogbo ohun ti oni ni ọwọ rẹ. O ti wa di alaini ohunkohun, afi asọ ti o wọ si ara rẹ. Ko ni awọn ẹbi nitorina a nilati ko awọn ohun ti ose pataki julo fun jọ. Mo ti ya owo ti e fi ranse si mi gbẹhin si ọtọ. Ti a ba da Varia pada ngo fun u ni owo yi. Mo ni igbagbọ wipe Ọlọrun yio fun u ni okun ati agbara lati le ni iforiti ni oju iwaju pẹlu ki Ọlorun ki o toju re!

Iwe kẹrin Mariạ nyin"

"Maria mi owon, ni ighehin mo ni aye lati ko 'we si e. Pelu alafia ni a gunle si ... Ago wa je ibuso mewa si ilu. Nko le se apejuwe igbesiaiye wa. Iwo na mo. Mo ni ife lati ko oro die nipa ara mi. Mo dupe lowo Olorun wipe o nfun mi ni ilera ati wipe mo le se ise. Emi ati

arabinrin 'X' ni a fi si ile isona lati sise. Ni ori awon ero ni a ti nsise nibe. Ise na le, beni arabinrin 'X' nse ailera pupo. Sugbon ki ise eleyi ni mo fe ko ninu iwe yi si o.

Okan mi yin Olorun beni mo ndupe bakanna wipe Olorun fi ona igbala han mi nipa re. Nisisiyi ti mo ti wa ni ona yi, igbesiaiye mi ni idi beni mo mo ibi ti ngo lo ati eniti mo ntitori tire jiya. O se ife okan mi lati so fun gbogbo eniyan ki nsi jeri nipa ayo nla ti o wa ninu igbala eyiti mo ni ninu okan mi. Tani o le ya wa kuro ninu ife Olorun ninu Kristi? Ko si eni na beni ko si ohun na. Ewon tabi ijiya Olorun ran si wa, nse ni onfun wa ni okun sii ninu igbagbe re. Okan mi kun fun ayo nitori wipe ore-ofe Olorun kun akunwosile. Nibi ise won nbumi be ni won fi iya je mi beni nwon nfun mi ni ise pupo lati se nitoripe nko le dake, sugbon nse ni mo nso fun gbogbo eniyan ohun ti Oluwa ti se fun mi. O ti so mi di ẹda titun, o ti so emi ti mo wa ni ona iparun di eda titun. Mo ha le dake lehin gbogbo eleyi bi? Rara, emi koje dake lai! Niwon igbati awon ete mi ba ti le soro, ngo jeri fun gbogbo eniyan nipa ife nla Re.

Nigbati a nlo si ago wa, a pade opolopo awon arakunrin ati arabinrin ninu Kristi. O je ohun iyanu gidi wipe o mo nipa ti Emi wipe Omo Olorun ni nwon se nigbati o ba koko ri awon arakunrin ati arabinrin wonyi. Ko di igba ti a ba soro. Nigbati o ba koko ri nwon o ti mo iru eniyan ti nwon je.

Nigbati a nlo si ago, ni ibuso oko oju irin kan, obinrin kan wa, o fun wa ni ounje o si so oro meji pere, oni: "Olorun ye."

Ni irole ojo ti a koko de ibi (ile ti nsu), nwon mu wa lo si ile awon omo ogun ti o wa ni abe ile. A ki awon ti a ba ni ibe bayi pe 'Alafia ki o wa pelu nyin.' Fun ayo nla wa, lati gbogbo koro ile yi ni a ti gbo idahun bayi pe: "A gba nyin pelu alafia." Beni lati ale ojo kini yi oda bi eni wipe arin ebi ni a wa.

Loto, be ni o ri. . Awa ti a gbagbo ninu Kristi gegebi Olugbala wa po ni ibi yi. Awon Onigbagbo ibi yi ju idaji gbogbo awon elewon ibi yi lo. Larin wa, awon ti o le korin gidi ati awon ti nwon le wasu ihinrere gidi wa. Ni irole, nigbati gbogbo wa ba pejo lehin ise ase-kara. Ohun ayo gidi ni oje lati lo igba die ninu adura ni ese Olugbala wa. Pelu Kristi, ominira wa ni ibi gbogbo . Ni ibiyi ni mo ti ko opolopo awon orin elemi ti o gbadun beni ni ojojumo ni Olorun nfun mi ni oro Re sii. Ni igba ti mo pe omo odun mokan-le-logun, mo se ajoyo ojo-ibi Kristi fun igba kini. Nko ni je gbagbe ojo iyanu yi lai! A nilati se ise titi ile fi su ni ojo yi. Sugbon lara awon arakunrin wa lo si odo ti o wa nitosi bi o tile ri be. Nibe ni nwon gbe fo omi didilo wa ni ori omi, nwon si toju ibe ni imura fun ale nibiti - gegebi oro Olorun - a se iribomi fun emi ati awon arakunrin meje. Ah, inu mi ma dun o, beni o si wu mi'pe ki iwo, Maria le wa ni ibe pelu mi, ki nle setutu bi o tile se die, nipa ife mi si o fun awon aida ti mo se si o sehin. Sugbon Olorun fi enikokan wa si bi ti a wa beni a nilati duro

sînsin si ibi ti Olorun fi wa si.

Ki gbogbo awon omo ebi Olorun. Olorun yio fi ibukun nla si ise ti e jo nse, gegebi o ti bukun emi na. Ka Iwe Heberu 12: 1-3.

Gbogbo awon ara wa ki o beni inu won dun wipe igbagbo re ninu Olorun lágbara ati wipe o nfi iyin fun Olorun ninu ijiya re laisimi. Ti o ba ko iwe si awon ti o ku, ba wa ki won.

Tire, Vaira"

Iwe karun.

"Maria mi owon. Ni igbehin, mo ti ri aye ati ko awon oro die yi si o. Mo le so fun e, olufe mi kansoso, wipe, nipa ore-ofe Olorun, emi ati arabinrin 'X' wa ni ilera a si wa ni alafia. Nisisiyi ... ni a wa . Nwon fi wa ranse si... a si wa ni ibe.

Mo dupe lowo re fun itoju ti o ntoju mi gegebi iya. Gbogbo ohun ti o pese fun wa ni a ri gba. Mo dupe lowo re fun ohun ti ose pataki julo, Bibeli. Mo dupe lowo gbogbo awon to ku, nigbati o ba si ko jwe si won, ba mi ki won ki o si bami dupe lowo won bakanna fun ohun ti nwon ti se fun mi.

Lati igba ti Olorun ti fi ijinle ife Re mimo han mi mo ka ara mi kun eniti inu re dun ju ni gbogbo aiye. Mo ka awon inunibini ti mo nilati foriti kun akanse ore-ofe. Mo dupe wipe Oluwa mi fun mi ni ayo nla lati jiya fun oun lati ibere igbagbo mi. Gbogbo nyin, e gbadura fun mi wipe ki nle je oloto si Oluwa titi de opin.

Ki Oluwa ki o pa gbogbo nyin mo ki o si fun nyin ni agbara fun ija mimo na.

Emi ati arabinrin 'X' fi enu ko gbogbo nyin lenu. Nigbati a ba ran wa lo si.. boya a o ni anfani lati tun ko iwe si nyin. E ma se yonu nipa wa. Inu wa dun a si kun fun ayo nitori esan wa ni orun tobi. Matt. 5:11-12.

Tire, Varia"

Eyi ni iwe ikehin lati odo Varia - odomobinrin Ijoba Alasepo ti o gba Kristi, ti o jeri nipa re ti a si dajo ewon pelu ise asekara bi eru fun. Ko si eniti o tun gburo re, sugbon ife re ti o lewa ati ijeri fun Kristi re yi fi ewa ti emi Ijo Abele ti o njiya ti o si je oloto ni idameta aiye ti o wa ni abe eto Ijoba Alasepo han

## ORI KEJE

## BI AWON ONIGBAGBO OLOMINIRA IWO ORUN SE LE RAN WA LOWO

### ISE TI A RAN MI SI NYIN LATI IJO ABELE

Nwon ti pe mi ni"Ohun Ijo Abele", Nko ka ara mi ye lati je ohun Eya Ara Kristi ti o ni ola bayi.

Bi o ti wu ki o ri, mo saju apa kan Ijo Abele fun opolopo odun ni awon ile Ijoba Alasepo. Nipa ise iyanu ni mo fi ye odun merinla idaloro ninu ewon ninu eyiti mo wa ni inu "yara iku" fun odun meji. Nipa ise iyanu ti o tun tobi ju eleyi lo, Olorun ri wipe o ye lati yo mi kuro ninu ewon yi, ki o si mu mi wa si Iwo Orun lati soro si Ijo ti o wa ni ominira.

Mo nsoro fun awon elegbe mi ti nwon wa ninu iboji ti ko ni oye ti ko si ni oruko. Mo nsoro fun awon elegbe mi ti nwon nse ipade ni ikoko ninu igbo, ninu awon yara ti o wa ni abe ile tabi eyi ti o wa ni abe orule ati awon bebe miran gbogbo.

Nwon pinnu ninu Ijo Abele ti Rumania wipe oye ki nkuro ni ilu mi, ki nsi mu irohin wa fun awon Onigbagbo ti o wa ni ominira ni gbogbo aiye. Nipa ise iyanu. o ti wa sese fun mi lati jade, mo si nmu ase ti awon ti nwon ku

lehin, ti nwon nsise, ti nwon nfi emi won wu ewu, ti nwon njiya ti nwon si nku ni awon ilu Ijoba Alasepo, pa fun mi se.

Ise ti nwon ran mi ti mo mu jade lati Ijo Abele ni wipe.

"E mase ko wa sile!"

"E ma gbagbe wa!"

"E mase ko 'we ikosile si wa!"

"E fun wa ni awon irin ise ti a nilo!"

A o san iyekiye ti o ba na wa lati lo won!"

Ise ti a pa ase re fun mi lati so fun nyin niyi.

Mo nsoro fun Ijo ti a pa - lenu mo, Ijo Abele, ijo ti o "ya odi", ti ko ni ohun lati soro.

E gbe awon igbe awon arakunrin ati arabinrin nyin ni awon ile Ijoba Alasepo! Nwon ko bere fun ajabo, ibi ailewu tabi igbesi-aiye ti o rorun. Nwon kan nbere fun awon irini ise lati ko oju ija si oro aigbagbo ninu Olorun ti nwon nfun awon odo won - iran ojo iwaju. Nwon nbere fun Bibeli lati lo fun itanka oro Olorun. Bawo ni nwon se le tan oro Olorun ka ti nwon ko ba ni Bibeli?

Ijo Abele dabi Onisegun Onise abe eyiti o rin irinajo pelu oko oju irin. Oko oju irin yi kolu oko oju irin miran ti o fi je 'pe ogorun aimoye eniyan ti nwon fi ara pa ti nwon si nku lo ni nwon wa ni ile. Onisegun Onise abe yi bere si rin ni arin awon ti nwon nku lo yi, o si nkigbe pe: "Oiba se wipe awon irin ise mi wa nibi!... Oiba se wipe awon irin ise mi wa nibi!" Pelu awon irin ise abe re yi iba sese fun u lati gba oplopo eniyan la. O se ife re ... sugbon ko ni awon irin ise re lowo. Iru ipo

ti Ijo Abele duro na niyi. O nfe lati sa gbogbo ipa re. O nfe lati fi emi re sile nitori ise yi! O nfe lati fi opolopo odun wu ewu ninu ewon Ijoba Alasepo! Sugbon asan ni gbogbo ife re wonyi jasi ti koba ni irin ise ti yio fi se ise na. Ebe Ijo Abele ti o se oloto ti o si ni iforiti si enyin, ti e wa ni ominira ni 'pe: E fun wa ni irin ise - awon oro ihinrere, Bibeli, iwe kika fun awon Onigbagbo, iranlowo na - awa yio si se eyiti o ku."

## BI AWON ONIGBAGBO TI NWON WA NI OMINIRA SE LE SE IRANLOWO

Gbogbo awon Onigbagbo ti nwon wa ni ominira ni nwon le se iranlowo ni awon ona wonyi:-

Awon ti ko gba Olorun gbo wonyi je awon ti ko gba orisun aiye ti a ko ri gbo. Nwon ko ni ogbon fun ohun ti se ijinle ni agbaiye ati ni igbesiaiye. Awon Onigbagbo le ran won lowo ni ona ti o dara julo nipa wipe ki awon fun ara won ma rin nipa igbagbo ki ise nipa ohun ti a ri, ki awon fun ara won si ma gbe igbeaiye idapo pelu Olorun ti a ko ri.

Nwon le ran wa lowo julo nipa sisaju nipa gbigba adura ki awon ti nwon ngbe Ijoba Alasepo le ri igbala. O le da bi enipe iru adura bayi je ohun yepere. A gbadura fun awon ti ngbe Ijoba Alasepo, ni ojo ti o ba si tele, idaloro ti nwon nfun wa a tun ju bi o ti ri ki a to gbadura fun won. Sugbon adura Oluwa wa Jesu Kristi na je ohun yepere. Nwon kan A mo agbelebu lehin adura. Sugbon ni ojo die lehin

igba na, nwon fi owo lu aiya won pe egberun marun si gba Kristi gbo ni ojo kan. Fun awon to ku na, adura yi ko sonu. Adura ti ko ba je itewogba nipa eniti a ngbadura yi fun, yio pada si o pelu ibukun nla yio si wa je ifibu fun eniti o ngba adura na. Ni mimu oro Kristi se, emi ati opolopo awon Onigbagbo ni a ma ngbadura fun Hitler ati awon eniyan re. O si dami loju wipe awon adura wa se iranlowo lati segun re gegebi awon ota ibon awon omo-ogun ore.

A nilati feran awon aldugbo wa bi ara wa. Aladugbo wa ni awon ti ngbe Ijoba Alasepo je gegebi elomiran ti je.

Awon ti ngbe Ijoba Alasepo ni abajade aimu oro Kristi se ti o wipe: "Mo wa lati wa fun nyin ni iye ni opo". Awon Onigbagbo lo ti mu ki iye yi wa ni opo fun gbogbo eniyan. Nwon ti fi awon elomiran sile ni eti ohun ti o se pataki ni igbe-aiye. Awon wonyi ti se ote, awon ni nwon si wa da Ijoba Alasepo sile. Awon ni aisoto iwa gbogbo eniyan ma nje. Nisisiyi nwon ti wa kun fun ikoro ati ika. A nilati doju ija ko won. Sugbon awon Onigbagbo, bi nwon tile doju ija ko ota, mo itumo ife, nwon a si feran ota yi.

A ko saini ebi wipe awon miran ngbe Ijoba Alasepo. Bi o tile kere, a jebi aise ise wa.

Fun eleyi, a nilati setutu nipa fifi ife han si won (eyiti ose ohun ti o yato patapata si wipe ki a kan fe won) ki a si ma gbadura fun won.

Ko je nkan yepere loju mi lati gbagbo wipe ife nikan le yanju isoro awon Ijoba Ala-

sepo. Nko ni gba awon alase ilu kan ni iyanju wipe ki won yanju isoro dia egbe awon ehanna sile nipa ife nikan. Awon Olopa, adajo ati ewon Ti awon ehanna ko ba ronupiwada, a nilati so won si ewon. Nko ni lo oro Onigbagbo nipa ife lati doju ija ko awon ti nwon ngbe Ijoba Alasepo, nitori a ri wipe ehanna ni awon na ti o gba gbogbo ilu kan. Awon ehanna a ma ji apo owo, nwon a ma ji gbogbo ilu. Sugbon Olusoaguntan ati Kristiani kokan ni lati sa ipa won lati mu awon omo egbe Ijoba alasepo wa si odo Kristi, boti wu ki ese poto, ati awon alaimokan to wa larin won. O ye ki a gbadura fun pelu oye.

## NI KIAKIA NI NWON NFE AWON BIBELI ATI IWE IHINRERE

Ni ona keji, awon Onigbagbo ti nwon wa ni ominira le se iranlowo.

Awon ona wa ti a le fi ko won lo si awon ile Ijoba Alasepo lai si ewon. Lati igbati mo ti jade wa, mo ti fi opolopo ranse, ti o si ti de ohun ni alafia. Ona wa dajudaju lati fi won ranse, ti o ba kan se wipe enyin Onigbagbo ti e wa ni ominira, yio pese awon nkan wonyi fun awon arakunrin ati arabinrin nhin ti nwon wa ni Ijo Abele. Nigbati mo fi wa ni Rumania, emi fun ara mi gba opolopo Bibeli ti a ko wo ilu nipa awon ona kan. Ko si oro wipe bawo ni ao se fi nwon ranse? Ohun ti o wa ni ibe ni wipe ki enyin pese won.

Nwon nfe awon nkan wonyi ni ti ajaku akata. Ogunlogo awon Onigbagbo ni nwon ko ti iri Bibeli ati awon iwe ihinrere fun ogun odun si adota odun ni Russia ati awon ilu ti nwon yi ka.

Awon okunrin meji lati abule kan wa si ile mi ni ojo kan. Nwon wa lati abule nwon wa ma nse ise atule, ni gbogbo akoko otutu nigbati gbogbo ile ba le koko ti omi inu ile di, lati re ri owo die tujo ti nwon si le fi ra Bibeli ti o ti gbo ti o si ti ya ki nwon si le mu pada lo si abule won. Nitoripe mo ri awon Bibeli kan gba lati Amerika, o sese fun mi lati fun nwon ni Bibeli titun, ki ise eyiti o ti gbo ti o si ti ya. O da bi eni wipe nwon nla ala ni! Nwon gbiyanju lati san owo fun mi lati inu owo ti nwon gba fun itule ti nwon se. Mo ko owo won, won si pada lo si abule won pelu Bibeli yi. Ni ojo die lehin igbana, mo ri iwe kan gba ti nwon ko pelu ekunrere ayo, nwon si fi dupe lowo mi fun oro Olorun yi. Ogun awon ara abule yi ni nwon fi owo si iwe yi! Nwon ti fi ogbongbon pin Bibeli yi si ona ogbon, nwon si nparo won larin ara won!

O je ohun ibanuje lati gbo wipe eniyan Russia kan ti o ntoro oju iwe kan inu Bibeli. O nbo okan re lati inu oju iwe Bibeli yi. Pelu ayo ni nwon fi nfi malu tabi ewure fun eniyan lati le gba Bibeli ni owo re. Okunrin kan ti mo mo ta oruka igbeyawo re lati le fi gba Majemu Titun ti o ti gbo. Awon omo wa ko ti ri awon iwe pelebe ti a fi nki eniyan ku odun keresimesi ri. Ti nwon ba ri okan, gbogbo awon omo abule ni yio sogba yi agbalagba ti o ba mu dani.

Agbalagba yi a si se alaye fun won nipa Jesu nigbati oje omo-owo, ati wundia mimo ati lehin eyi yio wa so fun won nipa itan Kristi ati igbala. Gbogbo iwonyi... lati inu iwe pelebe ihinrere ati iwe awon Onigbagbo ranse. Ona kan ni eyi ti e le fi se iranlowo.

Ni ona keta, a nilati te awon akanse iwe ti yio tako gbogbo oro aigbagbo ninu Olorun ti nwon nfi ko awon omode lati A.B.D. titi de ile eko giga. Awon ti ngbe Ijoba Alasepo yi ko iwe ti yio to awon eniyan si aigbagbo ninu Olorun. Ohun ni nwon npe ni "Bibeli" D.. ni ibere re, nwon si nko won ni ijinle re sii bi nwon ti ntesiwaju si. Bibeli" ibi yi a ma tele omode bi o ba ti ndagba si ti o si ntesiwaju si - yio si ma fun u ni oro aigbagbo ninu Olorun yi bi o ti ntesiwaju si. Awon Onigbagbo ni agbaiye ko iti te iwe kankan jade ni idahun si iwe ti nto ni ni ona aigbagbo ninu Olorun yi. A le se, beni a nilati te iwe yi jade ki a si fi ranse ni idahun si awon eko oro aigbagbo ninu Olorun wonyi. A nilati se eleyi ni esekese, nitori Ijo Abele ko ni iwe ti o le fun awon odo ti iwe yi nfun ni oro. A de owo awon Ijo Abele si ehin won titi yio fi ri awon iwe bawonyi ti a te ni orisisirisi ede awon ilu Ijoba Alasepo.

Awon odo wa ti nwon nfun ni oro yi nilati ri idahun - idahun Olorun - idahun Onigbagbo - idahun wa! Ohun miran ni eyi ti e le se iranlowo nipa re, nipa sise iranlowo lati pese iru awon iwe bawonyi gegebi idahun si iwe ti nto ni ni ona aigbagbo ninu Olorun yi - awon iwe odo ti o ni aworan ninu ati Bibeli awon omode.

Ohun ekerin ti a nilati se ni lati fi "owo-sowopo" pelu awon omo egbe Ijo Abele ki a si fun nwon ni iranlowo nipa ti owo lati le jeki nwon le lo lati ibikan si ekeji lati ma wasu ihinrere ni enikokan. Ni akoko yi, opolopo ninu won ni a "de mole" si ile won nitori aisi owo ti nwon le fi wo oko ati fun ounje nigbati nwon ba nrin-irinajo. Nipa be, nwon kuna bi oko, nwon ko le lo kakiri nigbati awon eniyan abule ti o to bi ogun si ogbon ibuso si ibiti nwon wa a ma pe won lati wa ba won se ipade ikoko, sugbon ofo ni eleyi ja si, ti a ba le fun won ni owo diedie (bi Naira mewa si ogun niar) ni osu, a le "tu" won sile lati dahun awon ipe wonyi ati pe ki nwon le ma lo si awon ilu jinjin pelu oro Olorun.

Awon Alufa teleri, ti nwon ti fi igba kan wa ni ewon nitori igbagbo won nfi itara fe lati wasu ihinrere, nwon nfi itara ni ife awon ti o nsegbe, sugbon nwon ko ni ona ti nwon le gba lati mu ihinrere yi lo si awon ilu ati ileto. Naira die ni ososu yio jeki nwon ni ona ati le lo.

Awon arakunrin ati arabinrin Onigbagbo na nfe iranlowo. Nitori wipe nwon je Onigbagbo pelu iroju ni owo ti nwon ngba fi nto won lati jeun, ko si ku ohunkohun fun won lati le fi wo oko lo lati abule de abule, lati ilu de ilu lati wasu ihinrere. "Ise Iyanu" ti Naira die ni osu yio se fun won ni eyi.

Awon Alufa Ijo ti Ijoba da sile, ti nwon nse awon ise Olorun ni ikoko ninu ewu nla nilati ni owo ti a o pese fun won ni ona ikoko fun awon ise bawonyi. "Owo osu" won ti Ijoba Alasepo nfun won kere pupo ju. Ife awon

Alufa wonyi ni lati fi ominira won wu ewu nipa kiko eti didi si awon ofin Ijoba Alasepo, ki nwon si ma wasu fun awon omode, odo ati awon agbalagba ni awon ipade ikoko, beni eleyi ko to. Nwon nilati ni ona ti nwon o fi se ise Olorun yi ni ikoko ti yio mu eso wa.

Naira mewa tabi ogun Naira ni osu yio ran iru awon omo egbe Ijo Abele yi lowo lati le fi tan ihinrere yi ka daradara. Ona miran ni eyi ti o fi le ran Ijo Abele lowo.

Lehin eyi, a nilati wasu ihinrere si awon ilu Ijoba Alasepo nipa ero gboungboun. Ni lilo awon ibi isoro si gboungboun ni apa aiye nibiti ominira wa, a le bo Ijo Abele ti ebi ounje iye npa, nipa ti emi. Nitoripe Ijoba Alasepo fun ara won nsoro sinu afefe fun awon eniyan lati gbo pelu iranlowo ero gboungboun. Ogunlogo awon eniyan Russia ati awon eniyan miran ti a ko ni eru ni nwon ni ero gboungboun nipa eyi ti nwon le gbo ohun ti Ijoba ba fe so fun won. Ilekun si sile nisisiyi lati soro sinu afefe nipa ero fun awon eniyan awon ilu Ijoba Alasepo lati gbo. A nilati tan ise yi ka. Ijoba Alasepo nilati ni ounje emi ti awon ikede ori ero gboungboun wonyi nmu wa. Ona miran tun ni eyi ti o fi le ran Ijo Abele lowo fun awon ile Ijoba Alasepo.

## ORO IBINUJE AWON EBI AWON AJERIKU ONIGBAGBO

A nilati pese iranlowo fun awon ebi awon ajeriku Onigbagbo. Egberun aimoye awon ebi bawonyi ni nwon jiya ni ona ibinuje ti ko se fi

enu so. Nigbati a ba mu omo egbe Ijo Abele kani, ohun ibanileru nla a si de ba ebi re. Oje ohun ti o lodi si ofin gidigidi fun enikan lati ran awon ebi bawonyi lowo. Ohun ti awon ti ngbe Ijoba Alasepo yi gbero gidi ni lati le fi je ki iya iyawo ati awon omo ti okunrin bayi ba fi sile le po si. Nigbati Onigbagbo kan ba lo si ewon - ati ni opolopo igba ti a ba lo pa abi lo daloro - iya na sese bere ni. Awon ebi re yio jiya pelu ailopin. Mo le so ohun kan ti o da mi loju, wipe ti gbogbo orisirisi awon Onigbagbo to wa ni ominira ni ko ba ti fi ohun iranlowo ranse si emi ati ebi mi ni, a ko ba ti le ye rara de bi ti ao wa ni arin nyin lati ko awon oro wonyi!

Ni akoko yi, nwon ti tun nmu awon Onigbagbo lopolopo beni rogbodiyan ti tun sele ni arin awon Onigbagbo ni Russia ati ni awon ibomiran. Ni igbagbogbo ni a ti tun pa awon Onigbagbo. Bi o tile je 'pe nwon lo si inu iboji ati si inu esan won, igbesiaiye ti awon ebi won ngbe bani leru gidi. A le ran won lowo beni a nilati ran won lowo. Dajudaju, a nilati ran awon eniyan India ati Afrika ti ebi npa lowo. Sugbon tani eni ti o nfe iranlowo awon Onigbagbo julo bikose awon ebi awon ti o ti ku fu Kristi tabi ti a daloro ni inu awon ewon Ijoba Alasepo nitori igbagbo won?

Lati igba ti a ti da mi sile, Egbe Onigbagbo awon Oyinbo ti nwon nsise Olorun ti fi ohun iranlowo pupo ranse si ebi awon ajeriku Onigbagbo. Ohun ti a ti se kere ti a ba fi we ohun ti a le se pelu iranlowo re.

Gegebi omo egbe Ijoba Abele ti oti ye ti o

si jabo mo ti mu ise ti a ran mi si e wa, ebe lati odo awon ara mi ti mo ti fi sile sehin.

Nwon ti ran mi lati je ise yi lati odo won si nyin. Ni ona iyanu mo tiye lati je ise na.

Mo ti so fun nyin nipa ikanju ti o wa ninu wipe ki a se nipa Kristi ni awon ile Ijoba Alasepo. Mo ti so nipa ikanju ti o wa ninu riran awon ebi awon ajeriku Onigbagbo lowo. Mo ti so fun nyin nipa awon ona ti e le fi ran Ijo Abele lowo lati tan ihinrere yi ka.

Nigbati a na mi ni atelese, ahon mike. Nitori idi wo ni ahon mi se ke? Oun sa ko ni a na. O ke nitori wipe ati ahon ati ese ara kan ni nwon je. Bakanna ni enyin Onigbagbo ti e wa ni ominira je apa ara kanna ti Kristi eyi ti nwon nlu bayi ni awon ewon Ijoba Alasepo, ti nwon si nku fun Kristi.

E ko ha mo irora wa lara bi?

Ijo isaju ninu gbogbo ewa re, irubo ati iya-ara won soto fun Olorun ti tun pada wa s'aiye ni awon ile Ijoba Alasepo.

Nigbati Oluwa wa Jesu Kristi nje irora nigbati o ngbadura ninu ogba Gethsemane, Peteru, Jakobu ati Johannu ko jinna si odo ibi ti Jesu wa ti o ti nja ijakadi ti o tobi julo ninu iwe itan - sugbon nwon sun lo fonfon. Melo ninu ohun ti o kan nyin gegebi Onigbagbo ati itore anu ni e dari si ona itura Ijo ajeriku? E bi alufa nyin lati ran awon arakunrin ati arabinrin nyin ti o wa ni ewon lowo.

Gbogbo igboya ati kiku nitori Kristi ti Ijo isaju tun nsele nisisiyi ninu awon ewon - awon Ijo ti nwon wa ni ominira si nsun.

Awọn ẹlẹgbẹ wa ni ohun, ni awọn nikan ati lai si iranlọwọ nja ija ti o le ju ti o si nfẹ igboiya julọ ni akoko wa yi, eyiti o dọgba pẹlu iṣẹ akoni, igboiya ati iya ara eni soto fun Olorun ti Ijọ isaju. Bẹni Ijọ ti o wa ni ominira si nsunlọ ni igbagbe ijakadi nwọn ati irora nwọn, gẹgẹbi Peteru, Jakobu ati Johannu ti sun lọ ni wakati irora Olugbala wọn.

Ṣe ẹnyin na yio ha tun sun bi nigbati Ijọ Abẹlẹ, awọn ara nyin ninu Kristi njiya ti nwọn si nnikan ja fun ihinrere?

Ẹnyin yio ha gbọ iṣẹ ti a ran mi bi:

"Ẹ ranti wa, e ran wa lowo"

"Ẹ mase ko wa sile!

Nisisiyi mo ti jẹ iṣẹ ti a ran mi lati ọdọ Ijọ Abẹle ti nwọn se oloto ti nwọn si nku nitori Kristi ni awọn ilu Ijọba Alasepo - lati ọdọ awọn arakunrin ati arabinrin nyin ti nwọn njiya ninu ide eto Ijọba Alasepo ti ko gba Olorun gbo.

*E le fi ibere ati ere atinuwa nyin ranse si :-*

**Voice of the Christian Martyrs**
**P. O. Box 476**
**Agege, Lagos**
**Nigeria**



RICHARD WURMBRAND, eniti ara re kụn fun ogbe ti idaloro ati ijiya odun merinla ninu ogba ewon Ijọba Olori-ojon (Commuists) je eleri igboya ati igbagbo ti o duro sinsin ti ogoro awon onigbagbo ti a ti pin niya pelu awon ololufe won, ti a ti je niya, ti a si ti lu ninu ara sugbon ki ise ninu emi, Nwon ntesiwaju ninu igbagbo, Bi won ti nfarada.

# IJIYA FUN KRISTI